**Ǹjẹ́ a le se apejuwe Ọlọ́run gege bi "onítẹ̀nbẹ̀lẹ̀kun" tabi "agbani-nímọ̀ràn burúkú" laarin gbogbo won? (Makara)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Habakuku 1:13 –** Mimo ni oju re, o ke le wo ibi o ko le gba ona ti ko to.
**Sakaraya 8:17 –** E ma maa gbero ibi si arayin e ma si feran ibura eke nitori gbogbo nnkan wonyi ni mo koriira.

---

**Al-i İmran 3:54 –** Nwon pete, Olohun si ja ete won, beni Olohun ni olubori awon apete.
**Ra'd 13:42 –** Dajudaju awon eniti o siwaju won ti pete sugbon Olohun lo ni gbogbo ewe-wa patapata.
**Kíyèsí:** NinuBíbélì 'tembelekun' ati 'simoran buruku' je ohunbúburúatipe awon ise yii je iwa ti a fi moSátánì, ki I seỌlọ́run: Cf. Gen. 3:1, Est. 9:25, Ps. 21:11, OD. 36:4, Pro. 1:30, 2Kor. 11:13-15, Efe. 6:11, 1Pet 5:8-9, 2 Johannu 1:7.

# 46.

**Se Ọlọ́runlo ma a ni da rudurudu, ikorira ati ainife sele laarin awon àwọn èèyàn tí ìgbàgbọ́ wọn se ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Jeremaya 29:11 –** Nitori pe mom o ero ti mo n gba si yin, ero alaafia ni, ki I se ero ibi. N oo mu ki ojo ola dara fun yin,n oo si fun yin ni ireti.
**Habakuku 1:13 –** Oju re mo ju eniti iwo ibi lo, iwo ko si le wo iwa-ika nitori kini iwo ha se now awon ti nhuwa arekereke, ti o si pa enu re mo nigbati eni-buburu je eniti ise olododo ju u run?

---

**Bakara 2:10** – Arun mbe ninu okan won nitorina Olohun se alekun arun na fun won iya elero mbe fun won nitoripe nwon tin puro.
**Nisa 4:88 –** Enyin ha nfe lati fi mo ona, eni ti Olohun fi sile ninu isina bi?
**Maide 5:14 –** Ati lati odo awon eniti nwipe: Nasar ani awia se, Awa se majemu pelu won sugbon nwon gbagbe apakan ninu ohuin ti a ran won leti re nitorina Awa da ota si arin won ati ikorira titi di ojo igbende.
**Maide 5:64 –** Awa si da ota ati ikorira si arin won titi di ojo igbende.

## 47.

**Se ohun ti Ọlọ́runní lọ́kànni lati mu ki okan awon eniyan kan le latimú wọn ṣáko lọ̀**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 18:11-14 –** Nitori Omo-Eniyan wa lati gba awon ti o ti sonu la. 14. Bee gan-an ni ki se ife baba yin ti n be ni orun pe ki okan ninu awon kekere wonyi ki o segbe.
**1 Timoti 2:3-4** Iru adura bayi dara,o si se itewogba niwaju Olorun Olugbal wa.

---

**Baqara 2:7, 15 & 26** – Olohun ti fi (odidi)di okan won ati igboro won ati igboro won,ebibo sib o iriran won, iya ti o tobi sim be fun won.
**Nisa 4:119 -** Dajudaju emi yio si won lona emi yio mo gba erokero,emi yio ma foro won tobe ti nwon yio ma ge eti awon eran osin, emi yio si foro won tin won yio ma yi eda Olohun pada.
**A'raf 7:186 –** Eniti Olohun ba fi sile ninu isina, ko si afini mona (miran) fun u, Atipe yio fi won sile ki nwon ma poyi ninu agbere won.

## 48.

**Se iwa Ọlọ́run ati ihuwasi re je ti ìwàǹwára àti ìkùgìrì  tabi ya ìpátá**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Nọmba 23:19 -** Olrun ko jo eniyan ti maa n puro bee ni ki I se eniyan ti maa n yi okan pada. Ohun tio ba ti so ni yoo se bi o ba si soro yoo ri bee.
**Orin Dafidi 119:90 -** Otito re wa lati irandiran; o ti fi idi aye mule osi doru.
**Malaki 3:6** OLUWA awon omo ogun ni "Nitori pe emi OLUWA ki yipada, ni a ko fi tii run eyin omo jakobu patapata.
**2 Timoti 2:13 -**Nitori Adamu ni a koko da ki a to da Efa.
**Titus 1:2** – ati ireti to iye ainipekun ti Olorun ti ki i puro ti seleri lati ayeraye.

---

**Hud 11:106-108 -** Nigbana ki e ria won tin won se ori-buburu, nwon o si ma be ninu ina; kikuru wa fun won ninu re kike irora.Nwon o si wa nibe lopin igbati sanma ati ile ba wa ayafi ohun ti Oluwa re ba fe.
**Hajj 22:14 –** Dajudaju Olohun yio fiawon onigbagbo ododo tin won si nse ise rere wo inu awon ogba idera ti awon odo yio ma san nisale re Dajudaju Olohun nse ohun ti O ba fe.
**Fatir 35:8 –** Nje eniti a se ise buru re ni oso fun u ti o si nwo o si sise rere? Nitoro dajudaju Olohun ma fi eniti O ba fe sile ninu isina A si ma lo emi re danu niti ibanuje lorinwon. Dajudaju Olohun na ti mo ohun tin won nse nise.
**Buruj 85:16 –** Ase-ohun ti o-wu U ni.

## 49.

**Se eewo ni fun eniyan lati dobale tabi foribale fun Olorun miran yato siỌlọ́run funra re?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ẹkisodu 20:2-5 –** Emi ni Oluwa Olurun yin ti o mu yin jade lati ile ijipiti ni oko eru ti e wa.
**Diutaronomi 5:7-9 –** " 'O ko gbodo bo orisa emi OLUWA ni ki o maa sin. O ko gbodo ya erekere Kankan fun ara re ki baa je ni aworan ohunkohun ti o w ani oju orun tabi ti ohun ti o wa lori ile tabi ti ohun ti o wa lori ile tabi eyi ti o wa ninu omi ni abe ile.O ko gbodo trriba fun won bee ni o kogbodo sin won, nitori pe Olorun tii maa n jowu ni emi OLUWA Olorun re.Emi a maa fi iya ese baba je omo ati omo omo titi de iran keta ati iran kerin ninu awon ti won koriira mi.
**Ìfihàn 22:8-9 –** Emi johanu ni mo gbo nnkan wonyi, ti mo si ri won. Nigba ti mo gbo, ti mo si ri won mo dojubole niwaju angeli tio o fi won han mi. Sugbon o so fun mi pe Eewo! Ma se bee! Iranse elegbe re, ni emi naa ati awon wolii, arakunrin re, ati awon ti won ti pa awon oro iwe yii mo. Olorun ni ki o juba."

---

**İsra 17:23 -** Atipe Oluwas re palase pe: E ko gbodo sin kinikan ayafi On nikan
**Zariyat 51:56 –** Atipe Emi ko se eda alijonu ati enia lasan ayafi ki nwon le ma sin Mi.

## 50.

**ṣe Ọlọ́run so oro ti o yato si ofin ati ilana ayeraye ti a ti gbekale tele tele ti o pa ase fun gbogbo ángèlì pe ki won wole fun Adamu"?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Aisaya 14:12-14 -** 12Báwo ni ìwọ ṣe ṣubú lulẹ̀ láti ọ̀run wá, ìwọ ìràwọ̀ òwúrọ̀, ọmọ òwúrọ̀ náà! 13. Èmi yóò gòkè lọ sí ọ̀run;Èmi yóò gbé ìtẹ́ mi sókè ga ju àwọn ìràwọ̀ Ọlọ́run 14. Èmi yóò ṣe ara mi gẹ́gẹ́ bí Ọgá-ògo.
**Isikiẹli 28:11-19 - '**Ìwọ jẹ́ àpẹẹrẹ ìjẹ́pípé náà, títí a fi rí àìṣedéédéé ní inú rẹ. Ọkàn rẹ gbéraga, nítorí ẹwà rẹ.Ìwọ sì ba ọgbọ́n rẹ jẹ́,nítorí dídára rẹ.

---

**Bakara 2:31-34 –** Nigba ti awa s iwi fun awon malaika wipe e terbia fun Adama,nwon si terbia ayafi Iblisu nikan
**İsra 17:61-65 –** Ati nigba ti a wi fun awon malaika pe e terbia fun Adama won si terbia ayafi Iblis o si wipe Emi ha le terbia fun eni ti Ire fi amo da?

# Ẹmí mímọ, Angèlì, Ẹmí èṣù ati Sátánì

## 51.

Se a gba "Ẹ̀mí mímọ̌" gege bi Ọlọrun? (Ruh-ül Kudüs)

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Orin Dafidi 139:7 –** Eni ti o da awon imole nla, nitori pe ife re ti ki i ye wa titi lae
**Johanu 4:24** – Emini olurun awon ti o ba n sin in nilati sin in mi ati ni otito".
**Ìṣe Àwọn Aposteli 5:3-4** – Peteru ba bi I pe "Anania,ki lo de ti satani fi gba o lokan ti o fi se ekesi Emi Mimo,ti ofi yo sile ninu owo ti o ri lori ile naa? Ki o to ta ile naa, mo sebi tire ni? Nigba ti o ta a tan, mo sebi o ni ase lori owo ti o ta a? Kilode ti o gbero iru nnkan yii? Ki I se eniyan ni oseke si, Olorun ni."

---

**Bakara 2:87 & 253 –** A wa fun Musa ni Tiran a Awa si fi awon ojise tele ara won lehin re, A si fun Isa omo M ariyama ni alaye oro to han, a si fi emi mimo ran a lowo . A si fun Isa omo Maryam ni awon ami ti o yanju, A si ran a lowo pelu emi mimo.
**Maide 5:110 –** Nigbati Oluhun wipe; iwo Isa omo Mariyamo, ranti ike Mi lori re lori iya re, nigbati Emi fi emi mimo ran o lowo ;
**Kíyèsí:**ibi mẹ̀tàléláàádọ́fà ni o wa ninu Bíbélì nibi tia ti se afihan Ẹ̀mí mímọ̌ bi I Ọlọ́run.

## 52.

**ṣeẸ̀mí mímọ̌ ni ágbára lati seda nnkan?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Jẹnẹsisi 1:1-2 –** Ni ibere nigbati Olorun da orun ati aye,aye ri juujuu, o si sofo. Ibu omi bo gbogbo aye, gbogbo re sokunkun biribiri, emi Olorun si n rababa loju omi.
**Jobu 26:13 –** O fi afefe se oju orun losoo; owo lo fi pa ejo ti n fo.
**Jobu 33:4 -|**Emi Olorun ni o da mi,eemi Olodumare ni o fun mi ni iye.
**Orin Dafidi 104:30 –** Nigbati o ran Emi ro jade,won di eda alaaye,o si so ori ile di otun.

---

**Maide 5:110, 116 & 118 -** Nigbati Oluhun wipe; iwo Isa omo Mariyamo, ranti ike Mi lori re lori iya re, nigbati Emi fi emi mimo ran o lowo ; iwo si nba awon enia soro ni omode ati ni agbalagba, ati nigbati Emi fi Tira na mo o ati ogbon ati At-Taorata ati Injila ati nigbati Emi iwo si now afoju ati adete san pelu ase Mi; ati nigbati Emi ka owo awon omo Israila ko lodo re nigbati iwo w aba won pelu alaye, sugbon awon ti o se aigbagbo ninu won wipe: Eyi ko je nkankan bikose idan ti o han gbangbaa.

## 53.

**Se okan ni "Ẹ̀mí mímọ̆" ati angeli ti o n je "Gébúrẹ́lì"?**

**Bibeli** **Rara / Bẹẹni** **Al-Qur'an**

**Luku 1:11-35 –** 11 Angẹli Olúwa kan sì fi ara hàn án, ó dúró ní apá ọtún pẹpẹ tùràrí.13Ṣùgbọ́n angẹli náà wí fún un pé, "Má bẹ̀rù, Sekariah: nítorí tí àdúrà rẹ gbà; Elisabeti aya rẹ yóò sì bí ọmọkùnrin kan fún ọ, ìwọ ó sì sọ orúkọ rẹ̀ ní Johanu.15Nítorí òun ó pọ̀ níwájú Olúwa, kì yóò sì mu ọtí wáìnì, bẹ́ẹ̀ ni kì yóò sì mu ọtí líle; yóò sì kún fún Ẹ̀mí Mímọ́ àní láti inú ìyá rẹ̀ wá. Angẹli náà sì dáhùn ó wí fún un pé, "Èmi ni Gabrieli, tí máa ń dúró níwájú Ọlọ́run; èmi ni a rán wá láti sọ fún ọ, àti láti mú ìròyìn ayọ̀ wọ̀nyí fún ọ wá

**Johanu 4:24 -** Emini olurun awon ti o ba n sin in nilati sin in mi ati ni otito".

---

**Bakara 2:87 & 98 -**Dajudaju A wa fun Musa ni Tiran a Awa si fi awon ojise tele ara won lehin re, A si fun Isa omo M ariyama ni alaye oro to han, a si fi emi mimo ran a lowo . O ha le je pe igbakigba ti okan nyin ko fe ni e o ma se igberaga? Tobe ie enyin fi npe apakan ni opuro (ninu won),ti e sin pa apakan. Eniyiowu ti o je ota Olhun ati awon malaika Re, ati awon ojise Re ati jibrila ati mikaila, nje dajudaju Olohu je ota awon alaigbagbo.

**Kíyèsí**: Ninu ẹ̀sìn Ìsìláàmù se a se afihan Ẹ̀mí mimo gege bi angeli ti o n je "Gébúrẹ́lì"

## 54.

**Se siso ọ̀rọ̀ òdì sí "Ẹ̀mí mímọ̆" nìkan ni o je ẹ̀ṣẹ̀ kan ṣoṣo ti ko ni idariji?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Matiu 12:31-32 -** 31Nítorí èyí, mo wí fún yín, gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ àti ọ̀rọ̀-òdì ni a yóò dárí rẹ̀ jí ènìyàn, ṣùgbọ́n ìṣọ̀rọ̀-òdì-sí Ẹ̀mí Mímọ́ kò ní ìdáríjì. 32Ẹnikẹ́ni tí ó bá sọ̀rọ̀-òdì sí Ọmọ ènìyàn, a ó dáríjì í, ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá sọ ọ̀rọ̀-òdì sí ẹ̀mí mímọ́, a kì yóò dáríjì í, ìbá à ṣe ní ayé yìí tàbí ní ayé tí ń bọ̀.

---

**Nisa 4:48, 116 & 168 –** Dajudaju Olohun ki yio foriji eni ti o ba da nnkan po mo sugbon yio saforiji ese miran yato si eyi fun enikeni ti O ba fe. 116. Dajudaju Olohun kii yio se aforiji nipa ki a ba a wa egbe. 168. Dajudaju awon eni ti o se aigbagbo ti o se abosi Olohun ki yio foriji won

## 55.

**Se Ìwé mímọ́ tẹnu mọ́ awon ohun ti emi?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Romu 1:11 –** Mo n daniyan lati ri yin, ki n le fun yin ni ebun ti yoo tubo fun yin lagbara.
Romu 8:9 – Sugbon ni tiyin, e ko huwa gege bi awwon ti eran-ara n dari mo Emi lo n samona yin, bi Emi Olorun ba n gbe inu yin nitooto. Nitori pe enikaeni ti ko b ani Emi Kristi ninu re ki I se ti Kristi.
**1 Kọrinti 2:13-16 –** Ohun ti a n so kii n se ohun ti eniyan fi oro ogbon ko wa.Emi ni o ko wa bi a ti n tumo nnkan tie mi, fun awon ti won ni Emi. Sugbon iru Emi ti Kristi ni ni awa naa ni.
**Juda 18-19 –** Won kilo fun yin pe akoko ikeyin, awon kan yoo maa fi maa esin se eleya, won yoo maa tele ifekufee ara won lai beru Olorun. Awon wonyi ni won n ya ara won soto.Won huwa bi eranko,won ko ni Emi Mimo.

---

**İsra 17:85 –** Atipe nwon o bi lere nipa emi. Sope: Emi mbe ninu ase Oluwa mi, atipe a ko fun nyin ni imo bikose die.

## 56.

**ṣe"Ẹ̀mí mímọ̋ Ọlọ́run n gbe inu awon onigbagbo ati pe se o ma a nfi ebun emi kun inu won?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 20:21-23 –** O tun ki won pe, Alaafin fun yin! Gege bi baba ti ran mi nise, bee nimo ran yin." Leyin ti o so bee tan, O mi si won, o ba wi fun won pe, "e gba Emi Mimo. Awon ti e ba dari ese ji, Olorun dariji won. Awon eni ti e ko ba dari ese ji,Olorun ko dariji won."
**Ìṣe Àwọn Aposteli 1:8** – sugbon eyin yoo gba agbara nigbati Emi Mimo b aba le yin. E oo wa maa se eleri mi ni jerusalemu, ati ni gbogbojudia ati ni samaria ati titi deopin ile aye.
**1 Kọrinti 12:1, 4-11 & 13 –** Eyin ara, n ko fe ki nnkan nipa ebun Emi Mimo sokunkun si yin.Orisirisi ni ebun Emi Mimo sugbon lati odo Emi kan naa ni wan ti n wa. I se Emi Mimo n farahan ninu olukuluku wa fun ire gbogbo wa.

---

**Kíyèsí:** Kùránì ko ṣe imenuba awon ebun emi tabi pe Ẹ̀mí mímọ̀ n gbe inu eniyan.

## 57.

**Nje a le ti ara enikan gba emi tabi ebun emi nipase gbigbe owo le ori eni?** B ibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**1 Timoti 4:14-16 –** Ma se ainaani ebun ti Emi Mimo fun o nipa asotele nigba ti won gba ijo gbe owo le o lori. Maa lepa awon nnkan wonyin. Awon ni ki o je o gba gbogbo akoko re, ki itesiwaju re le han si gbogbo eniyan. Maa so ara re ati eko re. Duro sinsin ninu won. Ti o ba n se bee, iwo yoo gba ara re la ati awon ti o n gbo oro re.
**2 Timothy 1:6** – Idi niyi ti mo fi n ran o leti pe ki o maaa ru ebun-ofe Olorun soke, Ti a fi fun o nipa owo mi ti mo gbe le o lori.
**Heberu 6:1 –** Nitori naa, e je ki a pa eko alakokoobere ti isin igbagbo ti ki a tediwaju lati ko eko ti o jinle. Ki a maa fi ipile lele mo, ipile bi eko nipa ironupiwada kuro ninu awon ise ti o yori si iku, eko nipa igbagboninu olorun.

---

**Kíyèsí:**Ninu Kùránìko si imenuba gbigbe owo le ori eni fun gbigba emi tabi ebun emi Cf. Romu 1:11, 2 Tesalonika 2:8 ati 1 Timoteu 4:14-16.

## 58.

**ṣe Ọlọ́run fun awon ọmọ lẹ́yìn Jésù ni agbara lati se irufe iṣẹ́ ìyanu ti Jésù ṣe nípasẹ̀ ágbára Ẹ̀mí ti on gbe ninu won?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 14:12 –** Mo fe ki e mo dajudaju pe eni ti o ba gba mi gbo yoo se awon ise ti n mo n se;yoo ti le awon ise ti o ju iwonyi lo,nitori mo n loso do baba.
**Luku 10:17 –** Awon omo eyin mejilaadorin pada de pelu ayo. Won ni “Olowa, awon emi esu paapaa gboran si wa lenu oruko re.”
**Ìṣe Àwọn Aposteli 6:8 –** Stefanu n se ise iyanu ati ise abami nla laarin awon eniya nitori pe ebun ati agbara Olorun po lowo re.
**Ìṣe Àwọn Aposteli 8:6 -**awon eniyan subo filipi ki won le gbo oro ti o n so, wo si ri ise abami ti o n se.

---

**Kíyèsí:** ko si akosile Kankan ninu Kùránì nipa enikeni ti o n seiṣẹ́ ìyanu Lẹ́yìn tí Jésù.

# 59.

**ṣe Ọlọ́run fun awon onigbagbọ ni ebun ifi ede fo tabi nípasẹ̀ ágbára Ẹ̀mí mímọ?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 14:2, 5 –** Nitori eni ti o ba n fi ede soro ko ba eniyan soro, Olorun ni o n ba soro.Nitori pe ko si eni ti o n so emi ni o gbe e ti O gbo ohun ti o nso. Emi ni o gbe e ti o fi n so ohunasiri ti o n so ti ko ye eniyan.

**Romu 8:26-27** - Bakana naa, Emi tun n ran wa lowo ninu ailera wa. Nitori a ko mo ohun ti o to ti a bam aa gbadura fun. Sugbon Emi funrare a mma bebe fun wa lodo Olorun lona ti a ko le fi enu so. Olorun Olumoran okan, m ero ti o wa lokan Emi, nitori Emi nii maa bebe fun awon eniyan Olorun bi Olorun funare ti fe.

---

**Kíyèsí:** ko si akosile ifi ede fo Kankan Ninu Kùránì.

# 60.

**Se iyato gedegbe wa laarin awonÁngèlì (Maleka) pe won je iranse Ọlọ́run atiẸ̀mí èṣù (Jini) pe won je iranse Sátánì?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 25:41 –** "Nigbana ni yoo wa so fun awon ti o wa ni owo osi pe, ''Ekuro lodo mi, eyin eni egun. E lo sinu ina ajooku ti a tip ese sile fun esu ati awon angeli re.

**Ìfihàn 12:9 –** Won le Eranoko Ewele naa jade-ejo atijo ni ti a n pe ni esu, tabi satani ti o n tan awon ti o n gbe inu aye je. Won le e jade lo sinu aye, ati oun ati awon angeli re.

---

**Jinn 72:1—16 –** Sope; a ranse si mi pe dajudaju awon ijo kan ninu awon anjonu nwon teti si (kike AL-Kurani)kan ti o kun fun iyanu.O nto ni si ona tara (tóto),nitori aw ani igbagbo ododo si i.orogun pelu Oluwa wa. Atipe dajudaju on (Olohun)Olu wa wa tito bi Re ga, ko ni aya, ko si bi'mo. Atipe dajudaju awon alaimokan ninu wa je enti o nsóro isokuso (ti o jinna si ododo) mo Olohun). Atipe dajudaju awa rope enia ati alijonu nwon ko ni le puro mo Olohun. Atipe dajudaju awon oniwa rere wa ninu wa ati awon elomiran ti nwon ko ni iwa rere ,awa pin si oju ona kelekele..Atipe dajudaju o mbe ninu wa awon ti o npa ofin Olohun mo (Musulumi),atipe o wa ninu wa awon eniti kin pa ofin Olohun moa won wonni lo ngbero lati tele ona tara.

## 61.

**Ǹjẹ́ o se e se fun Sátánì ki o ronupiwada ki o si di rere?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**Ìfihàn 12:9-10 –** Won le Eranko Ewele naa jade-ejo atijo ni ti a n pe ni Esu,tabi Satani ti o o n tan awon ti o n gbe inu aye je.Won le e jade lo sinu aye,ati oun ati awon abgeli re.Mo wa gbo ohun lile kan ni orun ti o so pe,"Akoko igbala niyi ati agbara ,ati ijoba ti Olorun wa,ati akoko ase Kristi re.Nitori a ti le Olufisun awon onigbabgo ara wa jade,ti o n fi ejo won sun niwaju Olurun wa tosan-toru.

---

**Bakara 2:208** -.A pe eniyin onigbagbo, e ko si esin Islam patapata,evma se tele isise esu, dajuudaju, on je ota ti o fi oju han awo fun nyin.
**Zukhruf 43:36-39** – Enikeni ti o ba seri kuro nibi iranti (Olohun) Ajoke aiye, Awa yio yan esu fu u, on yio si di alabarin fun u, Atipe dajudaju awon (esu) yio ma se won lori kuro ni oju ona (ti o to), atipe nwon yio ma ro pe dajudaju a ti fi awon mona. Titi yio fi wa bawa, on yio sope: A!iba sese ki ona jijin wa larine mi pelu re, ni jijin iyo-orun ati iwo-orun, nitori ore buru loje fun mi.(Abamo nyin)ko le se nyin ni anfani ni oni, nigbati e ti se abosi, pe e jo pin iya na.

## 62.

**Ǹjẹ́ o se e se fun awon "Ẹmí èṣù" latironupiwada ki won si di rere? (Jinn)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Juda 6-7 –** Bee n ani awon angeli ti won koja aaye won akoko, ti won kuro ni ipo ti Olorun ko fi de won mo inu okunkun bibribiri titi di ojo nla nni tii se ojo idajo. Bee si ni ilu sdomu ati ilu gomora ati awon ilu ti yi wo ka. Awon naa se bi awon angeli ti wo koja aaye won, won se agbere ati orisirisi ohun ibaje ti ko ba iwa eniyan mu. Olorun fi won se apere fun gbogbo eniyan nigba tiwon jiya ina ajonirun.

---

**Jinn 72:1, 11, 13 & 14 -** Sope; a ranse si mi pe dajudaju awon ijo kan ninu awon anjonu nwon teti si (kike AL-Kurani)kan ti o kun fun iyanu.13- Atipe dajudaju nigbati awa gbo itosona awa Gbagbo.Enikeni ti o ba gba Oluwa re gbo ko ni beru adanu kosi beru abosi.14- Atipe dajudaju o mbe ninu wa awon ti o npa ofin Olohun mo (Musulumi),atipe o wa ninu wa awon eniti kin pa ofin Olohun moa won wonni lo ngbero lati tele ona tara.

# 63.

**se awon ese kan wa ninu Ìwé mímọ́ nipa lile Ẹ̀mí èṣù jade ninu awon eniyan?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Matiu 9:33 –** Sugbon bi o ti le emi esu naa jade ni odi naa bere si soro.Enu ya gbogbo awon eniyan, won n so pe, A ko ri iru eyi ri ni Isreali."

**Matiu 17:18 –** Jesu ba pase fun emi esu naa kio jade kuro ninu re, ar omo naa si da lati igba naa.

**Maku 1:25-26 –** Jesu ba a wi, o ni, "pa enu mo ki o jade kuro ninu okunrin yii." Emi esu naa wo gbo okurin naa.

**Luku 4:35, 8:33 & 9:42 –** Jesu ba ba wi, o ni, "pa enu mo ki o si jade kuro ninu okunrin yii!" Emi esu naa bag be okunrin nan sanle loju gbogbo won, oba jade kuro lara re, lai pa a lara.

---

**Kíyèsí:** Ko si ese Kùránì Kankan ti o soro nipa lile Ẹ̀mí èṣù jade ninu awon eniyan; sugbon ese mọ́kàndínláàádọ́rùn-ún ninu Bíbélì ni o soro nipa lile Ẹ̀mí èṣù jade.

# 64.

**Se a se afihan ágbára itanije Sátánì'sbi eleyi ti ko ni emi ninu tabi eyi ti ko sise rara?**

**Bibeli** **Rara / Bẹẹni** **Al-Qur'an**

**Luku 4:6 –** O so fun Jesu pe, "Iwo ni n oo fun ni gbogbo ase yii ati ogo re, nitori emi ni a ti fi won le lowo, eni ti o ba si wu mi ni mo le fun.

**2 Kọrinti 4:3—4 –** Sogbon ti iyin rere w aba sokunkun, awon ti yoo segbe ni o sokunkun si. Awon orisa aye yii ni won fo iru awon eni bee loju, ti okan won ko fi le Gbagbo.Eyi ni ko je ki imole iyin rere Kristi, ti o logo, ki o tan si won lara;ani, Kristi tii se aworan olorun.

---

**Nisâ 4:76 –** Awon ti now Gbagbo nja ni oju ona ti Olohun, awon ti nwon si se aigbagbo nja ni oju ona esu ja;dajudaju ete esu nma nj yepere.

**İbrahim 14:22** – Atipe nwon nwa idajo, gbogbo alafojudi, olorokunkun padanu.

**Nahl 16:98** – Melomelo iran ti A pare siwaju won! Nje ire le ri enikan ninu won tabi ire tun gbo ohunwon ni?

**Shu'arâ 26:210-211 –** Awon esu ko lo so kale.Atipe ko to si won nwon ko si ni agbara(lati so o kale).

## 65.

**Se a se afihan Sátánì gege bi omo alade tabi oludari aye yii?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Luku 4:6 –** Osu fun Jesu pe,"Iwo ni n oo fun ni gbogbo ase yii ati ogo re, nitori emi ni a ti fi won le lowo eni ti o ba si wu mi ni mo le fun.
**Johanu 12:31 –** Akoko to fun idajo aye yii. Nsinsinyii ni a oo le alase aye yii jade.
**Johanu 14:30** – N ko tun ohun pupo ba yin so mo nitori alase aye yii n bo. Ko ni agbara kan lori mi.
**2 Kọrinti 4:3-4 -** Sogbon ti iyin rere w aba sokunkun, awon ti yoo segbe ni o sokunkun si. Awon orisa aye yii ni won fo iru awon eni bee loju, ti okan won ko fi le Gbagbo.Eyi ni ko je ki imole iyin rere Kristi, ti o logo, ki o tan si won lara;ani, Kristi tii se aworan olorun.

---

**Nisa 4:76 -** Awon ti now Gbagbo nja ni oju ona ti Olohun, awon ti nwon si se aigbagbo nja ni oju ona esu ja;dajudaju ete esu nma nj
**Shuara 26:210-211 -** Awon esu ko lo so kale.Atipe ko to si won nwon ko si ni agbara(lati so o kale).

# Kristi ati Hz. Muhammed

## 66.

**Se otito ni wi pe a bi Kristinipase wundia?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Aisaya 7:14 –** Nitori naa, OLUWA funrare yoo fun yin ni ami kan. E gbo! O Olomoge kan yoo loyun si bi omokunrin kan, yoo pe oruko re Imanuel.
**Matiu 1:18 –** Bit tan ibi Jesu Kristi ti ri niyi. Nigba ti Maria iya re w ani iyawo afesona josepho, ki won to se igbeyawo, a ri pe Maria ti loyun lati odo Emi-Mimo.

---

**Meryem 19:16-22 – (**Maryamoa) wipe: Bawo ni od mokunrin yio se wa fun mi nigbati abara kan ko fowokan mi beni emi ko si je alagbere (pansaga). O wipe: Beni yio je Oluwa re wipe: O rorun fun Mi ( lati se); atipe ki A le se e ni arisami fun awon enia ati anu lati odo Wa. O si je oro ti a ti pari. O si ni oyun re; o sig be e lo si aye kan ti o jinna.
**Enbiya 21:91-** Olohun ko fi kan se omo atipe ko si olohun kan pelu Re, ti o ba je beni, olohun kokan iba siti bori apakeji. Mimo ti Olohun ju ohun tin won se irohin lo.

## 67.

**Se otito ni wi pe Kristi ko ni ese kankan?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Maku 1:24 –**"Ki ni o pa tawa-tire po, Jesu ara Nasareti? Se o de lati pa wa run ni? Mo mo eni ti o je. Eni Mimo Olorun ni o."
**Johanu 7:18 –** Eni Ti o ba soro ti ara re n wa ogo ti ara re .Sugbon eni ti o ba wa eni ti o ran an nise je oloooto, ko si aisododo ninu re.
**Johanu 8:46 –** Tani ni ninu yin tio ka ese mo mi lowo ri? Bi mo ba n so otito,kilode ti e ko fi gba mi gbo?
**2 Kọrinti 5:21 –** Kristi ko dese.Sibe nitori tiwa, Olorun so o di okan pelu eda elese, ki a le di olododo niwaju Olorun nipa re.
**2 Johanu 3:5 –** Jesu dahun pe, "Mo fe ki o mo dajudaju pe, enikeni ti a ko ba fi omi ati Emi bi, ko le wo ijoba Olorun.

---

**Bakara 2:253 -** A si fun Isa omo Maryam ni awon ami ti o yanju, A si ran a lowo pelu emi mimo.
**Meryem 19:19 -** Maryamoa) wipe On (Maliaka) wipe: Dajudaju iranse Oluwa re ni emi je pe:Emi yio fun o ni (iro) omokunrin kan ti o mo

## 68.

**Se otito ni wipe Kristi ní agbára ìmòye àràmàǹdà ati ogbon?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 9:4 –** Sugbon jesu mo ero inu won; o ba bi won pe," kilo de ti e fi n ro ero buruku ninu okan yin?"
**Johanu 7:45-46** – Nigbati awon eso Tempili ti won ran lo mu Jesu pada de odo awon Farisi, won bi won pe "Ki lo de ti e ko fi mu un wa? Awon eso ohun dahun pe "Enikeni ko soro bi okunrin yii ri!"
**Johanu 16:30 –** A wa mo wayi pe o mo ohun gbogbo, ko sese di igba ti eniyan ba bi o ki o to dahun oro. Nitori naa a Gbagbo pe lati odo Olorun ni o ti wa."

---

**Al-i İmran 3:45-48 –** Nigbati Malaika wipe; Ire Mariyama, dajudaju Olohun fun o ni iri-idunnu pelu gbolohun kan lati odo Re wa, enikan ti oruko yio ma je MASHI isa omo Mariyama, abiyi ni ni aiye ati ni orun yio ma be ninu awon ti a sunmo (Olohun).
**Zuhruf 43:63 –** Atipe nigba (annabi )Isa na de pelu alye, o sope; Dajudaju mo de wa nyi pelu ogbon, atipe lati le se alaye fun nyin apakan ohun ti yapa-enu si. Nitorina e beru Olohun ki e si tele temi.

## 69.

**Se otito ni wipeKristiní agbára àràmànđà fun iṣẹ́ ìyanu ati lati ji oku dide?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Maku 1:40-45 –** Enikan ti o ni arun ete wa si odo re o "bi o ba fe o le so ara mi di mimo... Jesu...Mo fe...

**Maku 6:47-**....Jesu to maa lo sodo won. O n rin lori omi

**Johanu 11:14-44 –** 43 Ma mbe O kwusiri ihe ndia, O were oké olu tie nkpu, si, Lazarọs, puta n'èzí. 44 Onye nwururi anwu putara, ewerewori ákwà-ozu ke ya ukwu na aka; were kwa ichafọ kechie ya iru. Jisus si ha, Tọpunu ya, ghara kwa ya ka ọ la.

---

**Al-i İmran 3:45-50 -** Nigbati Malaika wipe; Ire Mariyama, dajudaju Olohun fun o ni iri-idunnu pelu gbolohun kan lati odo Re wa, enikan ti oruko yio ma je MASHI isa omo Mariyama, abiyi ni ni aiye ati ni orun yio ma be ninu awon ti a sunmo (Olohun).

**Zuhruf 43:63 –** Atipe nigba (annabi )Isa na de pelu alye, o sope; Oluwa nyin pe emi yio ya aworan kan fun nyin pe emi yio ya aworon kan fun nyin lati inu amo gegebi aworan eiye, emi yio si fe (ategun) sinu re ti yio si di eiye pelu ase.

**Kíyèsí:** Iṣẹ́ ìyanu metadinlogoji Jésù ni a se akosile re ninu Injili.

## 70.

**Se otito ni wi pe Kristi ló lẹ́tọ̀ọ́sí pipa ase nipa ìgbàgbọ́ ati igboran lati odo gbogbo eniyan**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 23:10...**Kí a má sì ṣe pè yín ní Olùkọ́ nítorí Olùkọ́ kan ṣoṣo ni ẹ̀yin ní, òun náà ni Kírísítì.

**Johanu 14:15 & 21-24...**Bí ẹ̀yin bá fẹ́ràn mi, ẹ ó pa òfin mi mọ́. 21. Ẹni tí ó bá ní òfin mi, tí ó bá sì ń pa wọ́n mọ́, òun ni ẹni tí ó fẹ́ràn mi: ẹni tí ó bá sì fẹ́ràn mi, Bí ẹnìkan bá fẹ́ràn mi, yóò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́...24. Ẹni tí kò fẹ́ràn mi ni kò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́;

---

**Al-i İmran 3:50 & 55...**emi si wa ban yin pelu ami kan ti o ti odo Oluwa nyin wa nitorina e beru Olohun ki e si tele mi...55..Emi yio si we o mo kuro lodo awon alaigbagbo Emi yio si fi awon ti o ba tele o leke awon ti o se aigbagbo lo titi di ojo ajinbe...

**Zuhruf 43:61 & 63....**atipe on je mimo kan fun akoko na...63. nitorina e beru Olohun ki e si tele mi...

## 71.

**Se otito ni wipe a se afihan Jésù Kristi gege bi i "Mèsáyà ″? (Eni ti a fi ami ororo yan)**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 26:63-64...** 63. Ṣùgbọn Jésù dákẹ́ rọ́rọ́. Nígbà náà ni olórí àlùfáà wí fún un pé, "Mo fi ọ́ bú ní orúkọ Ọlọ́run alàáyè: Kí ó sọ fún wa, bí ìwọ bá í ṣe Kírísítì Ọmọ Ọlọ́run." 64. Jésù sì dáhùn pé, "Bẹ́ẹ̀ ni, ìwọ wí,"

**Johanu 1:41...** Ohun àkọ́kọ́ tí Áńdérù ṣe ni láti wá Símónì arákùnrin rẹ̀, ó sì wí fún un pé, "Àwa ti rí Mèṣáyà" (ẹni tí ṣe Kírísítì).

**Johanu 4:25-26...**25. Obìnrin náà wí fún un pé, mo mọ̀ pé, "Mèsáyà ń bọ̀ wá, tí a ń pè ní Krísítì: Nígbà tí Òun bá dé, yóò sọ ohun gbogbo fún wa. 26.Jésù sọ ọ́ di mímọ̀ fún un pé, "Èmi ẹni tí ń bá ọ sọ̀rọ̀ yìí ni Òun.

---

**Al-i İmran 3:45...**olohun fun o ni iro-idunnu ati gbolohun kan lati odo Re wa, Enikan ti oruko Re yio ma je Masihu Isa...

**Nisa 4:171-172...**Masihu, Musa omo Mariyama, ko je nkankan ju omo Olorun lo...172. Al-Masihu ko se ikorira lati je olujosin fun Olohun...

**Kíyèsí: a lo** Awon òrò "Mèsáyà ″ tabi "Kristi"ni igba ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹta le ni méjìdínlọ́gọ́taninu majemu tituna si loòrò "Mèsáyà ″ ni igba mewa ninu Kùránì lati soro nipa Kristi.

## 72.

**Se otito ni wipe a toka si Kristi gege bi i Òrò Ọlọ́run?( (Logos / Kalimullâh)**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 1:1-3 & 14...**1. Ní àtètèkọ́ṣe ni Ọ̀rọ̀ wà, Ọ̀rọ̀ sì wà pẹ̀lú Ọlọ́run, Ọlọ́run sì ni Ọ̀rọ̀ náà. 14. Ọ̀rọ̀ náà sì di ara, òun sì ń bá wa gbé. Àwa sì ti rí ògo rẹ̀, àní ògo Òun ọmọ bíbí kan ṣoṣo, àní Àyànfẹ́ rẹ̀ tí ó ti ọ̀dọ̀ Baba wá, ó kún fún oore-ọ̀fẹ́ àti òtítọ́.

**Ìfihàn 19:13-16..**13. A sì wọ̀ ọ́ ní aṣọ tí a tẹ̀ bọ inú ẹ̀jẹ̀: a sì ń pe orúkọ rẹ̀ ní Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. 16. Ó sì ní lára aṣọ rẹ̀ àti ni ìtàn rẹ̀ orúkọ kan tí a kọ: ỌBA ÀWỌN ỌBA ÀTI Olúwa ÀWỌN Olúwa

---

**Al-i İmran 3:39...**Olohun nfun o niro-idunnu nipa Yahyha ti yio jeri ododo nipa oro kan ti o ti odo Olohun wa, yio si je eni-ola, ko si je eniti nyanhanhan...

**Al-i İmran 3:45...**olohun fun o ni iro-idunnu ati gbolohun kan lati odo Re wa, Enikan ti oruko Re yio ma je Masihu Isa...

# 73.

**Se ọtito ni wipe Kristiti waa gege bi Òrò Ọlọrunki a to bi i saye?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Aisaya 9:6...**Nítorí a bí ọmọ kan fún wa, a fi ọmọkùnrin kan fún wa... Ọlọ́run Alágbára Baba ayérayé, Ọmọ ọba aládé Àlàáfíà.
**Mika 5:2...** Ṣùgbọ́n ìwọ, Bẹ́tílẹ́hẹ́mù... yóò ti jáde tọ̀ mí wá, ìjáde lọ rẹ̀ sì jẹ́ láti ìgbà àtijọ́, láti ìgbà láéláé
**Johanu 8:58...**Jésù sì wí fún wọn pé, "Lóòótọ́ lóòótọ́ ni mo wí fún yín, kí Ábúráhámù tó wà, èmi nìyìí."
**Heberu 13:8...**Jésù Kírísítì ọkan náà ni lánà, àti lóní, àti títí láé.
**Ìfihàn 1:1, 8 & 17-18...** Ìfihàn ti Jésù Kírísítì... 8Mu onwem bu Alfa ahu na Omega ahu, ka Onye-nwe-ayi Chineke kwuru, bú Onye nādi adi, Onye di-kwa-ri, Onye nābia kwa, Onye puru ime ihe nile.

---

**Al-i İmran 3:59...**Dajudaju apejuwe Isa ni odo Olohun o dabi apejuwe Adama; O seeda re lati inu erupe, lehin na O wi fun u pe: Je be! O si jebe.

# 74.

**Se otito ni wipe Òrò Ọlọ́run, lo di eniyan ti a n pe niJésù Kristi? (Kenosis or Hûlul)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 1:18-24...**23.Wúńdíá kan yóò lóyún, yóò sì bí ọmọkùnrin kan, a ó sì pe orúkọ rẹ̀ ní 'Èmánúẹ́lì,' " èyí tí ó túmọ̀ sí, "Ọlọ́run wà pẹ̀lú wa.
**Johanu 1:1 & 14...**Ní àtètèkọ́ṣe ni Ọ̀rọ̀ wà, Ọ̀rọ̀ sì wà pẹ̀lú Ọlọ́run, Ọlọ́run sì ni Ọ̀rọ̀ náà. 14. Ọ̀rọ̀ náà sì di ara, òun sì ń bá wa gbé. Àwa sì ti rí ògo rẹ̀, àní ògo Òun ọmọ bíbí kan ṣoṣo, àní Àyànfẹ́ rẹ̀ tí ó ti ọdọ̀ Baba wá, ó kún fún oore-ọ̀fẹ́ àti òtítọ́.

**Filipi 2:5-8...5.** Kírísítì Jésù... 6. Ẹni tí, bí o tilẹ̀ jẹ́ ìrísí Ọlọ́run...7... a sì ṣe é ni àwòrán ènìyàn....8...ó rẹ ara rẹ̀ sílẹ̀
**Kolose 1:3 & 15...**Nígbàkúùgbà tí a bá ń gbàdúrà fún un yín ni a máa ń dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run Baba Olúwa wa Jésù Kírísítì. 15... Kírísítì ni àwòrán Ọlọ́run tí a kò le rí, àkọ́bí gbogbo ẹ̀dá.
**1 Timoti 3:16...**Láìṣiyè méjì, títóbi ní ohun ìjìnlẹ̀ ìwà-bí-Ọlọ́run: ẹni tí a fi hàn nínú ara, tí a dáláre nínú Ẹ̀mí, ti àwọn áńgẹ́lì rí, tí a wàásù rẹ̀ láàrin àwọn orílẹ̀-èdè, tí a gbàgbọ́ nínú ayé, tí a sì gbà sókè sínú ògo.

---

**Maide 5:17...**dajudaju nwon ti se aigbagbo (keferi) awon eniti nwipe Al-Masihu omo Mariyama ni Olhun...A ma da ohun ti O ba fe...

## 75.

**Se otito ni wipe Kristi je "Àtọ̀runwá" tabi Ọlọ́run ni ipo eleran ara?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 1:1 & 14...** Ní àtètèkọ̀ṣe ni Ọ̀rọ̀ wà, Ọ̀rọ̀ sì wà pẹ̀lú Ọlọ́run, Ọlọ́run sì ni Ọ̀rọ̀ náà. 14. Ọ̀rọ̀ náà sì di ara, òun sì ń bá wa gbé. Àwa sì ti rí ògo rẹ̀, àní ògo Òun ọmọ bíbí kan ṣoṣo,

**Johanu 5:17-18...**17. Ṣùgbọ́n Jésù dá wọn lóhùn pé, "Baba mi ń ṣiṣẹ́ títí di ìsinsin yìí, èmi náà sì ń ṣiṣẹ́." 18. Nítorí èyí ni àwọn Júù túbọ̀ ń wá ọ̀nà láti pa á, kì í ṣe nítorí pé ó ba ọjọ́ ìsinmi jẹ́ nìkan ni, ṣùgbọ́n ó wí pẹ̀lú pé, Baba òun ni Ọlọ́run jẹ́, ó ń mú ara rẹ̀ bá Ọlọ́run dọ́gba.

**Johanu 10:25-33...** 25. Jésù...iṣẹ́ tí èmi ń ṣe lórúkọ Baba mi, àwọn ni ó ń jẹ́rìí mi....30. Ọ̀kan ni èmi àti Baba mi."

**Johanu 20:28-29...**28. Tọ́másì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Olúwa mi àti Ọlọ́run mi!" 29. Jésù wí fún un pé, "Nítorí tí ìwọ rí mi ni ìwọ ṣe gbàgbọ́: alábùkún fún ni àwọn tí kò rí mi, tí wọ́n sì gbàgbọ́!"

**Kolose 2:8-9...**9. Nítorí nínú Kírísítì ni àti rí ẹ̀kún ìwà Ọlọ́run ní ipò ara

---

**Maide 5:17, 72, 75, 116 & 118...**Dajudaju nwon ti se aigbagbo keferi awon eniti nwipe: Al-Masihu omo Mariyama ni Olohun...

**Zuhruf 43:57-59....**57. Omo Mariyama...59. On ko je kinikan ju erusin ti A se ni apejuwe...

**Kíyèsí:** Bíbélì se afihan Jésù bi i "Ọlọ́run" ni igba ọ̀ọ́dúnrún le ni mẹ́tàdínláàádọ́rin

## 76.

**Se otito ni wipe Kristi lo seda aye?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Efesu 3:8-9...**9. Ọlọ́run, ẹni tí o dá ohun gbogbo nípa Jésù Kírísítì

**Kolose 1:13-20...**13.ìjọba Ọmọ tí ó fẹ́ràn...15... àwòrán Ọlọ́run tí a kò le rí, àkọ́bí...16...Nítorì nípa rẹ̀ ní a dá ohun gbogbo: àwọn ohun tí ń bẹ ní ọ̀run àti ní ayé

**Heberu 1:1-2 & 10-12...**Ọlọ́run… 2. ní ìgbà ìkẹyìn yìí Ọlọ́run ń bá wa sọ̀rọ̀...nípasẹ̀ ẹni tí ó dá gbogbo ayé...10. ìwọ Olúwa, ìwọ fi ìdí ayé sọlẹ̀.

---

**Maide 5:75, 116 & 118...**Masihu omo Mariyama ko je nkankan ju Ojise lo...

**Zuhruf 43:57-59...**On ko je kinikan ju erusin lo ti A se idera fun lo atipe A se ni apejuwe fun awon omo Israil

## 77.

**Se otito ni wipe Kristi nikan ni olulaja laarin Ọlọ́run ati ènìyàn**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 14:6...**Jésù dá wọn lóhùn pé, "Èmi ni ọ̀nà, òtítọ́ àti ìyè: kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Baba, bí kò ṣe nípaṣẹ̀ mi.

**Ìṣe Àwọn Aposteli 4:12...**Kò sì sí ìgbàlà lọ́dọ̀ ẹlomìíràn; nítorí kò sí orúkọ mìíràn lábẹ́ ọ̀run ti a fifún ni nínú ènìyàn, nípa èyí tí a lè fi gbà wá là."

**1 Timoti 2:5-6...**Nítorí Ọlọ́run kan ní ń bẹ, onílàjà kan pẹ̀lú láàrin Ọlọ́run àti ènìyàn, àní Kírísítì Jésù ọkùnrin náà. 6. Ẹni ti ó fi ara rẹ̀ ṣe ìràpadà fún gbogbo ènìyàn—ẹ̀rí tí a fi fún ni ní àkókò tó yẹ.

---

**Bakara 2:48...**e be ru ojo kan to je pee mi kan ko ni le se anfani fun emi keji. Beni aki yio gba ipe sise kan lowo re, ako si ni gba aro kan lowo re, aki yio si ran wan lowo.

**Yunus 10:3...**olohun...ko si olusipe kan pelu re...

Zümer 39:44...Olohun lo ni gbogbo ipe sise...

## 78.

**Se otito ni wipe Kristi ni Omo Ọlọ́run?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 16:16...**Símónì Pétérù dáhùn pé, "Ìwọ ni Kírísítì náà, Ọmọ Ọlọ́run alààyè"

**Maku 14:61-62...**61. Ṣùgbọ́n Jésù dákẹ́. Olórí àlùfáà tún bi í, lẹ́ẹ̀kan sí i, ò ní, "Ṣé ìwọ ni Kírísítì náà, Ọmọ Ọlọ́run?" 62. Jésù wá dáhùn, ó ni, "Èmi ni: Ẹ̀yin yóò sì rí Ọmọ-Ènìyàn tí yóò jókòó lọ́wọ́ ọ̀tún agbára. Ẹ̀yin yóò sì tún rí Ọmọ-Ènìyàn tí ó ń bọ̀ láti inú àwọ̀sánmọ̀ ojú ọ̀run."

**Luku 1:32 & 35...32...**Òun ó pọ̀, Ọmọ Ọ̀gá-ògo jùlọ ni a ó sì máa pè é: Olúwa Ọlọ́run yóò sì fi ìtẹ́ Dáfídì baba rẹ̀ fún: **35.**.Áńgẹ́lì náà sì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Ẹ̀mí Mímọ́ yóò tọ̀ ọ́ wá, àti agbára Ọ̀gá-ògo jùlọ yóò sìji bò ọ́. Nítorí náà ohun mímọ́ tí a ó ti inú rẹ bí, Ọmọ Ọlọ́run ni a ó máa pè é.

---

**Tevbe 9:30-31...**30. Awon Yahudi ni omo Olohun ni Usairu...31. ko si Olohun kan leyin re. Mimo re tayo ohun tin won fin se orogun (Re)

**Kíyèsí:**ese méjìléláàádọ́rùn-únninu Bíbélì lo se afihanJésùgege bi "OmoỌlọ́run" sugbon cf. En'am 6:101, Furkan 25:2, Zuhruf 43:81 ati Jini 72:3.

## 79.

**Ninu Ìwé mímọ́ nigba ti a ba lo "Omo of Ọlọ́run" se a lo bi eni wipe a n so oro omo ti a ba nipase ibalopo okunrin ati obinrin??**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Luku 1:26-35...27...**sí wúndíá kan tí a ṣè lérí láti fẹ́ fún ọkùnrin kan, tí a ń pè ní Jóṣéfù, ti ìdílé Dáfídì; orúkọ wúndíá náà a sì máa jẹ́ Màríà. 35...Áńgẹ̀lì náà sì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Ẹ̀mí Mímọ́ yóò tọ̀ ọ́ wá, àti agbára Ọ̀gá-ògo jùlọ yóò sìji bò ọ́. Nítorí náà ohun mímọ́ tí a ó ti inú rẹ bí, Ọmọ Ọlọ́run ni a ó máa pè é.
**1 Johanu 5:20...**Àwa sì mọ̀ pé Ọmọ Ọlọ́run dé, ó sì tí fi òye fún wa, kí àwa lè mọ ẹni tí í ṣe òtítọ́, àwa sì ń bẹ nínú ẹni tí í ṣe òtítọ́, àní, nínú Ọmọ rẹ̀, Jésù Kírísítì. Èyí ni Ọlọ́run òtítọ́, àti ìyè àinípẹ̀kun.

---

**En'am 6:101...**(On ni) Olupile da sanma ati ile. Kini yio tise ni omo nigbati ko ni aya, O si da gbogbo nkan, On si ni Olumo gbogbo nkan.
**Jinn 72:3...**Atipe dajudaju On (Olohun) Oluwa wa ti to bi re ga, ko ni aya, ko si b'imo.

## 80.

**Se looto ni awon eniyan n josin fun Kristi ati wipe ṣe Kristi tewogba ijosin won?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 28:9-10...** Bí wọn ti ń sáré lọ lójijì Jésù pàdé wọn. Wọ́n sì forí balẹ̀ fún un. 10. Nígbà náà, Jésù wí fún wọn pé, "Ẹ má ṣe bẹ̀rù. Ẹ lọ sọ fún àwọn arákùnrin mi pé...
**Johanu 9:35-38...**35.Ìwọ gba Ọmọ Ọlọ́run, gbọ́ bí?...38.. Ó sì wí pé, "Olúwa, mo gbàgbọ́," ó sì wólẹ̀ fún un.
**Johanu 20:28-29...**28. Tọ́másì dáhùn ó sì wí fún un pé, "Olúwa mi àti Ọlọ́run mi!"
29. Jésù wí fún un pé, "Nítorí tí ìwọ rí mi ni ìwọ ṣe gbàgbọ́: alábùkún fún ni àwọn tí kò rí mi, tí wọ́n sì gbàgbọ́!"
**Filipi 2:10-11...**10.Pé ni orúkọ Jésù ni kí gbogbo eékún máa wólẹ̀, ní ọ̀run, àti ní orí ilẹ̀ ayé àti ní ìsàlẹ̀ ilẹ̀ ayé, 11. Àti pé kí gbogbo ahọ́n jẹ́wọ́ pé, Jésù Kírísítì ni Olúwa, fún ògo Ọlọ́run Baba.

---

**Maide 5:116 & 118...**Ati nigbati Olohun wipe: Iwo Isa omo Mariyama iwo ni O so fun awon enia pe: emu emi ati iya mi ni olohun meji leyin Olohun bi? Isa wipe: Mimo re, ko to fun mi lati so ohun tie mi ko ni eto re (lati so)...118...Ire na ni Alagbara, Ologbon...

## 81.

**Se otito ni wipe Kristi le se idariji ese fun awon eniyan?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Maku 2:5-7 & 10-11...**Nígbà tí Jésù sì rí ìgbàgbọ́ wọn, ó sọ fún arọ náà pé, "Ọmọ, a dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì ọ́." 7. "È é ṣe ti ọkùnrin yìí fi sọ̀rọ̀ báyìí? O ń sọ̀rọ̀ òdì. Ta ni ó lè darí ẹ̀ṣẹ̀ ji ni bí ko ṣe Ọlọ́run nìkan?". 10. Ṣùgbọ́n ẹ lè mọ̀ pé Ọmọ-Ènìyàn ní agbára ní ayé làti dárí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ ji ní. 11...Mo wí fún ọ, dìde, gbé ẹní rẹ kí ó sì máa lọ ilé rẹ.

**Luku 5:20...**Nígbà tí ó sì rí ìgbàgbọ́ wọn, ó wí pé, "Ọkùnrin yìí, a darí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì ọ́

**Ìṣe Àwọn Aposteli 10:43....**Òun ni gbogbo àwọn wòlíì jẹ́rìí sì pé, ẹnikẹ́ni ti ó bá gbà á gbọ́ yóò rí ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ gbà nípa orúkọ rẹ̀."

**Ìṣe Àwọn Aposteli 13:38...**Ǹjẹ́ kí ó yé yín, ará pé nípasẹ̀ Jésù yìí ni a ń wàásù ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ fún yín

**1 Johanu 2:12...**Èmi ń kọ̀wé sí yín, ẹ̀yin ọmọ mi ọ̀wọ́n, nítorí tí a darí ẹ̀ṣẹ̀ yín jì yín nítorí orúkọ rẹ̀.

---

**Al-i İmran 3:135...**Tani ma n fi ori ese jinni bikose Olohun...

**Maide 5:75...**Masihu omo Mariyama jo je nkankan ju Ojise lo...

## 82.

**Se otito ni wipe Kristi ni kokoro iku ati"ọ̀run àpáàdì̀ lowo?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Luku 12:5...**Ṣùgbọ́n èmi ó sì sọ ẹni tí ẹ̀yin ó bẹ̀rù fún yín: Ẹ bẹ̀rù ẹni tí ó lágbára lẹ̀yìn tí ó bá pànìyàn tan, láti wọ́ ni lọ sí ọ̀run àpádì: lóòótọ́ ni mo wí fún yín òun ni kí ẹ bẹ̀rù

**Ìfihàn 1:11-18...**1. Ìfihàn ti Jésù Kírísítì...8. Èmi ni Álfà àti Òmégà," ni Olúwa Ọlọ́run wí, "ẹni tí ó ń bẹ, tí ó ti wà, tí ó sì ń bọ̀ wá, Olódùmarè..14. ojú rẹ̀ sì dàbí, ọwọ́ iná...17. Èmi ni ẹni-ìṣájú àti ẹni-ìkẹyìn...18. Èmi ni ẹni tí ó ń bẹ láàyè, tí ó sì ti kú; sì kíyèsí i, èmi sì ń bẹ láàyè sí i títí láé! Mo sì ní kọ́kọ́rọ́ ikú àti ti ipò-òkú.

---

**Zuhruf 43:57 & 59...57.** Omo Mariyama...59...On ko je kinikan ju erusin ti a se ni apejuwe fun awon omo Israila...

## 83.

**Se otito ni wipe Kristi ni "Olugbala" araye?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Aisaya 43:11-13...11.**Èmi, àní Èmi, Èmi ni Olúwa, yàtọ̀ sí èmi, kò sí olùgbàlà...13.. Èmi ni...

**Luku 2:11...**Nítorí a ti bí Olùgbàlà fún yín lónì-ín ní ìlú Dáfídì, tí í ṣe Kírísítì Olúwa

**Johanu 4:42...**Wọ́n sì wí fún obìnrin náà pé, "Kì í ṣe nítorí ọ̀rọ̀ rẹ nìkan ni àwa ṣe gbàgbọ́: nítorí tí àwa tìkára wa ti gbọ́ ọ̀rọ̀ rẹ̀, àwa sì mọ̀ pé, nítòótọ́ èyí ni Krísítì náà, Olùgbàlà aráyé."

**Titus 1:4...**Sí Títù, ọmọ mi tòótọ́ nínú ìgbàgbọ́ wa kan náà. Oore-ọ̀fẹ́ àti àlàáfíà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run baba àti Kírísítì Jésù Olùgbàlà wa

**Titus 3:4-6...**Ṣùgbọ́n nígbà tí inú rere àti ìfẹ́ Ọlọ́run Olùgbàlà wa farahàn, 5. Ó gbà wá là. Kì í ṣe nípa iṣẹ́ tí àwa ṣe nínú òdodo bí kò ṣe nítorí àánú rẹ̀. Ó gbà wá là, nípaṣẹ̀ ìwẹ̀nù àtúnbí àti ìsọdọtun ti Ẹ̀mí Mímọ́, 6èyí tí tú lé wa lórí ní ẹ̀kún-rẹ́rẹ́ nípaṣẹ̀ Jésù Kírísítì Olùgbàlà wá

**1 Johanu 4:14...**Àwa tí rí, a sì jẹ́rìí pé Baba rán Ọmọ rẹ̀ láti jẹ́ Olùgbàlà fún aráyé

---

**Nisa 4:171...**Masihu, Isa omo Mariyama ko je nkankan ju omo Olorun lo.

## 84.

**Se otito ni wipe igbagbo ninu Kristi gege bi Olugbala ati Olúwa nikan ni ona lati ri iye anipekun?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Johanu 3:16 & 36...**Nítorí Ọlọ́run fẹ́ aráyé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, tí ó fi ọmọ bíbí rẹ̀ kan ṣoṣo fúnni, kí ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà á gbọ́, má bà á ṣègbé, ṣùgbọ́n kí ó lè ní iyè àìnípẹ̀kun. 36. Ẹni tí ó bá gba Ọmọ gbọ́, ó ní ìyè àìnípẹ̀kun: ẹni tí kò bá sì gba Ọmọ gbọ́, kì yóò rí ìyè; nítorí ìbínú Ọlọ́run ń bẹ lórí rẹ̀

**Johanu 14:6...**Jésù dá wọn lóhùn pé, "Èmi ni ọ̀nà, òtítọ́ àti ìyè: kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Baba, bí kò ṣe nípaṣẹ̀ mi

**Ìṣe Àwọn Aposteli 4:10-12...** ni orúkọ Jésù Kírísítì.... 12. Kò sì sí ìgbàlà lọ́dọ̀ ẹlomìíràn; nítorí kò sí orúkọ mìíràn lábẹ́ ọ̀run ti a fifún ni nínú ènìyàn, nípa èyí tí a lè fi gbà wá là."

---

**Al-i İmran 3:19 & 85...19.** Dajudaju esin (kansoso) ti mbe lodo Olohun ni Islam...85. enikeni ti o bat un wa esin kan yato si Islam, A ki yio gba lowow re; ni ojo ikehin ohun yio si wa ninu awon eni –ofo...

**Kíyèsí:**a ni ju es eBíbélì igba lo ti o se afihan Jesu gege bi Olugbala

## 85.

**Se otito ni wipeEje Kristi's ni a ta sile gege bi irubo iwenumo fun gbogbo ese araye?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Aisaya 53:5-12...**5. Ṣùgbọ́n a ṣá a lọ́gbẹ́ nítorí àìṣedédé wa a pa á lára nítorí àìsòdodo wa... àti nípa ọgbẹ́ rẹ̀ ni a fi múwa láradá...6... Olúwa sì ti gbé e ka orí ara rẹ̀ gbogbo àìṣedédé wa.

**Johanu 1:29...**Ní ọjọ́ kejì Jòhánù rí Jésù tí ó ń bọ̀ wá sí ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó sì wí pé, "Wò ó, Ọ̀dọ́-àgùntàn Ọlọ́run, ẹni tí ó kó ẹ̀ṣẹ̀ ayé lọ!

**1 Kọrinti 15:3-4...**3. Nítorí èyí tí mo rí gbà ṣáájú ohun gbogbo ní èmi pẹ̀lú ti gbà lé e yín lọ́wọ́, bí Kírísítì ti kú nítorí ẹ̀ṣẹ̀ wá gẹ́gẹ́ bí ìwé mímọ́ tí wí. 4. Àti pé a sìnkú rẹ̀, àti pé ó jíǹdé ní ijọ́ kẹta gẹ́gẹ́ bí iwe mímọ́ tí wí

---

**En'am 6:164...**gbogbo ise tie mi kokan ba se o se fun ori ara re, olureru kan ko ni ru eru elomiran...

**İsra 17:15...**Areru kan ko ni ru eru elomiran...

**Nejm 53:38...**aru eru (ese) kan ko ni le ru eru (ese) elomiran...

## 86.

**Ninu Ìwé mímọ́ se a se akosile abi igba oro sile wòlíì pe Mèsáyà (Jésù) ma a ku?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Orin Dafidis 16:10...**nítorí ìwọ kò ní fi ọ̀kan sílẹ̀ nínú iṣà òkú, tàbí kí ìwọ jẹ́ kí ẹni mímọ́ Rẹ kí ó rí ìdíbàjẹ́

**Aisaya 53:1-12...11.** Òun ni yóò sì ru àìṣedédé wọn...12. nítorí pé òun jọ̀wọ́ ẹ̀míi rẹ̀ fún ikú, tí a sì kà á mọ́ àwọn alárèékọjá Nítorí ó ru ẹ̀ṣẹ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀, ó sì ṣe ìlàjà fún àwọn alárèékọjá.

**Danięli 9:26...** Lẹ́yìn ọ̀ṣẹ̀ méjìlélọ́gọ́ta, a ó ké ẹni òróró náà kúrò, kò sì ní ní ohun kan. Àwọn ènìyàn alákòóso tí yóò wá ni yóò pa ìlú náà àti ibi mímọ́ run. Òpin yóò dé bí ìkún omi: ogun yóò máa jà títí dé òpin, a sì ti pàṣẹ ìdahoro.

---

**Al-i İmran 3:55...**Nigbati Olohun wipe: Iwo Isa! Emi yio pa o, Emi yi o sig be o wa si odo Mi, Emi yio si we o mo kuro lowo awon alaigbagbo, Emi yio si se idajo larin nyin nipa ohun ti enyin nse iyapa enu si...

**Meryem 19:30 & 33...**O fun mi ni Tira, O si ti se mi ni Annabi kan...33.Ati ki alaafia kio ma ba mi ni ojo ti a bi mi, ati ni ojo tie mi yio ku ati ni ojo ti a o ba gbe mi dide ni aye...

# 87.

**Se Jésù funra ara re so wipe a ma a pa oun nipase Àwọn Júù?**

Bibeli **Bẹẹni** / **Rara** Al-Qur'an

**Matiu 16:21-23...**Láti ìgbà yìí lọ, Jésù bẹ̀rẹ̀ sí iṣàlàyé fún àwọn ọmọ-ẹ̀yin rẹ̀ kedere nípa lílọ sí Jerúsálémù láti jẹ ọ̀pọ̀ ìyà lọ́wọ́ àwọn, olórí àwọn àlùfáà àti àwọn olùkọ́ òfin, pé wọn yóò pa òun, àti pé òun yóò jí dìde sí ààyè ní ọjọ́ kẹta.
**Johanu 10:11 & 15...**Èmi ni olùṣọ́ àgùntàn rere: olùṣọ́-àgùntàn rere fi ọkàn rẹ̀ lélẹ̀ nítorí àwọn àgùntàn...15. Gẹ́gẹ́ bí Baba ti mọ̀ mí, tí èmi sì mọ Baba; mo sì fi ọkàn mi lélẹ̀ nítorí àwọn àgùntàn
**Johanu 12:32-33...**Àti èmi, bí a bá gbé mi sókè èmi ó fa gbogbo ènìyàn sọ́dọ̀ ara mi!" 33. Ṣùgbọ́n ó wí èyí, ó ń ṣàpẹrẹ irú ikú tí òun ó kú.

---

**Kíyèsí:** ko si akosile ninuKùránìnibi ti Jésù funra ara re ti so wipe a ma a pa oun nipase Àwọn Júù

# 88.

**Se otito ni wipe ara ìyára Kristi ku lori agbelebu ati wi pe o ji dide kuro ninu oku?**

Bibeli **Bẹẹni** / **Rara** Al-Qur'an

**Matiu 27:50...**Nígbà tí Jésù sì kígbe ní ohùn rara lẹ́ẹ̀kan sí i, ó jọ̀wọ́ ẹ̀mí rẹ̀, ó sì kú
**Maku 15:37...**Jésù sì tún kígbe soke ni ohùn rara, ó jọ̀wọ́ ẹ̀mí rẹ̀ lọ́wọ́.
**Luku 24:44 & 46...**Ó sì wí fún wọn pé, "Wọ̀nyí ni ọ̀rọ̀ tí mo sọ fún yín, nígbà tí èmí ti wà pẹ̀lú yín pé: A ní láti mú ohun gbogbo ṣẹ, tí a ti kọ nínú òfin Mósè, àti nínú ìwé àwọn wòlíì, àti nínú Sáàmù, nípasẹ̀ mi. 46. Bẹ́ẹ̀ ni a ti kọ̀wé rẹ̀, pé: Kí Kírísítì jìyà, àti kí ó sì jíǹde ní ijọ́ kẹ́ta kúrò nínú òkú
**Johanu 19:30...**Nígbà tí Jésù sì ti gba ọtí kíkan náà, ó wí pé, "Ó parí!" Ó sì tẹ orí rẹ̀ ba, ó jọ̀wọ́ ẹ̀mí rẹ̀.
**1 Kọrinti 15:3-4...3.** Nítorí èyí tí mo rí gbà ṣáájú ohun gbogbo ní èmi pẹ̀lú ti gbà lé e yín lọ́wọ́, bí Kírísítì ti kú nítorí ẹ̀ṣẹ̀ wá gẹ́gẹ́ bí ìwé mímọ́ tí wí. 4. Àti pé a sìnkú rẹ̀, àti pé ó jíǹdé ní ijọ́ kẹtà gẹ́gẹ́ bí iwe mímọ́ tí wí

---

**Nisa 4:157...**Won ko pa a , be si ni nwon ko kan mo agbelebu (alore) sugbon a je ki o ri be loju nwon ni, atipe dajudaju awon ti o se iyapa enu nipa re dajudaju nwon mbe ninu iyemeji nipa re, k si si mimo kan fun nwon ni pa re ayafi itele aroso; be si ni nwon ko pa dajudaju.

# 89.

**Se otito ni wipe Kristi wa laaye loni ati pe o n pada bo?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 14:2-3...**Nínú ilé Baba mi ọpọ̀lọpọ̀ ibùgbé ni ó wà: ìbá má ṣe bẹ́ẹ̀, èmi ìbá tí sọ fún yín. Èmi ń lọ láti pèsè àyè sílẹ̀ fún yín. 3. Bí mo bá sì lọ láti pèsè àyè sílẹ̀ fún un yín, èmi ó tún padà wá, èmi ó sì mú yín lọ sọ́dọ̀ èmi tìkáara mi; pé níbi tí èmi gbé wà, kí ẹ̀yin lè wà níbẹ̀ pẹ̀lú.
**Ìfihàn 2:25...** Ṣùgbọ́n èyí tí ẹ̀yin ní, ẹ di i mú ṣinṣin títí èmi ó fi dé.
**Ìfihàn 22:12 & 20...**Kíyèsí i, èmi ń bọ̀ kánkán; èrè mí sì ń bẹ pẹ̀lú mi, láti sán fún olúkúlùkù gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ rẹ̀ yóò tí rí. 20. Ẹni tí ó jẹ̀rìí nǹkan wọ̀nyí wí pé, "Nítòótọ́ èmi ń bọ̀ kánkán." Àmín, Má a bọ̀, Jésù Olúwa!

---

**Nisa 4:158.....**Olohun gbe lo si odo ara Re...
**Zuhruf 43:61....**Atipe on je mimo kan fun akoko na, nitorina e ma se iyemeji si...
**Kíyèsí:**Ese mẹ́tàléláàádọ́rin ninu Bíbélì lo soro nipa ipadabo Jesu leekeji

# 90.

**Nje a ri awon ese Bíbélì ti o "sàsọtẹ́lẹ̀" tabi "sàsọsiwájú" pipada Hz. Muhammed?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 24:11 & 26...**ọ̀pọ̀ àwọn wòlíì èké yóò farahàn, wọn yóò tan ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn jẹ. 26. Nítorí náà, bí ẹnìkan bá sọ fún yín pé, 'Olùgbàlà ti dé,' àti pé, 'Ó wà ní ihà,' ẹ má ṣe wàhálà láti lọ wò ó, tàbí tí wọ́n bá ní ó ń fara pamọ́ sí iyàrá, ẹ má ṣe gbà wọn gbọ́
**Johanu 5:31...**Bí èmi bá ń jẹ́rìí ara mi, ẹ̀rí mi kì í ṣe òtítọ́
**2 Kọrinti 13:1...** Èyí ni ó dí ìgbà kẹta tí èmi ń tọ̀ yín wá. Ní ẹnu ẹlẹ́rìí méjì tàbí mẹ́ta ni a ó fí ìdí ọ̀rọ̀ gbogbo múlẹ̀

---

**A'raf 7:157...**Awon na ni eniti nwon tele ti Ojise na, Annabi na, eniti ko mo ko ti ko mo ka, eniti nwon ba akosile re lodo won ninu At-Taora ati ninu Injila
**Saf 61:6...**Isa sope: Emi je Ojise Olohun si nyin ti o jeri ododo si ohun ti o ti siwaju ninu At-Tahorata mo si je olufun nyin ni iro idunnu nipa Ojise kan ti yio de lehin mi ti oruko Re yio ma je Ahmadu...

## 91.

**Láti lè je kiHz. Muhammedlè yẹ̀ lẹ́ni tó máa  a je̖ Iranse lati bá àwọn èèyàn sọrọ̀ nipa àwọn àsọtẹlẹ̀ Ọlọ́run ti a ko sile, Ǹjẹ́ o nilo lati je Juu ti o ka iwe?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 4:22...**Ẹ̀yin ń sin ohun tí ẹ̀yin kò mọ̀: àwa ń sin ohun tí àwa mọ̀: nítorí ìgbàlà ti ọ̀dọ̀ àwọn Júù wá

**Romu 3:1-2...**Ǹjẹ́ àǹfààní wo ní Júù ní? Tàbí kín ni èrè ilà kíkọ? 2. Púpọ̀ lọ́nà gbogbo; pàtàkì jùlọ ni pé àwọn ni a fi ọ̀rọ̀ Ọlọ́run lé lọ́wọ́.

**Romu 9:4...**Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ni Ọlọ́run ti fi fún yín: Ṣùgbọ́n síbẹ̀, ẹ kì yóò tẹ́tí sí i. Ó yàn yín bí ẹni ọ̀tọ̀ fún ara rẹ̀. Ó sìn yín (la ihà já) pẹ̀lú ìtànsán ògo rẹ̀, ó mú kí ó dá a yín lójú pé òun yóò bù kún yín, ó fi òfin fún yín kí ẹ le mọ ìfẹ́ rẹ̀ lójojúmọ́, ó yọ̀ǹda fún yín láti sin òun pẹ̀lú ìpinnu ńlá.

---

**A'raf 7:157-158...**Awon na ni eniti nwon tele ti Ojise na, Annabi na, eniti ko mo o ko ti ko mo ka….

**Shura 42:52....**Atipe bayi ni A se fi ise reran wa ninu ase Wa ranse si o. Ire ko mo ohun ti Tiran a je…

## 92.

**Se kíkéde tara-ẹni-nìkan ti Hz. Muhammed se nipa jije Iranse Olorun je eri ti o fidi mule nipa ipe si ise iranse?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 5:31 & 36...31.** Bí èmi bá ń jẹ́rìí ara mi, ẹ̀rí mi kì í ṣe òtítọ́. 36.Ṣùgbọ́n èmi ní ẹ̀rí tí ó pọ̀ju ti Jòhánù lọ: nítorí iṣẹ́ tí Baba ti fi fún mi láti ṣe parí, iṣẹ́ náà pàápàá tí èmi ń ṣe náà ń jẹ́rí mi pé, Baba ni ó rán mi

**1 Kọrinti  14:32-33...**Ẹ̀mí àwọn wòlíì a sí máa tẹríba fún àwọn wòlíì. 33. Nítorí Ọlọ́run kì í ṣe Ọlọ́run ohun rúdurùdu, ṣùgbọ́n ti àlàáfíà. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ nínú gbogbo ijọ ènìyàn mímọ́

**2 Kọrinti  13:1...**Èyí ni ó dí ìgbà kẹta tí èmi ń tọ̀ yín wá. Ní ẹnu ẹlẹ́rìí méjì tàbí mẹ́ta ni a ó fí ìdí ọ̀rọ̀ gbogbo múlẹ̀

---

**Rad 13:43...**Atipe awon alaigbagbo nso kiri pe Ire ki ise ojise kan. Wipe: Olohun to ni eleri ni arin emi ati enyin ati enikeni ti mimo tira na mbe ni odo re.

**Fetih 48:28...**On Olohun ni Eniti o ran Ojise re ni ise pelu itonisona ati esin ododo ki o le fi bori gbogbo esin-kesin. Olohun to julo fun eleri...

# 93.

**Se awon oro ti Hz. Muhammed so wa ni ibamu pipe pelu awon oroti Jésù ati awon Wòlíì miran?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Aisaya 8:20** ...Sí òfin àti májẹmú! Bí wọn kò bá sọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ yìí, wọn kò ní ìmọ́lẹ̀ ọjọ́.
**1 Kọrinti 14:32-33...**Ẹ̀mí àwọn wòlíì a sí máa tẹríba fún àwọn wòlíì. 33. Nítorí Ọlọ́run kì í ṣe Ọlọ́run ohun rúdurùdu, ṣùgbọ́n ti àlàáfíà. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ nínú gbogbo ijọ ènìyàn mímọ́

---

**Shu'ara 26:192-197....**Atipe dajudaju eyi (Al-Kurani) je ohun ti o sokale lati odo Oluwa gbogbo eda wa. 196. Atipe om be ninu Tira ti awon eni akoko. 197. Abi ko wa je ami kan fun nwon nip e awon alufa awon omo Israila mo be?
Fussilet 41:43...Nwon ko so kinikan fun O bikose iru awon eyi tin won ti so fun awon Ojise tin won ti siwaju re...
**Shura 42:15...**sope: Emi ni igbagbo ododo si ohun ti Olohun sokale ni Tira...ko si ijiyan larin awa ati enyin...

# 94.

**ṣe Ọlọ́run fun Hz. Muhammed ni ágbára agbayanu lati se awon iṣẹ́ ìyanu bi I Jésù ati awon wòlíì miran gege bi ifesemule pe Olorun lo ran an nise?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 5:36...**Ṣùgbọ́n èmi ní ẹ̀rí tí ó pọ̀ju ti Jòhánù lọ: nítorí iṣẹ́ tí Baba ti fi fún mi láti ṣe parí, iṣẹ́ náà pàápàá tí èmi ń ṣe náà ń jẹ́rí mi pé, Baba ni ó rán mi
**Johanu 14:11...**Ẹ gbà mí gbọ́ pé, èmi wà nínú Baba, Baba sì wà nínú mi: bí kò ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ gbà mí gbọ́ nítorí àwọn iṣẹ́ náà pàápàá

---

**En'am 6:37-38...**Nwon tun nsope: Ese ti A ko so Ayah kan kale fun u lati odfo Oluwa re? Dajudaju Olhun ni agbara lori ati so Ayah kan kale...38. Awa ko se kinikan ku ninu tira ni...
**Yunus 10:20...**Nwon si nsope: kilose ti A o so ami kan kale fun u lati odo Oluwa re? Dajudaju ohun ti o pamo ti Olohun ni, nitorina e ma reti; emi na yio ma be ninu awon olureti pelu nyin..
**Kíyèsí:** akosile iṣẹ́ ìyanu metadinọgọ́jọ ti Jésù se ati awon wòlíì miran ninu Bíbélì, sugbon ko si akosile ti o fara jo eyi fun Hz. Muhammed ninu Kùránì.

## 95.

**ṣe Hz. Muhammed ni ebun ágbára woli lati "sàsọtẹ́lẹ̀" tabi "sàsọsiwájú" bi I Jésù ati awo nWòlíì miran?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**Diutaronomi 18:22...**Nígbà tí ohun tí wòlíì bá sọ ní orúkọ Olúwa kò bá wá sí ìmúṣẹ tàbí jẹ́ òtítọ́, ìyẹn ni ọ̀rọ̀ tí Olúwa kò sọ, irú wòlíì bẹ́ẹ̀ tí sọ láìwádìí. Kí ẹ má ṣe bẹ̀rù rẹ̀.
**1 Samuẹli 9:9...**Tẹ́lẹ̀ ní Ísírẹ́lì tí ọkùnrin kan bá lọ béèrè lọ́dọ̀ Ọlọ́run, yóò wí pé, "Wá, Jẹ́ kí a lọ sí ọ̀dọ̀ wòlíì náà," nítorí àwọn aláṣọtẹ́lẹ̀ ìsinsìn yìí ni wọ́n ń pè ní wòlíì
**Aisaya 41:22...**Mú àwọn ère-òrìṣà rẹ wọlé láti sọ fún wa ohun tí yóò ṣẹlẹ̀. Sọ fún wa ohun tí àwọn nǹkan àtijọ́ jẹ́, kí àwa lè ṣe àgbéyẹ̀wò wọn kí àwa sì mọ àbájáde wọn nípari. Tàbí kí o sọ fún wa ohun tí ó ń bọ̀ wá...

---

**En'am 6:50...**Sope: Emi ko so fun nyin pe pepe oro ti Olohunmbe ni odo mi, be si ni emi ko mo ohun ti o pamo...
**Ahkaf 46:9...**Emi ko mo ohun ti ao se fun mi ati fun enyin na, emi ko tele kinikan ayafi ohun ti a ba fi ranse si mi...

## 96.

**Ǹjẹ́ Ọlọ́run Ábúráhámù fi aaye gba Hz. Muhammed lati fenuko okuta dudu ni Ka'ba Hz.tabi fi aye gba bibowo fun àwọn òrìṣà abọ̀rìṣà Lárúbáwá re?**

Bibeli **Rara / Bẹ̀ẹ̀ni** Al-Qur'an

**Ẹkisodu 20:3-5...** 3.Ìwọ kò gbọdọ̀ ní Ọlọ́run mìíràn pẹ̀lú mi. bẹ́ẹ̀ ni ìwọ kò gbọdọ̀ sìn wọ́n; nítorí Èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ, Ọlọ́run owú ni mí,
**1 Àwọn Ọba 19:18...**Ṣíbẹ̀, Èmi ti pa ẹẹ́dẹ́gbàarin (700) ènìyàn mọ́ fún ara mi ní Ísírẹ́lì, àní gbogbo eékún tí kò ì tíì kúnlẹ̀ fún òrìṣà Báálì, àti gbogbo ẹnu tí kò ì tí ì fi ẹnu kò ó ní ẹnu.
**2 Kọrinti 6:16...**Tàbí ẹ kò mọ̀ pé bí ẹnìkan bá so ara rẹ̀ pọ̀ mọ́ àgbérè ó jẹ́ ara kan pẹ̀lú rẹ¬? Nítorí a tí kọ ọ́ wí pé, "Àwọn méjèèjì ni yóò di ara kan ṣoṣo.

---

**Bakara 2:158...**Dajudaju Safa ati Marwa wa ninu Awon ami Olohun, enikeni ti o bar in irin ajo lo si ile na ni asiko Haj tabi ti o lo be e wo ni igba miran, ko si ese fun u bi o bar o kiri kawon...
**Nejm 53:18-20...**nje enyin ko ha ri (orisa) Lata ati (orisa) Usa..20.. Ati (orisa) Manata eyiti o keta nikehin.

## 97.

**Ǹjẹ́ a fi oju eniyan eleran ara woHz. Muhammed tabi eniyan ti o nilo idariji ese?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìwé Oníwàásù 7:20...**Kò sí olódodo ènìyàn kan láyé tí ó ṣe ohun tí ó tọ́ tí kò dẹ́ṣẹ̀ rárá.

**2 Johanu 1:8 & 10...**Ẹ kíyèsára yín, kí ẹ má ba à sọ iṣẹ́ tí ẹ tí ṣe nù, ṣùgbọ́n kí ẹ̀yin lè rí èrè kíkún gbà. 10. Bí ẹnikẹ́ni bá tọ̀ yín wá, tí kò sì mu ẹ̀kọ́ yìí wá, ẹ má ṣe gbà á sí ilé, kí ẹ má sì ṣe kí i kú àbọ̀

---

**Nisa 4:106....**ki o si toro aforijin ni odo Olohun, dajudaju Olohun je alaforijin, Alaanu.

Yusuf 12:53...Emi ko koja eniti o le dese; dajudaju emi ife-inu mi ma n pami lase iwa aidara...

**Muhammad 47:19....**Ki o si wa aforijin kuro nibi ese dida fun ara re..

**Fatih 48:1-2...**Dajudaju Awa ti fun o ni isegun ti o han gbangba.

## 98.

**Ǹjẹ́ a se iriri Hz. Muhammed gege bi wòlíì ti o gbeyin ti o si lokiki ju?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìfihàn 1:1, 8 & 17...**Ìfihàn ti Jésù Kírísítì, tí Ọlọ́run fi fún un, láti fi hàn fún àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀, ohun tí kò le ṣàìṣe ní lọ́ọ́lọ́; ó sì ránṣẹ́, ó sì fi í hàn láti ọwọ́ áńgẹ́lì rẹ̀ wá fún Jòhánù, ìránṣẹ́ rẹ̀. 8. Èmi ni Álfà àti Òmégà," ni Olúwa Ọlọ́run wí, "ẹni tí ó ń bẹ, tí ó ti wà, tí ó sì ń bọ̀ wá, Olódùmarè. 17. Nígbà tí mo rí i, mo wólẹ̀ ní ẹsẹ̀ rẹ̀ bí ẹni tí ó kú. Ó sì fi ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ lé mi, ó ń wí fún mi pé, "Máṣe bẹ̀rù. Èmi ni ẹni-ìṣájú àti ẹni-ìkẹyìn

**Ìfihàn 22:13, 16 & 20...**Èmi ni Álífà àti Òmégà, ẹni ìṣáájú àti ẹni ìkẹyìn, ìpilẹ̀ṣẹ̀ àti òpin. 16. Èmi, Jésù, ni ó rán áńgẹ́lì mi láti jẹ̀rìí nǹkan wọ̀nyí fún yin ní tí àwọn ìjọ. Èmi ni gbòngbò àti irú-ọmọ Dáfídì, àti ìràwọ̀ òwúrọ̀ tí ń tàn 20. Ẹni tí ó jẹ̀rìí nǹkan wọ̀nyí wí pé, "Nítòótọ́ èmi ń bọ̀ kánkán."

---

**Ahzab 33:40...**Muhamadu ki ise baba enikankan ninu awon okunrin nyin, sugbon O je Ojise Olohun ati ipekun awon annabi. Olohun si je oni-mimo nipa gbogbo nkan.

**Fatih 48:28...**On Olohun ni eniti o ran Ojise re ni ise pelu itonisona ati esin ododo ki o le fi bori gbogbo esin-kesin. Olohun to julo fun eleri

**Kíyèsí:**a ni ireti pe Jésùn pada bo. A ko reti Hz. Muhammed.

## Ènìyàn ati ẹṣẹ̀

## 99.

**Nigba ti Adamu ati Efa d'ese, o fa iyapa pàtàkì gan-an si aarin Ọlọ́run ati ènìyàn ti o wa yori si ki ènìyàn nilo igbala kuro ninu idajo?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Jẹnẹsisi 2:16-17...**wí fún obìnrin náà pé: "Èmi yóò fi kún ìrora rẹ ní àkókò ìbímọ; ni ìrora ni ìwọ yóò máa bí ọmọ. Ọ̀dọ̀ ọkọ rẹ ni ìfẹ́ rẹ yóò máa fà sí, òun ni yóò sì máa ṣe àkóso rẹ." 17 Ọlọ́rún sì wí fún Ádámù pé, "Nítorí pé ìwọ fetí sí aya rẹ, ìwọ sì jẹ nínú èṣo igi tí mo pàṣẹ fún ọ pé 'Ìwọ kò gbọdọ̀ jẹ nínú rẹ̀,' "Ègún ni fún ilẹ̀ nítorí rẹ; nínú ọpọ̀ làálàá ni ìwọ yóò jẹ nínú rẹ̀, ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ.
**Romu 5:12-19...**Nítorí gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ṣẹ̀ ti tipa ọ̀dọ̀ ènìyàn kan wọ ayé, àti ikú nípa ẹ̀ṣẹ̀ bẹ́ẹ̀ni ikú sì kọjá sórí ènìyàn gbogbo, láti ọ̀dọ̀ ẹni tí gbogbo ènìyàn ti dẹ́ṣẹ̀

---

**Bakara 2:35-38...**Awa wipe: Adama! Mase sunmo igi yi ki e ma ba di ara awon alabosi...37. Lehinna Adama ri awon oro kan gba lati odo Oluwa re, On gba ironupiwada re, On ni Olugba ironupiwada, Alaanu.

## 100.

**Se awon ese Bibeli ti o so nipa ibi wa gege bi elese tabi jijẹ́ẹ̀dá ẹlẹ́ṣẹ̀wa ninu Bibeli (Ojulowoẹ̀ṣẹ̀)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Aisaya 64:6...**Gbogbo wa ti dàbí ẹnìkan tí ó jẹ́ aláìmọ́, gbogbo òdodo wa sì dàbí èkíṣà ẹlẹ́gbin; gbogbo wa kákò bí ewé, àti bí afẹ́fẹ́, ẹ̀ṣẹ̀ wa ti gbá wa lọ kúrò
**Jeremaya 13:23...**Ǹjẹ́ Ètópíà le yí àwọ̀ rẹ̀ padà? Tàbí ẹkùn lè yí àwọ̀ rẹ̀ padà? Bí èyí kò ti lè rí bẹ́ẹ̀ náà ni ẹ̀yin tí ìwà búburú bá ti mọ́ lára kò lè ṣe rere.
**Jeremaya 17:9...**Ọkàn kún fún ẹ̀tàn ju ohun gbogbo lọ, ó kọjá ohun tí a lè wòsàn, tani èyí lè yé?
**Romu 3:23....**Gbogbo ènìyàn ni ó sá ti ṣẹ̀, tí wọ́n sì kùnà ògo Ọlọ́run

---

**Taha 20:122...**Lehin na Oluwa re sa a lesa, O si gba ituba re, O si to o sona.
**Tin 95:4...**Dajudaju A da eniyan ni eya daradara julo...

## 101.

**Segbogboeniyan pelu awon wòlíìni o jebi dida ẹ̀ṣẹ̀? (a yo Jésù kuro)**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**1 Àwọn Ọba 8:46...**Nígbà tí wọ́n bá ṣẹ̀ sí ọ, nítorí kò sí ẹnìkan tí kì í ṣẹ̀, tí ìwọ sì bínú sí wọn, tí ìwọ sì fi wọ́n lé ọ̀tá lọ́wọ́, tí ó kó wọn ní ìgbékùn lọ sí ilẹ̀ wọn, jínjìnnà tàbí nítòòsí

**Orin Dafidi 130:3...**Olúwa, ìbáṣe pé kí ìwọ kí o máa ṣàmì ẹ̀ṣẹ̀, Olúwa, tà ni ìbá dúró.

**Ìwé Òwe 20:9...**Táni ó le è wí pé, "Mo ti ṣe ọkàn mi ní mímọ́, mo mọ́, n kò sì lẹ́ṣẹ̀"?

**Romu 3:10...**Gẹ́gẹ́ bí a ti kọ ọ́ pé: "Kò sí ẹni tí í ṣe olódodo, kò sí ẹnìkan

**2 Johanu 1:8...**Ẹ kíyèsára yín, kí ẹ má ba à sọ iṣẹ́ tí ẹ tí ṣe nù, ṣùgbọ́n kí ẹ̀yin lè rí èrè kíkún gbà

---

**Yusuf 12:53...**Emi ko koja eniti o le dase; dajudaju emi ife-inu ma npa ni lase iwa aidara...

**İbrahim 14:34...**dajudaju awon eniyan je alabosi alaimore...

**Nahl 16:61...**Ti o ba se pe Olohun yio mu awon eniyan nitori abosi nwon ni, ko ba ti fi eda kan sile lori ile...

**Shu'ara 26:82...**Atipe On ni Eniti mo n se ireti pe yio fi ori asise mi jin mi ni ojo esan...

**Muhammad 47:19...**Ki o si wa aforiji kuro nibi ese dida fun ara re...

## 102.

**Nje a se afihan tabi iriri Maria, Iya to biJésù,gege bi eni ti o ni ànímọ́ àtọ̀runwá ati pe se a le pe e ni iya Ọlọ́run?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**Aisaya 42:8...**Èmi ni Olúwa; orúkọ mi nìyìí! Èmi kì yóò fi ògo mi fún ẹlòmìíràn tàbí ìyìn mi fún ère-òrìṣà.

**Johanu 2:3-5...**Nígbà tí wáìnì sì tán, ìyá Jésù wí fún un pé, "Wọn kò ní wáìnì mọ́."
4.Jésù fèsì pé, "Arábìnrin ọ̀wọ́n, èése tí ọ̀rọ̀ yìí fi kàn mí? Àkókò mi kò tí ì dé."
5. Ìyá rẹ̀ wí fún àwọn ìránṣẹ́ náà pé, "Ẹ ṣe ohunkóhun tí ó bá wí fún yín."

---

**İsra 17:22-23...**Atipe Oluwa re pa lase pe: E ko gbodo sin kinikan ayafi On nikan...

**Zariyat 51:56...**Atipe Emi ko se eda alijonu ati eniyan lasan ayafi kin won le ma sin Mi.

## 103.

Ṣe ẹṣẹ̀ ti o ya èniyàn kuro ninu iwa Mímọ́ Ọlọ́run ti o je mimo, ati gege bi iìyọrísí tabi àbájáde èyí pe gbogbo ẹlẹṣẹ̀ ni a ti da lejo si"ọ̀run àpáàdì?

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Isikiẹli 18:4 & 20...**Nítorí pé èmi ló ní gbogbo ọkàn, ọkàn baba tèmi bẹ́ẹ̀ ni ọkàn ọmọ pàápá jẹ tèmi, ọkàn tó bá sẹ̀ ní yóò kú. 20. Ọkàn tí ó bá sẹ̀ ní yóò kú. Ọmọ kò ní í ru ẹ̀bi baba rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni baba náà kò ní i ru ẹ̀bi ọmọ rẹ̀. Ìwà rere èniyàn rere yóò wà lórí rẹ̀, ìwà búburú ti èniyàn búburu náà la ó kà síi lọ́rùn.

**Luku 12:5...** Ṣùgbọ́n èmi ó sì sọ ẹni tí ẹ̀yin ó bẹ̀rù fún yín: Ẹ bẹ̀rù ẹni tí ó lágbára lẹ́yìn tí ó bá pàniyàn tan, láti wọ́ ni lọ sí ọ̀run àpádì:

**Ìfihàn 20:13—15...**Òkun sì jọ̀wọ́ àwọn òkú tí ń bẹ nínú rẹ̀ lọ́wọ́; àti òkú àti ipò-òkú sì jọ̀wọ́ òkú tí ó wà nínú wọn pẹ̀lú: a sì ṣe ìdájọ́ wọn, olúkúlùkù gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ wọn. 14. Àti ikú àti ipò-òkú ni a sì sọ sínú adágún iná. Èyí ni ikú keji. 15. Bí a bá sì rí ẹnikẹ́ni tí a kò kọ orúkọ rẹ̀ sínú ìwé ìyè, a ó sọ ọ́ sínú adágún iná.

---

**A'raf 7:41...**ite mbe fun nwon ninu inu Jahannama, ebibo ina sim be fun nwon ni oke ori won gege bayi ni awa nsan esan fun awon alabosi...Atipe awon eniti o n se buburu...awon wonyi ni ero ina, inu re ni nwon o se gbere si.

**Yunus 10:27 –** Atipe awon eniti o se buburu, esan buburu iru re… Awon wonyi ni ero ina inu re ni nwon o se gbere si.

## 104.

**Ṣe Ọlọ́run Mímọ́ a ma a ka awon ese kekere si?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 5:19...** Ẹnikẹ́ni ti ó bá rú òfin tí ó tilẹ̀ kéré jù lọ, tí ó sì kọ́ ẹlòmíràn láti ṣe bẹ́ẹ̀, òun ni yóò kéré jù lọ ní ìjọba ọ̀run,

**Matiu 12:36...** Ṣùgbọ́n, mo sọ èyí fún yín, ẹ̀yin yóò jíyìn gbogbo ìsọkúsọ yín ní ọjọ́ ìdájọ́.

**1 Kọrinti 5:6...**Ìfọ́nnú yín kò dára. Ẹ̀yin kò mọ̀ pé ìwúkàrà díẹ̀ ní i mú gbogbo ìyẹ̀fun di wíwú?

**Jakọbu 2:10...**Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá pa gbogbo òfin mọ́, tí ó sì rú ọ̀kan, ó jẹ̀bi rírú gbogbo rẹ̀.

---

**Ahzab 33:5...**Atipe ko si ese fun nyin nipa eyi ti e ba fi sise sugbon (ebi wa fun nyin lori) eyiti okan nyin momo se...

**Nejm 53:31-32...**Awon eniti nwon jina si ese nlanla ati iwa ibaje ayafi awon ese pepepe, dajudaju Oluwa Re je Oba ti O gboro ni aforiji. 32. nitorina ema se ma fo ara nyin mo...

# 105.

**Se ifiya jeni ti o ton ani gige owo eni ti o ba ja ole?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ẹkisodu 22:1-4...**Bí ọkùnrin kan bá jí akọ màlúù tàbí àgùntàn, tí ó sì pa á tàbí tà á. Ó gbọdọ̀ san akọ màlúù márùn ún padà fún ọkan tí ó jí, àti àgùntàn mẹ́rin mìíràn fún ọkan tí ó jí.
4"Bí a bá rí ẹran tí ó jí gbé náà ni ọwọ́ rẹ̀ ní ààyè: ìbá se akọ màlúù, akọ kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ tàbí àgùntàn, yóò san án padà ní ìlọ́po méjì.
**Ìwé Òwe 6:30-31...**30. Àwọn ènìyàn kì í kẹ́gàn olè tí ó bá jalè nítorí àti jẹun nígbà tí ebi bá ń pa á. 31. Ṣíbẹ̀ bí ọwọ́ bá tẹ́ẹ́, ó gbọdọ̀ san ìlọ́po méje
**Luku 6:35-36...**35. Ṣùgbọ́n kí ẹ̀yin fẹ́ àwọn ọ̀ta yín kí ẹ̀yin sì ṣoore, kí ẹ̀yin sì yá, kí ẹ̀yin má ṣe retí láti rí nǹkan gbà padà; èrè yín yóò sì pọ̀, àwọn ọmọ ọ̀gá ògo ni a ó sì máa pè yín: nítorí tí ó ṣeun fún aláìmoore àti fún ẹni búburú. 36. Ǹjẹ́ kí ẹ̀yin ní àánú, gẹ́gẹ́ bí Baba yín sì ti ní àánú.

---

**Maide 5:38...**ole okunrin ati ole obinrin, e ge owo nwon mjejeji ni esan fun ise awon mejeji, arikogbon lati odo Olohun...

# 106.

**Ǹjẹ́ o da nigba miran fun onigbagbo lati pa iro tabi tan elomiran je nitori won n gbiyanju latidáàbòbòara won? (Taqiyya or Kitman)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìwé Òwe 6:16-17...**16. Àwọn ohun mẹ́fà wà tí Olúwa kórìíra, ohun méje ní ó jẹ́ ìríra síi: 17. Ojú ìgbéraga, Ahọ́n tó ń parọ́ọ́wọ́ tí ń ta ẹ̀jẹ̀ aláìṣẹ̀ sílẹ̀
**Sefanaya 3:13...**Àwọn ìyókù Ísírẹ́lì kì yóò hùwà ibi, wọn kì yóò sọ̀rọ̀ èké, bẹ́ẹ̀ ni a kì yóò rí ahọ́n àrékérekè ní ẹnu wọn. Àwọn yóò jẹun, wọn yóò sì dùbúlẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni kì yóò dẹrù bà wọn
**Efesu 4:25...**Nítorí náà ẹ fi èké ṣiṣe sílẹ̀, kí olúkúlùkù yín máa ba ọmọnìkejì rẹ̀ sọ òtítọ́, nítorí ẹ̀yà ara ọmọnìkejì wa ni àwá jẹ́
**Ìfihàn 21:8 & 27...** 8..Ṣùgbọ́n àwọn ojo... ni yóò ni ipa tiwọn nínú adágún tí ń fí iná àti súfúrù jó: èyí tí i ṣe ikú kéjì. 27. Ohun aláìmọ́ kan ki yóò sì wọ inú rẹ̀ rárá, tàbí ohun tí ń ṣiṣẹ́ ìríra àti èké; bí kò ṣe àwọn tí a kọ sínú ìwé ìyè Ọ̀dọ́-Àgùntàn.

---

**Bakara 2:225...**Olohun ko ni mu nyin fun ibura nyin ti ko ti inu wa...
**Tahrim 66:2...**olohun ti se ofin fun nyin bi e ti ma moribo ninu ibura nyin...
**Kíyèsí:** Taqiyya = siso ohun ti o kii n se otito.
Kitènìyàn =Piparo nipa sise ayokuro

## 107.

**Se a se iriri tabi ifojusi ìbẹ́yà-kannáà-lòpọ̀ gege bi ese ti o je eewo ti a si ti fi gegun?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Lefitiku 18:22..**Ìwọ kò gbọdọ̀ bá ọkùnrin lòpọ̀ bí ìgbà tí ènìyàn ń bá obìnrin lòpọ̀: ìríra ni èyí jẹ́.
**Lefitiku 20:13...**Bí ọkùnrin kan bá bá ọkùnrin mìíràn lòpọ̀ bí wọ́n í ti bá obìnrin lòpọ̀: àwọn méjèèjì ti ṣe ohun ìríra: pípa ni kí ẹ pa wọ́n, ẹ̀jẹ̀ wọn yóò wà lórí wọn.
**Romu 1:24 & 26-27...24.**Nítorí náà Ọlọ́run fà wọ́n lé ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ọkàn wọn lọ́wọ́ láti máa ṣe ohun ìríra pẹ̀lú ara wọn èyí tí kò tọ́. 26. Nítorí èyí yìí ni Ọlọ́run ṣe fi wọ́n fún ìfẹ́ ìwàkíwà: nítorí àwọn obìnrin wọn tilẹ̀ yí ìlò àdánidá padà sí èyí tí ó lòdì sí ti àdánidá: 27. Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọkùnrin pẹ̀lú, wọn a máa fi ìlò obìnrin nípa ti ẹ̀dá sílẹ̀, wọn a máa fẹ́ ìfẹ́kúfẹ́ sí ara wọn, ọkùnrin ń bá ọkùnrin ṣe èyí tí kò yẹ, wọ́n sì ǹ jẹ èrè ìsìnà wọn nínú ara wọn bí ó ti yẹ sí.

---

**A'raf 7:80-81...**Atipe Awa ran Lutu, nigbati o wi fun awon eniyan re pe: Enyin huwa ibaje ti enikan ko se siwaju nyin ninu awon eda. 81. Dajudaju enyin nlo baa won okunrin sepo, e si fi awon obinrin sile sugbon enyin je awon eniyan kan ti o koja enu ala...
**Neml 27:54-55...**Ise buburu ni e o ma se ni? 55. Enyin yio ha ma yanhanhan ba okunrin (lopo) laise obinrin?

## 108.

**Se a ri oye wipe oyun sise ati ipaniyan je gege bi ese ti o je eewo ti a si ti fi gegun?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Jẹnẹsisi 9:6-7...**Ẹnikẹ́ni tí ó bá ta ẹ̀jẹ̀ ènìyàn sílẹ̀ láti ọwọ́ ènìyàn ni a ó gbà ta ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ sílẹ̀. Nítorí ní àwòrán Ọlọ́run ni Ọlọ́run dá ènìyàn. 7. Ṣùgbọ́n ní tiyín, ẹ máa bí sí i, kí ẹ sì máa pọ̀ sí i, ẹ máa gbá yìn-ìn lórí ilẹ̀, kí ẹ sì pọ̀ sí i lórí rẹ̀
**Ẹkisodu 20:13...**Ìwọ kò gbọdọ̀ pa ènìyàn
**Ẹkisodu 21:12...**Ẹnikẹ́ni tí ó bá lu arákùnrin rẹ̀ pa, pípa ni a ó pa á
**Ìwé Òwe 6:16-17...**16. Àwọn ohun mẹ́fà wà tí Olúwa kórìíra, ohun méje ní ó jẹ́ ìríra síi: 17. Ojú ìgbéraga, Ahọ́n tó ń parọ́ọ̀wọ́ tí ń ta ẹ̀jẹ̀ aláìṣẹ̀ sílẹ̀

---

**Maide 5:32...**enikeni ti o ba pa enikan laije pe nitori pipa enikan tabi sise ibaje kan lori ile, nitorina o da gegebi eniti o pa gbogbo eniyan patapata.
**Isra 17:31...**Atipe e ma pa awon omo nyin mo nitori ipaiya osi. Awa ni nse ije imu nwon ati fun enyin na. Dajudaju pipa ti en pa won je ese ti o tobi.

# 109.

**se a le pa ifiya jeni fun ẹ̀ṣẹ̀re nipa sise "ise rere"? (Sevap)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Romu 3:28...**Nítorí náà a parí rẹ̀sí pé nípa ìgbàgbọ́ni a ń dá ènìyàn láre láìsí iṣẹ́òfin.
**Galatia 3:11...**Nítorí ó dánilójú pé, a kò dá ẹnìkẹ́ni láre níwájú Ọlọ́run nípa iṣẹ́ òfin: nítorí pé, olódodo yóò yè nípa ìgbàgbọ́
**Titus 3:5-6...**Ó gbà wá là. Kì í ṣe nípa iṣẹ́ tí àwa ṣe nínú òdodo bí kò ṣe nítorí àánú rẹ̀. Ó gbà wá là, nípaṣẹ̀ ìwẹ̀nù àtúnbí àti ìsọdọ̀tun ti Ẹ̀mí Mímọ́, 6èyí tí tú lé wa lórí ní ẹ̀kún-rẹ́rẹ́ nípaṣẹ̀ Jésù Kírísítì Olùgbàlà wá.
**Jakọbu 2:10...** Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá pa gbogbo òfin mọ́, tí ó sì rú ọ̀kan, ó jẹ̀bi rírú gbogbo rẹ̀.

---

**Hud 11:114...**Dajudaju awon ise rere ma npa ise buburu re ni...
**Ankebut 29:7...**atipe awon eniti o gbagbo ni ododo tin won sin se ise rere, dajudaju Awa yio ha buburu ise won kuro fun nwon...
**Nejm 53:32...**Awon eniti nwon jina si ise nlanla ati (iwa) ibaje ayafi awon ese pepepe, dajudaju Oluwa re je (Oba) ti O gboro ni aforiji...

# Ìgbàlà
# 110.

**Se a bi eniyan gege bi "Kristiani" tabi a "Musulumi"?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 1:12-13...**12. Ṣùgbọ́n iye àwọn tí ó gbà á, àní àwọn náà tí ó gbà orúkọ rẹ̀gbọ́, àwọn ni ó fi agbára fún láti di ọmọ Ọlọ́run; 13Àwọn ọmọ tí kì íṣe nípa ẹ̀jẹ̀, tàbí nípa ti ìfẹ́ ara, bẹ́ẹ̀ni kì í ṣe nípa ìfẹ́ ti ènìyàn, bí kò ṣe láti ọwọ́ Ọlọ́run.
**Johanu 3:5...** Jésù dáhùn wí pé, "Lóòótọ́ lóòótọ́ ni mo wí fún ọ, bí kò ṣe pé a fi omi àti Ẹ̀mí bí ènìyàn, òun kò lè wọ ìjọba Ọlọ́run
**1 Peteru 1:23...** Bí a ti tún yín bí, kì í ṣe láti inú ìdíbàjẹ́ wá, bí kò ṣe èyí ti kì í díbàjẹ́ nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí ń bẹ láàyè tí ó sì dúró.

---

**Kâfirûn 109:1-6...**1. Sope: Mope enyin alaigbagbo...6..esin (aigbagbo) tiyin wa fun nyin, esin (igba-Olohun-lokan) temi si wa fun mi.
**Kíyèsí:** gege bi ilana Bíbélì a ko le bi enikeni ni Kristieni; awon ti won ti di atunbi nipa emiỌlọ́run nikan ni o ma jogun ijobaỌlọ́run. Ninuẹ̀sìn Ìsìláàmùeni ti Bàbá re ba a je Musulumi ti di Musulumi lati igba ti a bi

# 111.

**Se ìgbàlà eniyan sinmi lórí ise rere won? (Ameller)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Romu 4:2...** Nítorí bí a bá dá Ábúráhámù láre nípa iṣẹ́, ó ní ohun ìṣògo; ṣùgbọ́n kì í ṣe níwájú Ọlọ́run

**Efesu 2:8-9...**Nítorí oore ọ̀fẹ́ ní a fi gbà yín là nípa ìgbàgbọ́: àti èyí yìí kì í ṣe ti láti ọ̀dọ̀ ẹ̀yin fúnra yín: ẹ̀bùn Ọlọ́run ni: 9. Kì í ṣe nípa àwọn iṣẹ́, kí ẹnikẹ́ni má ba à ṣògo.

**Titus 3:5-6...**Ó gbà wá là. Kì í ṣe nípa iṣẹ́ tí àwa ṣe nínú òdodo bí kò ṣe nítorí àánú rẹ̀. Ó gbà wá là, nípaṣẹ̀ ìwẹ̀nù àtúnbí àti ìsọdọ̀tun ti Ẹ̀mí Mímọ́, 6. èyí tí tú lé wa lórí ní ẹ̀kún-rẹ́rẹ́ nípaṣẹ̀ Jésù Kírísítì Olùgbàlà wá.

---

**Hud 11:114...**Dajudaju awon ise rere ma npa ise buburu re ni…

**Ankebut 29:7...**atipe awon eniti o gbagbo ni ododo tin won sin se ise rere, dajudaju Awa yio ha buburu ise won kuro fun nwon...

# 112.

**se ipese Ọlọ́run fun ìgbàlà kuro lowo ebi ẹ̀ṣẹ̀da le lori lilo tabi sise irubo eje? (Kefaret)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Lefitiku 17:11...**Nítorí pé nínú ẹ̀jẹ̀ni ẹ̀mí ẹ̀dá wà èmi sì ti fi fún yín lórí pẹpẹ fún ètùtù ọkàn yín: nítorí pé ẹ̀jẹ̀ni a fi ń ṣe ètùtù fún ẹ̀mí ènìyàn.

**Heberu 9:12 & 22...**Bẹ́ẹ̀ni kì í ṣe nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀ ewúrẹ́ àti ọmọ màlúù, ṣùgbọ́n nípa ẹ̀jẹ̀ òun tìkararẹ̀, o wọ ibi mímọ́ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo, lẹ́yìn tí ó ti rí ìdáǹdè àìnípẹ̀kun gbà fún wa. 22. Ó sì fẹ́rẹ̀ jẹ́ ohun gbogbo ni a fi ẹ̀jẹ̀ wẹ̀nù gẹ́gẹ́ bí òfin; àti pé láìsí ìtàjẹ̀sílẹ̀kò sí ìdáríjì

---

**Bakara 2:48...** Eberu ojo kan, to je pee mi kan ko ni le se anfani kan fun emi keji. Beni a ki yio gba ipe sise kan lowo re, ako si ni gba aro kan lowo re...

**Hajj 22:37...**Eran won ati eje nwon ko ni de odo Olohun, sugbon ipaiya nyin ni yio de odo Re...

## 113.

**Se nipa ore ofe nipase ore pfe ninu ita eje odoaguntan Olorun nikan ni a ti le ri ipese Ọlọ́run fun ìgbàlàgba? (Jésù Kristi)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 1:29...**Nínú rẹ̀ ni àwa ni ìràpadà wa nípa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, ìdáríjì àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, ní ìbámu pẹ̀lú ọrọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run

**Romu 3:24-28...24...** ẹni tí a ń dáláre lọ́fẹ̀ẹ́ nípa oore-ọ̀fẹ́ rẹ̀, nípa ìdáǹdè tí ó wà nínú Kírísítì Jésù. 25...láti jẹ́ ètùtù nípa ìgbàgbọ́ nínú ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ 28. Nítorí náà a parí rẹ̀ sí pé nípa ìgbàgbọ́ ni a ń dá ènìyàn láre láìsí iṣẹ́ òfin

**Efesu 1:7...**Nínú rẹ̀ ni àwa ni ìràpadà wa nípa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, ìdáríjì àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, ní ìbámu pẹ̀lú ọrọ̀ oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run

**Efesu 2:8...**Nítorí oore ọ̀fẹ́ ní a fi gbà yín là nípa ìgbàgbọ́: àti èyí yìí kì í ṣe ti láti ọ̀dọ̀ ẹ̀yin fúnra yín: ẹ̀bùn Ọlọ́run ni

---

**En'am 6:164...**gbogbo ise tie mi kokan ba se o se e fun ori ara re, olureru kan ko ni ru eru elomiran...
İsra 17:15...areru kan ko ni ru eru elomiran...

**Nejm 53:38....**aru-eru (ese) kan ko ni ru eru (ese) elomiran...

## 114.

**Lati le je kieniyan ri iye ainipekun gba, se o pon dandan lalakoko fun won lati gbo ati lati ni oye ihinrere tiJésù Kristi atitun Gbagbo peỌlọ́runlo ran lati jeMèsáyà, Olùgbàlàaraye?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Romu 10:9-10 & 17...**9. Bí ìwọ bá gbàgbọ́ ní ọkàn rẹ pé, Olúwa ti jí dìde kúrò nínú òkú, tí ó sì jẹ́wọ́ rẹ̀ fún àwọn ẹlòmíràn pé Jésù Kírísítì ní Olúwa rẹ, a ó gbà ọ́ là. 10. Nítorí pé, nípa ìgbàgbọ́ nínú ọkàn ni ènìyàn le gbà ní àlàáfíà pẹ̀lú Ọlọ́run. Bẹ́ẹ̀ ni ẹnu ni a sì fi ń sọ fún àwọn ẹlòmíràn ní ti ìgbàgbọ́ wa. Nípa bẹ́ẹ̀, a sì sọ ìgbàlà wa di ohun tí ó dájú.17...Ǹjẹ́ nípa gbígbọ́ ni ìgbàgbọ́ ti í wá, àti gbígbọ́ nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

---

**Bakara 2:119-120....**119. Dajudaju Awa ni A ran O nise pelu ododo,ni oniro-idunnu ni olukilo...120 Awon Yahudi ati Nasara ko ni le yonu si O ayafi ti o ba tele isin won, sope, imona ti Olohun ni imona...

# 115.

**Se otito ni wipegbigba pe Jésù Kristi je Olùgbàlà ati Olúwa nikan ni ona funeniyan lati ri idariji ẹ̀ṣẹ̀gba ati lati ri iye ainipekun?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 11:25...** Jésù wí fún un pé, "Èmi ni àjíǹde àti ìyè: ẹni tí ó bá gbà mí gbọ́, bí ó tilẹ̀ kú, yóò yè

**Johanu 17:3...**Ìyè àìnípẹ̀kun náà sì ni èyí, kí wọn kí ó lè mọ ìwọ nìkan Ọlọ́run òtítọ́, àti Jésù Kírísítì, ẹni tí ìwọ rán.

---

**Al-i Imran 3:19-20...**Dajudaju esin (kansoso) tin be lodo Olohun ni Islam. Awon ti a fun ni Tira (siwaju) ko si se iyapa-enu, ayafi enyin igba ti amodaju (re) ti wa ba won...20... ti won ba te ara won ba (fun Olorun), nja nigbana nwon tele ona tara, sugbon bi nwon ba yi pada iba ki o mu ise jije de opin ni tire...

# 116.

**Se iribomi se Pataki si onigbagbo laye ode oni?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 28:19-20...19**Nítorí náà, Ẹ lọ, ẹ máa kọ́ orílẹ̀-èdè gbogbo, ẹ máa bamitíísì wọn ní orúkọ Baba àti ti Ọmọ àti ti Ẹ̀mí Mímọ́. 20. Ẹ kọ́ wọn láti máa kíyèsí ohun gbogbo èyí tí mo ti pa láṣẹ fún yín. Nítorí èmi wà pẹ̀lú yín ní ìgbà gbogbo títí tí ó fi dé òpin ayé.

**Maku 16:16...**Ṣùgbọ́n nígbà tí Hẹ́rọ́dù gbọ́ èyí, ó wí pé "Jòhánù tí mo tí bẹ́ lórí ni ó ti jíǹde kúrò nínú òkú

**Ìṣe Àwọn Aposteli 2:38...**Pétérù sì wí fún wọn pé, "Ẹ ronúpìwàdà, kí a sì bamitíisì olúkúkùkù yín ní orúkọ Jésù Kírísítì fún ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ yín. Ẹ̀yin yóò sì gba ẹbun Ẹ̀mí Mímọ́

**Ìṣe Àwọn Aposteli 22:16....**Ǹjẹ́ nísinsìn yìí, kín ni ìwọ ń dúró dè? Dìde, kí a sì bamitíisì rẹ̀, kí ó sì wẹ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù, kí ó sì máa pé orúkọ rẹ̀.'

---

**Kíyèsí:** ko si akosile iribomi Kankan ninuKùránì.

## 117.

**Se awon okunrin onigbagbo ode oni nilo ìdádọ̀dọ́?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìṣe Àwọn Aposteli 15:5-11**...è é ṣe tí ẹ̀yin o fi.... àjàgà bọ àwọn ọmọ-ẹ̀yìn lọ́rùn...
**1 Kọrinti 7:18 & 20**...18. Ǹjẹ́ ọkùnrin kan há ti kọlà nígbà tí a pè é? Kí ó má sì ṣe di aláìkọlà. Ǹjẹ́ ọkùnrin kan ha ti kọlà nígbà tí a pè é? Kí ó ma ṣe kọlà. 20. Ó yẹ kí ẹnìkọ̀ọ̀kan máa ṣe iṣẹ́ tí ó ń ṣe tẹ́lẹ̀, kí Ọlọ́run tó pé é sínú ìgbàgbọ́ nínú Kírísítì
**Galatia 5:2**...Kíyèsí i, èmi Pọ́ọ̀lù ni ó wí fún yín pé, bí a bá kọ yín nílà, Kírísítì kì yóò lérè fún yín ní ohunkóhun.
**Galatia 5:6**...Nítorí nínú Kírísítì Jésù ìkọlà kò jẹ́ ohun kan, tàbí àìkọlà; ṣùgbọ́n ìgbàgbọ́ ti ń ṣiṣẹ́ nípa ìfẹ́.

---

**Nahl 16:123**...Lehinna A ranse si O pe: ki o tele esin Ibrahima...
**Kíyèsí:** ninu ẹ̀sìn Ìsìláàmù, ìdádọ̀dọ́je are esin Ábúráhámùu, atiwa maa n ri wipe o pon dandan funÀwọn Mùsùlùmí. A tun ri eyi ninu Hadith: Bukhari 1252, Fatih al-Bari 6:388; ati Muslim 4:2370.

## 118.

**Se a ria won aklosile ti o pa ni ase fun awon eniyan lati je mimo ati pe se iwa mimo jeỌ̀kan lára ohun tí à ńilo lati de orun rere**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Lefitiku 11:44**...Èmi ni Olúwa Ọlọ́run yín, ẹ ya ara yín sọ́tọ̀ kí ẹ sì jẹ́ mímọ́ torí pé mo jẹ́ mímọ́. Ẹ má ṣe sọ ara yín di àìmọ́ nípaṣẹ̀ ohunkóhun tí ń rìn kákiri lórí ilẹ̀.
**1 Kọrinti 3:16-17**...16 Ṣé ẹ̀yin kò tilẹ̀ mọ̀ pé tẹ́mpìlì Ọlọ́run ni ẹ̀yin jẹ? Pé Ẹ̀mí Ọlọ́run ń gbé inú yín? 17. Bí ẹnikẹ́ni bá ba tẹ́mpìlì Ọlọ́run jẹ́, òun ni Ọlọ́run yóò parun; nítorí pé mímọ́ ni tẹ́mpìlì Ọlọ́run, èyí tí ẹ̀yín jẹ́.
**Heberu 12:14**...Ẹ máa lépa àlàáfíà pẹ̀lú ènìyàn gbogbo, àti ìwà mímọ́, láìsí èyí yìí kò sí ẹni tí yóò rí Olúwa
**2 Peteru 1:15-16**...15 Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹni tí o pè yin ti jẹ mímọ; bẹ́ẹ̀ ni kí ẹ̀yin náà jẹ mímọ́. 16 Le Nítorí a ti kọ ọ pé, "Ẹ jẹ́ mímọ́: nítorí tí Èmi jẹ mímọ!"
**Ìfihàn 22:11**...Àti ẹni tí ń ṣe ọlọ̀dodo, kí ó máa ṣe òdodo nìṣó: Àti ẹni tí ń ṣe mímọ́, kí ó máa ṣe mímọ́ nìṣó

---

**Kíyèsí:** ko si akosile nipa ki eniyan je mimo tabi pe won le di mimo ninuKùránì.

## 119.

**se awon eniyan leyàn láti di omo Ọlọ́run nípasẹ̀ ipinu okan won lai se afi ipa mu?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 1:12...**Ṣùgbọ́n iye àwọn tí ó gbà á, àní àwọn náà tí ó gbà orúkọ rẹ̀ gbọ́, àwọn ni ó fi agbára fún láti di ọmọ Ọlọ́run

**Romu 8:14 & 16...**14. Nítorí pé, iye àwọn tí ẹ̀mí Ọlọ́run bá ń darí ni ọmọ Ọlọ́run. 16. Nítorí ẹ̀mí mímọ́ ń sọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú ọkàn wa, ó sì ń sọ fún wa pé, ní tòótọ́, àwa jẹ́ ọmọ Ọlọ́run.

**Galatia 3:26...**26. Nítorí pé ọmọ Ọlọ́run ni gbogbo yín, nípa ìgbàgbọ́ nínú Kírísítì Jésù.

**Heberu 12:5...**Ẹ̀yin sì ti gbàgbé ọ̀rọ̀ ìyànjú tí ó n ba yin sọ̀rọ̀ bí ọmọ pé, Ọmọ mi, ma ṣe aláìnání ìbáwí Olúwa, kí o má sì ṣe rẹ̀wẹ̀sì nígbà tí a bá ń ti ọwọ́ rẹ̀ ba ọ wí..

---

**Maide 5:18...**Awon Yahudi ati Nasara nwipe: Awa ni omo Olohun ati Ayanfe Re (pelu), wipe: Ese nigbana ti O fi njeyin niya nitori awon ese nyin? Beko, eniyan ni enyin ninu ise ti O da...

## 120.

**Ọlọ́run lo kọ̀ kádàrá gbogbo ohun téèyàn á ṣe láyé tàbí bí ọjọ́ iwájú wa ṣe máa rí? (Kader tabi Kısmet)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Diutaronomi 11:26-27...**26. Ẹ kíyèsí i, mo fi ìbùkún àti ègún lélẹ̀ níwájú u yín lónìí: 27. ìbùkún ni, bí ẹ bá pa òfin Olúwa Ọlọ́run yín, tí mo ń fún un yín lónìí mọ́.

**Diutaronomi 30:19...** Lónìí mo pe ọ̀run àti ayé bí ẹlẹ́rìí sí ọ pé mo ti gbékalẹ̀ síwájú rẹ ìyè àti ikú, ìbùkún àti ègún. Nísinsìnyìí yan ìyè, nítorí kí ìwọ àti àwọn ọmọ rẹ lè gbé

**Joṣua 24:15...**Ṣùgbọ́n bí ẹyin kò bá fẹ́ láti sin Olúwa nígbà náà ẹ yàn fún ara yín ní òní ẹni tí ẹ̀yin yóò sìn bóyá òrìṣà tí àwọn baba ńlá yín sìn ní ìkọjá odò, tàbí òrìṣà àwọn ará Ámórì, ní ilẹ̀ ẹni tí ẹ̀yin ń gbé. Ṣùgbọ́n ní ti èmi àti ilé mi, Olúwa ni àwa yóò máa sìn.”

---

**Tevbe 9:51...**Wipe: nkankan ko le wa ba wa ayafi eyi ti Olohun ti ko sile fun wa...

**Kasas 28:68...**sisa esa ko to si won...

**Ahzab 33:38...**Atipe ase Olohun je ebubu kan ti a ti se sile ti ko leyi...

**Note:** Laarin Àwọn Kristẹni,awon ara Armini so wipe “Bẹ́ẹ̀ko”; sugbon awonara Kalfini so wipe “Bẹ́ẹ̀ni”.

## 121.

**ṣe Ọlọ́run n lo ibá adọ́gba lórí òṣùwọ̀nti o fi I n won ìdájọ́ ise rere tabi ise buburu ti eniyan ba se lati fi mo boya orun rere tabi"ọ̀run àpáàdì`ni won n lo? (Terazi)**

Bibeli **Rara / Bẹ̀ẹ̀ni** Al-Qur'an

**Efesu 2:8-9...**8. Nítorí oore ọ̀fẹ́ ni a fi gbà yín là nípa ìgbàgbọ́: àti èyí yìí kì í ṣe ti láti ọ̀dọ̀ ẹ̀yin fúnra yín: ẹ̀bùn Ọlọ́run ni: 9. Kì í ṣe nípa àwọn iṣẹ́, kí ẹnikẹ́ni má ba à ṣògo.
**Titus 3:4-5...**4. Ṣùgbọ́n nígbà tí inú rere àti ìfẹ́ Ọlọ́run Olùgbàlà wa farahàn, 5. Ó gbà wá là. Kì í ṣe nípa iṣẹ́ tí àwa ṣe nínú òdodo bí kò ṣe nítorí àánú rẹ̀. Ó gbà wá là, nípaṣẹ̀ ìwẹ̀nù àtúnbí àti ìsọdọ̀tun ti Ẹ̀mí Mímọ́

---

**A'raf 7:8-9...8...**enikeni ti osuwon re ba te owuwon, awon wonni ni yio se orire...9. Enikeni ti osuwon ise (rere) re ba fuye, awon wonni ni eniti o pofo emi won...
**Mü'minun 23:102-103...**102. Enikeni ti osuwon ise rere won ba te iwon, awon ni eniti o la. 103. Enikeni ti osuwon (ise rere) won ba fuye, awon ni eniti won pa emi won lofo inu ina Jahannama ni nwon yio gbe gbere.

## 122.

**Lati le fun eniyan lágbára lati wo inu ijoba Ọlọ́run, se o koko pon dandan pe ki a tun eniyan bi nipa ti emi ati lati di atunbi?**

Bibeli **Bẹ̀ẹ̀ni / Rara** Al-Qur'an

**Johanu 1:12-13...** 12. Ṣùgbọ́n iye àwọn tí ó gbà á, àní àwọn náà tí ó gbà orúkọ rẹ̀ gbọ́, àwọn ni ó fi agbára fún láti di ọmọ Ọlọ́run; 13. Àwọn ọmọ tí kì íṣe nípa ẹ̀jẹ̀, tàbí nípa ti ìfẹ́ ara, bẹ́ẹ̀ ni kì í ṣe nípa ìfẹ́ ti ènìyàn, bí kò ṣe láti ọwọ́ Ọlọ́run.
**Johanu 3:3** Jésù dáhùn ó sì wí fún un pé, "Lóòótọ́ lóòótọ́ ni mo wí fún ọ, bí kò ṣe pé a tún ènìyàn bí, òun kò lè rí ìjọba Ọlọ́run."
**2 Kọrinti 5:17...**Nítorí náà bí ẹnìkan bá wà nínú Kírísítì, ó di ẹ̀dá titun: ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsí i, ohun titun ti dé.
**1 Peteru 1:23...** Bí a ti tún yín bí, kì í ṣe láti inú ìdíbàjẹ́ wá, bí kò ṣe èyí ti kì í díbàjẹ́ nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí ń bẹ láàyè tí ó sì dúró.

---

**Note:** The Qur'an does not mention anything about the need for a spiritual rebirth or being "born again".

## 123.

**Ṣe Ọlọ́runse ileritabifúnni ní ẹ̀rí ìdánilójú pé iye ainipekun wa fun awon onigbagbo otito ninu Kristi?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 3:36...**Ẹni tí ó bá gba Ọmọ gbọ́, ó ní ìyè àìnípẹ̀kun: ẹni tí kò bá sì gba Ọmọ gbọ́, kì yóò rí ìyè; nítorí ìbínú Ọlọ́run ń bẹ lórí rẹ̀.”
**Johanu 5:24...**Lóòótọ́, lóòótọ́ni mo wí fún yín, ẹnikẹ́ni tí ó bá gbọ́ọ̀rọ̀mi, tí ó bá sì gba ẹni tí ó rán mi gbọ́, ó ní ìyè tí kò nípẹ̀kun, òun kì yóò sì wá sí ìdájọ́; ṣùgbọ́n ó ti ré ikú kọjá bọ́sí ìyè.

---

**Al-i İmran 3:55 & 113-115...**55. Nigbati Olohun wipe: Iwo Isa! Emi yi o si fi awon ti o ba tele O leke awon ti o se aigbagbo lo titi di ojo ajinde...
**Maide 5:47 & 69....**Awon oni injila...69....Awon oni tira gbagbo ni ododo tin won si beru (Olohun)...

## Iṣẹlẹ̀ọ́jọ́iwájú

## 124.

**Se awon òrò “Wolii” ati “Isotele” ti a maa n lo nigba ti a ba n soro Pataki fun awon eniyan ti won tipase ebun Olorun ni Ogbon Iṣẹlẹ̀ọ́jọ́iwájú? (Nebi)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**1 Samuẹli 9:9...** Tẹ́lẹ̀ní Ísírẹ́lì tí ọkùnrin kan bá lọ béèrè lọ́dọ̀Ọlọ́run, yóò wí pé, “Wá, Jẹ́kí a lọ sí ọ̀dọ̀ wòlíì náà,” nítorí àwọn aláṣọtẹ́lẹ̀ ìsinsìn yìí ni wọ́n ń pè ní wòlíì.
**Ìfihàn 19:10...**Mo sì wólẹ̀ní ẹsẹ̀rẹ̀láti foríbalẹ̀ fún un. Ó sì wí fún mi pé, “Wò ó, má ṣe bẹ́ẹ̀: ìránṣẹ́ẹlẹ́gbẹ́rẹ̀ni èmi, àti ti àwọn arákùnrin rẹ̀ tí wọ́n di ẹ̀rí Jésù mú: foríbalẹ̀fún Ọlọ́run: nítorí pé ẹ̀rí Jésù ni ìsọtẹ́lẹ̀.

---

**A’raf 7:158 & 188....**Nitorina ki e gba Olorun na gbo ati Ojise Re, Annabi ti ko mo ko ti ko mo ta…
**Ahkaf 46:9...**sope: emi ko ni eni akoko ninu awon Ojise, be si ni emi ko ohun ti a o se fun mi ati fun enyin na. Atipe emi ko tele kinikan ayafi ohun ti a ba fi ranse simi, emi ko je kinikan ayafi olukilo ti o han.

## 125.

Nje a ni ekunrere ifikun nipa awon isele ojo iwaju ati ni igbeyin aye? (Eschatology / Gayb Haber)

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 24:3, 14 & 25...3.** Sọ fún wa nígbà wo ni èyí yóò ṣẹlẹ̀? Kí ni yóò jẹ́ àmì ìpadàwá rẹ, àti ti òpin ayé?14. A ó sì wàásù ìyìn rere nípa ìjọba náà yí gbogbo ayé ká, kí gbogbo àwọn orílẹ̀-èdè lè gbọ́ ọ, nígbà náà ni òpin yóò dé ní ìkẹyìn. 25. Wò ó, mo ti kìlọ̀ fún yín tẹ́lẹ̀.

**Ìfihàn 1:1**...Ìfihàn ti Jésù Kírísítì, tí Ọlọ́run fi fún un, láti fi hàn fún àwọn ìranṣẹ́ rẹ̀, ohun tí kò le ṣàìṣẹ ní lọ́ọ́lọ́; ó sì ránṣẹ́, ó sì fi í hàn láti ọwọ́ angẹ́lì rẹ̀ wá fún Jòhánù, ìránṣẹ́ rẹ̀:

---

**En'am 6:50** sope: Emi ko so fun nyin pe pepe oro ti Olohun mbe ni odo mi,be si ni emi ko mo ohun ti o pamo be si ni emi ko ni so fun nyin pee mi je malaika kan. Emi ko tele kinikan ayafi ohun ti a fi ranse simi...

## 126.

**Se awon ese bibeli ti o je mo asotele nipa ijoba satani kan ti o lagbara ti o ma jade ni igbeyin ojo wa? (Aselodi si Kristi / Mehidi)**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Matiu 24:21-25...** 23Nígbà náà, bí ẹnikẹ́ni bá sọ fún yín pé, 'Wo Kírísítì náà,' tàbí pé ó ti farahàn níhìn-ín tàbí lọ́hùn-ún, ẹ má ṣe gbà á gbọ́. 24. Nítorí àwọn èké Kírísítì àti àwọn èké wòlíì yóò dìde.

**Tẹsalonika Keji 2:7-9**...Nítorí agbára ìkọ̀kọ̀ ẹ̀ni ẹ̀ṣẹ̀ ti ń ṣiṣẹ; ṣùgbọ́n ẹni tí ń dènà yóò máa ṣe bẹ̀ẹ̀ títí a ó fi mú-un kúrò ní ọ̀nà. 8. Nígbà náà ni a ó fi ẹni ẹ̀ṣẹ̀ hàn, ẹni tí Jésù Olúwa yóò fi èémí ẹnu rẹ̀ pa, tí yóò sì fi ọlá ìpadàbọ̀ rẹ̀ parun. 9. Wíwá ẹni ẹ̀ṣẹ̀ yóò rí bí iṣẹ́ Sàtánì, gbogbo èyí tí a fihàn gẹ́gẹ́ bí àdàmọ̀dì iṣẹ́-ìyanu, àdàmọ̀dì àmì àti àdàmọ̀dì idán.

**1 Johanu 2:18**...Ẹ̀yin ọmọ mi ọ̀wọ́n, ìgbà ìkẹyìn ni èyí; bí ẹ̀yin sì tí gbọ́ pé Aṣòdìsí-Kírísítì ń bọ̀ wá, àní nísinsin yìí, púpọ̀ Aṣòdì-sí-Kírísítì ló ń bẹ. Nípa èyí ni àwa fí mọ́ pé ìgbà ìkẹ́yìn ni èyí

**Ìfihàn 6:1-2**...1. Èmi sì rí i nígbà tí Ọdọ́-Àgùntàn náà sí ọ̀kàn nínú èdìdì wọ̀nyí, mo sì gbọ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀dá alàáyè mẹ́rin náà ń wí bí sísán àrá pé, "Wá, wò ó!" 2. Mo sì wò ó, kíyèsí i, Ẹṣin funfun kan: ẹni tí ó sì jókòó lórí i rẹ̀ ní ọrùn kan; a sì fi adé kan fún un: ó sì jáde lọ láti ìṣẹ́gun dé ìṣẹ́gun.

---

**Note: Kíyèsí:**a ko menuba bibo aṣòdì-sí-Krist tabi Mehidi ninu Kurani

# 127.

**Se ojo ti a le pe ni "ọjọ́ ìdájọ́" ma a wa nigba ti Ọlọ́run ma ji gbogbo eniyan kuro ninu oku leyo kookan lati woye boya orun rere tabi "ọ̀run àpáàdì" ni won n lo?(Ahiret Günü)**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Heberu 9:27...**Níwọ̀n bí a sì ti fi lélẹ̀ fún gbogbo ènìyàn láti kú lẹ̀ẹ̀kanṣoṣo, ṣùgbọ́n lẹ̀yìn èyí ìdájọ́:
**2 Peter 2:9...**Bí ó bá rí bẹ́ẹ̀, Olúwa mọ bí a tí ń yọ àwọn ẹni ìwà-bí-Ọlọ́run kúrò nínú ìdẹwò àti bí a ti ń pa àwọn aláìṣòótọ́ mo fún ọjọ́ ìdájọ́ nígbà tí wọn yóò tẹ̀síwájú nínú ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ wọn.
**Ìfihàn 20:11-15...** 12 Mo sì rí àwọn òkú, àti èwe àti àgbà, wọn dúró níwájú ìtẹ́; a sì sí àwọn ìwé sílẹ̀; a sì ṣí àwọn ìwé mìíràn kan sílẹ̀ tí í ṣe ìwé ìyè: a sì ṣe ìdájọ́ fún àwọn òkú láti inú ohun tí a ti kọ sínú àwọn ìwé náà, gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ wọn. 15 Bí a bá sì rí ẹnikẹ́ni tí a kò kọ orúkọ rẹ̀ sínú ìwé ìyè, a ó sọ ọ́ sínú adágún iná.

---

**Bakara 2:113...**olohun yio se idajo ni arin won ni ojo ajinde nipa ohun ti won yapa enu si...
**Al-i İmran 3:185...**gbogbo emi kokan ni yio je ohun ti yio to iku wo.A o san esan yin fun nyin lekun ni ojo ajinde.

# 128.

**Se gbogbo eniyan ni o maa lo si "ọ̀run àpáàdì" lati lo jiya fun igba die?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 5:24...**Lóòótọ́, lóòótọ́ ni mo wí fún yín, wákàtí náà ń bọ̀, ó sì dé tán nísinsìn yìí, nígbà tí àwọn òkú yóò gbọ́ ohùn ọmọ Ọlọ́run: àwọn tí ó bá gbọ́ yóò sì yè.
**Romu 8:1...**Nítorí náà, kò sí ìdálẹ́bi nísinsinyìí fún àwọn tí ó wà nínú Kírísitì.
**Tẹsalonika Kinni 5:9...**Nítorí pé, Ọlọ́run kò yàn wa láti da ìbínú rẹ̀ gbígbóná sí orí wa, ṣùgbọ́n ó yàn láti gbà wá là nípasẹ̀ Olúwa wa, Jésù Kírísítì.

---

**Al-i İmran 3:185...**eniti a ba mu jinna si ina ti a si je ki owo alijanna...
**Meryem 19:70-72...**lehin na dajudaju awa lo ni mimo julo nipa awon eniti nwon ni eto si ijo na (Jahannama). 71. Ko si enikan ninu nyin ayafi ki o wo, o je oranyan ti Oluwa re ti se idajo re ti ko ni iye.72. Lehin na A o gbala awon eniti won paiya, A o si awon alabosi sile ninu re ni ikunle.

## 129.

**Ti eniyan ba lo si "ọ̀run àpáàdì, se o se e se ki o jade nibe ki o si lo si orun rere?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 25:41 & 46...**41. Nígbà náà ni yóò sọ fún àwọn tí ọwọ́ òsì pé, 'Ẹ kúrò lọ́dọ̀ mi, ẹ̀yin ẹni ègún, sínú iná àìnípẹ̀kun tí a ti tọ́jú fún èṣù àti àwọn áńgẹ́lì rẹ̀.46. Nígbà náà wọn yóò sì kọjá lọ sínú ìyà àìnípẹ̀kun, ṣùgbọ́n àwọn olódodo yóò lọ sí ìyè àìnípẹ̀kun.

**Luku 16:25-26...**25 "Ṣùgbọ́n Ábúráhámù wí pé, 'Ọmọ, rántí pé, nígbà ayé rẹ, ìwọ ti gba ohun rere tìrẹ, àti Lásárù ohun búburú: ṣùgbọ́n nísinsin yìí ara rọ̀ ọ́, ìwọ sì ń joró. 26Àti pẹ̀lú gbogbo èyí, a gbé ọ̀gbun ńlá kan sí agbede-méjì àwa àti ẹ̀yin, kí àwọn tí ń fẹ́ má baa le rékọjá láti ìhín lọ sọ́dọ̀ yín, kí ẹnikẹ́ni má sì le ti ọ̀hún rékọjá tọ̀ wá wá.

---

**En'am 6:128...**On o wipe: inu ni ibugbe nyin, enyin o se gbre sinu re ayafi bi Olohun ba ti fe…

**Hud 11:106-107...**Nigbana ki e rio awon tin won nse ori buburu, nwon o si ma be ninu ina; kikun riri wa fun nwon ninu re ati kike irora.

## 130.

**se ago ara ti a gbewo nigba ajinde je eyi ti o ni ara, egun ati eje?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 15:35-50...**Báwo ni àwọn òkú yóò ṣe jíǹde? Irú ara wó ni wọn ó padà sí? 44. A gbìn ín ni ara ti ọkàn, a sì jí i dìde ni ara ti ẹ̀mí. Bí ara tí ọkàn bá ń bẹ, ara ẹ̀mí náà sì ń bẹ. 50...ara àti ẹ̀jẹ̀ kò lè jogún Ìjọba Ọlọ́run

---

**Bakara 2:25 & 259...**25...awon enikeji ninu awon oinrin ti o mo sim be fun won ninu re ,nwon yio si ma gbe ibe lailai. 259. Ba wo ni A ti se to won jo po ti A si fie ran bo won.

**Zuhruf 43:70...**Ewo ogba idera na, enyin ati awon aya yin ki e si je eniti yio mu dunnu.

**Vakia 56:35-38...**Dajudaju Awa ni a tun won da ni eda tuntun. 36. Awa se won ni wundia. 37. Ti nwon yio feran oko won ti nwon yio si se jegbe kan na. 38. Fun awon ero owo otun.

**Nebe 78:33...**Ati awon odo (obinrin) tin won ko ju ara won lo.

# 131.

**Se igbeyawo ati ibalopo laarin okunrin ati obinrin ma wa ni orun?( (Houris)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 22:28-33...28.** Nítorí tí ó ti ṣe ìyàwó àwọn arákùnrin méjèèje, ìyàwó ta ni yóò jẹ́ ní àjíǹde òkú?” 29...Jésù dá wọn lóhùn pé, “Àìmọ̀kan yín ni ó fa irú ìbéèrè báyìí. Nítorí ẹ̀yin kò mọ ìwé Mímọ́ àti agbára Ọlọ́run. 30. Nítorí ní àjíǹde kò ní sí ìgbéyàwó, a kò sì ní fi í fún ni ní ìyàwó. Gbogbo ènìyàn yóò sì dàbí àwọn áńgẹ́lì ní ọ̀run.

---

**Tur 52:20...**Ni irogboku lori ite ti a to, A o se igbe iyawo eleyinju ege fun nwon.

**Rahman 55:55-56, 70-72...55....**Nitorina ewo ni ninu idera ni ti Oluwa enyin mejeji ti e n pe ni iro? 56. Awon (obinrin) ti o fi ara won si owo mbe ninu nwon, ti eniyan kan ko fowo kan won ri siwaju (awon oko nwon) beni anjonu ko fofokan won. 70. Awon obinrin oniwa rer ti o dara mbe ninu awon ogba na. 72. Awon eleyinju ege ti a fi  pamo sinu ileso.

# 132.

**Se gbogbo Ṣọ́ọ̀ṣì pátápátá ni a le pe ni “Iyawo Kristi”?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Efesu 5:23, 25, & 32...**23. Kírísítì tí i ṣe orí ìjọ..25. Ẹ̀yín ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́ bí Kírísítì tí fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fí ara rẹ̀ fún-un. 32.Àṣírí ńlá ní èyí: ṣùgbọ́n èmí ń sọ nípá ti Kírísítì àti tí ìjọ

**Ìfihàn 19:7...**Ẹ jẹ́ kí a yọ̀, kí inú wa kí ó sì dùn gidigidi, kí a sì fi ògo fún un. Nítorí pé ìgbéyàwó Ọ̀dọ́-Àgùntàn dé, aya rẹ̀ sì ti múra tán.

**Ìfihàn 21:9...**Ọ̀kan nínú àwọn áńgẹ́lì méje, tí wọ́n ni ìgò méje, tí ó kún fún ìyọnu méje ìkẹyìn sì wá, ó sì ba mi sọ̀rọ̀ wí pé, “Wá níhìnín, èmi ó fi ìyàwó, aya Ọ̀dọ́-Àgùntàn hàn... **-**

**Ìfihàn 22:17...**Ẹ̀mí àti ìyàwó wí pé, “Máa bọ!” Àti ẹni tí ó ń gbọ́ kí ó wí pé, “Máa bọ̀!” Àti ẹni tí òùngbẹ ń gbẹ kí ó wá, àti ẹni tí o bá sì fẹ́, kí ó gba omi ìyè náà lọ́fẹ̀ẹ́.

---

**Kíyèsí:**Kùránì kan menuba Ṣọ́ọ̀ṣì lkan soso ko si akosile fun “Iyawo Kristi”: Hajj 22:40.

# Awon ohun ti a n ri

## 133.

**ṣe Ọlọ́run fẹ́ki awon onigbagbo maa a gbe ni abe ofin lode oni? (Shariah)**

**Bibeli Rara / Bẹẹni Al-Qur'an**

**Romu 6:14**...Nítorí ẹ̀ṣẹ̀kì yóò tún ní ipá lórí yín mọ́, nítorí ẹ̀yin kò sí lábẹ́ ìdè òfin, bí kò ṣe lábẹ́oore-ọ̀fẹ́

**Romu 10:4**...Títí ìsinsin yìí, wọn kò ì tíì mọ̀pé, Kírísítì kú láti pèsè ohun gbogbo tí wọ́n ń fi àníyàn wá kiri nípa òfin fún àwọn tí ó gbẹ́kẹ̀lé e, ó ti fi òpin sí gbogbo rẹ̀.

**Galatia 3:11 & 25...11.** Nítorí ó dánilójú pé, a kò dá ẹnìkẹ́ni láre níwájú Ọlọ́run nípa iṣẹ́òfin: nítorí pé, olóododo yóò yè nípa ìgbàgbọ́. 25. Ṣùgbọ́n lẹ́yìn ìgbà tí ìgbàgbọ́ti dé, àwa kò sí lábẹ́olùkọ́ni mọ́.

---

**Maide 5:48**...A ti se ofin ati liana esin fun...

**Jathiyah 45:18**.....Lehinna A fi o si oju ona nipa oran na, nitorina tele e, atipe o ki gbodo tele ife inu awon ti ko ni mimo.

## 134.

**Se eewo ni fun onigbagbo lati mu wáìnì?**

**Bibeli Rara / Bẹẹni Al-Qur'an**

**Luku 7:34-35**...Ọmọ ènìyàn dé, ó ń jẹ, ó sì ń mu; ẹ̀yin sì wí pé, 'Wò ó, Ọ̀jẹun, àti ọmùtí, ọrẹ́àwọn agbowó òde àti àwọn "ẹlẹ́ṣẹ̀!"' 35. Ṣùgbọ́n àwọn ọmọ rẹ̀gbogbo dá a nipa ọgbọ́n tí ó lò.

**Johanu 2:1-11**...Won ko ni waini mo...Jesu...e pon omi kun ikoko wonyi...ti a so di waini.

**1 Timoti 5:23**...Ma ṣe máa mu omi nìkan, ṣùgbọ́n máa lo wáìnì díẹ̀nítorí inú rẹ, àti nítorí àìlera ìgbàkúùgbà.

---

**Bakara 2:219**...nwon o bi o l'ere nipa oti ati tete; wipe:ese nla mbe ninu mejeji...

**Maide 5:90-91**...Enyin onigbagbo ododo, dajudaju oti ati tete tita ati orisa bibo ati fifi ofa pin nkan, egbin ni, o n be ninu ise esu, nitorna e jina si, ki e le se orire. 91.e ki yio ha siwo?

# 135.

Se eewo ni fun onigbagbo lati máa a jẹ ẹran ẹlẹ́dẹ̀?

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìṣe Àwọn Aposteli 10:13-15...**13. Ohùn kan si fọ̀sí i pe, "Dìde, Pétérù; máa pa kí o sì má a jẹ." 14. Ṣùgbọn Pétérù dáhùn pé, "Àgbẹdọ̀, Olúwa; nítorí èmi kò jẹ ohun èèwọ̀ àti aláìmọ́ kan rí." 15. Ohùn kan sì tún fọ̀sí i lẹẹ́méjì pé, "Ohun tí Ọlọ́run bá ti wẹ̀nù, ìwọ má ṣe pè é léèwọ̀mọ́."

**1 Kọrinti 10:25...**Jẹ ẹrankẹ́ran tí wọ́n bá ń tà lọ́jà. Má ṣe gbìyànjú láti wádìí lọ́wọ́ ẹni tí ń tà á nítorí ẹ̀rí ọkàn

**Kolose 2:16...**Nítorí náà ẹ má ṣe jẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣe ìdájọ́ yín ní ti jíjẹ, tàbí ní ti mímu, tàbí ní ti ọjọ àṣẹ, tàbí oṣù titun, àti ọjọ́ ìsinmi

---

**Maide 5:3...**A se ni ewo fun nyin eran ti o ku fun rare ati eje (didi) ati eran elede...

**En'am 6:145...**sope: ewo fun jije fun eniti yio je ...o je oku- nbete abi eje ti nda jade abi eran elede..nitoripe dajudaju o je egbin...

# 136.

**ṣe Ọlọ́run n woye wipe o ye ki awon onigbagbo ode oni ma a gba awe?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Joẹli 2:12...** Njẹ́ nítorí náà nísínsin yìí," ni Olúwa wí...

**Matiu 6:17-18...** .17.Ṣùgbọ́n nígbà tí ìwọ bá gbààwẹ̀, bu òróró sí orí rẹ, kí ó sì tún ojú rẹ ṣe dáradárá 18. Kí ó má ṣe hàn sí ènìyàn pé ìwọ ń gbààwẹ̀, bí kò ṣe sìí Baba rẹ, ẹni tí ìwọ kò rí, àti pé, Baba rẹ tí ó rí ohun tí o ṣe ni ìkọ̀kọ̀, yóò san án fún ọ. Títo Ìṣúra Jọ Sí Ọ̀run

**Maku 2:20...**Ṣùgbọ́n láìpẹ́ ọjọ́, a ó gba ọkọ ìyàwọ kúrò lọ́dọ̀ wọn. Nígbà náà wọn yóò gbààwẹ̀ ni ọjọ́ wọ̀nyí.

**1 Kọrinti 7:5...**Nítorí náà, ẹ má ṣe fi àwọn ẹ̀tọ́ tọkọtaya wọ̀nyí dun ara yín, bí kò ṣe nípa ìfìmọ̀ṣọ̀kan, kí ẹ̀yin lè fi ara yín gún ààwẹ̀ àti àdúrà,

---

**Bakara 2:183 & 185...**Enyin tie gbagbo, A se awe ni oranyan leyin lori gegebi A ti se ni oranyan le awon ti o saju nyin lori...Osu Ramadhani eyiti A so Al-kurani kale ninu re...enikeni ti osu nab a se oju re ninu nyin, nje ki o gba awe...

**Ahzab 33:35...**Dajudaju awon ti o ju owo-juse sile fun Olohun ni okunrin ati ni obinrin..awon tin gbawe ni okunrin ati ni obinrin Olohun ti pa lese de nwon aforiji ati esan ti o tobi.

# 137.

**Ṣe Ọlọ́run fe ki a maa se awe ati adura ni gbagede nibi ti awon eniyan to ku ma a ri wa?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 6:5-8....**6. Ṣùgbọ́n nígbà tí ìwọ bá ń gbàdúrà, wọ inú iyàrá rẹ lọ, sé ilẹ̀kùn mọ́ara rẹ, gbàdúrà sí Baba rẹ ẹni tí ìwọ kò rí. Nígbà náà ni Baba rẹ tí ó mọ gbogbo ohun ìkọ̀kọ̀rẹ, yóò san án fún ọ.

**Matiu 6:16-18...**16. "Nígbà tí ẹ̀yin bá gbààwẹ̀...
18. Kí ó má ṣe hàn sí èniyàn pé ìwọ ń gbààwẹ̀, bí kò ṣe sìí Baba rẹ, ẹni tí ìwọ kò rí, àti pé, Baba rẹ tí ó rí ohun tí o ṣe ni ìkọ̀kọ̀....

---

**Nisa 4:103...**Nigbati e ba pari irun, nigbana e ma ranti olohun ni iduro ati ni ijoko ati ni ifegbelele nyin...

**Jumah 62:9...**Enyin olugbagbo ododo, nigbati nwon ba pe irun ni ojo Jum'ah(akojo), e yara lo sibi iranti Olohun, efi rira-tita sile, eyi ni o dara fun nyin ti o ba je pe e mo o.

# 138.

**Ṣe Ọlọ́run fẹ́ki awon eniyan ma a gba awe ni osan ki won ma a se faaji lorun leekan lodoodun (Ramadan)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Aisaya 58:3...'**Èéṣe tí àwa fi ń gbààwẹ̀,' ni wọ́n wí, 'tí ìwọ kò sì tí ì rí? Èéṣe tí àwa fi rẹra wa sílẹ̀, tí ìwọ kò sì tí ì ṣe àkíyèsí?' "Ṣíbẹ̀ṣíbẹ̀ní ọjọ́ ààwẹ̀yín, ẹ̀yin ń ṣe bí ó ti wù yín ẹ sì ń pọ́n àwọn òṣìṣẹ́yín gbogbo lójú.

**Matiu 6:16-18...**16. "Nígbà tí ẹ̀yin bá gbààwẹ̀...
18. Kí ó má ṣe hàn sí èniyàn pé ìwọ ń gbààwẹ̀, bí kò ṣe sìí Baba rẹ, ẹni tí ìwọ kò rí, àti pé, Baba rẹ tí ó rí ohun tí o ṣe ni ìkọ̀kọ̀....

---

**Bakara 2:183-185...**183. Enyin ti e gbagbo A se awe ni oranyan leyin lori gegebi A ti se ni oranyan le awon ti o saju nyin lori...185. Osu Ramadhana... enikeni ti osu nab a se oju re ninu nyin, nje ki o gba awe ninu re; eniti o ban se aisan tabi ti o m be lori irin ajo (yio sana we na pada ninu) onka ojo miran. Olohun nfe irorun fun nyin kosi fe inira ninu nyin, ki e si se asepe onka na...

## 139.

**Ṣe Ọlọ́run nreti ki awon onigbagbo ma a san idamewa ati ki won ma a se saara? (Zekat)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Malaki 3:8-10...8.**"Ènìyàn yóò ha ja Ọlọ́run ni olè bí? Ṣíbẹ̀ ẹ̀yin ti jà mí ní olè. "Ṣùgbọ́n ẹ̀yin béèrè pé, 'Báwo ni àwa ṣe jà ọ́ ní olè?' "Nípa ìdámẹ́wàá àti ọrẹ.

**Matiu 6:3...**Ṣùgbọ́n bí ìwọ bá ń́fi fún aláìní, má ṣe jẹ́ kí ọwọ́ òsì rẹ mọ ohun tí ọwọ́ ọ̀tún rẹ ń ṣe,

**Matiu 19:21-23...**21. lọ ta ohun gbogbo tí ìwọ ní, kí o sì fi owó rẹ̀ tọrẹ fún àwọn aláìní. Ìwọ yóò ní ọrọ̀ ńlá ní ọ̀run.

**Luku 11:41...**Kí ẹ̀yin kúkú má a ṣe ìtọrẹ àánú nínú ohun tí ẹ̀yin ní, sì kíyèsii, ohun gbogbo ni ó di mímọ́ fún yín.

---

**Bakara 2:177...**sugbon ifokansi...atipe o fi owo tore...

**Tevbe 9:103-104...103.** gba itore anu ninu oro won...104...Olohun On ni Olugba ironupiwada. Alaanu.

**Mu'minun 23:1 & 4...**1.Papa awon onigbagbo ododo ti jere (la). 4. Ati awon eniti nwon nyan saka.

## 140.

**Ṣe Ọlọ́run fẹ́ lạti mafi eti si ààtò àdúrà ti a n so léraléra lẹ̀ẹ̀marùn-ún nigba kanaa lojojumo? (Namaz)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 6:7...**Ṣùgbọ́n nígbà ti ẹ̀yin bá ń gbàdúrà, ẹ má ṣe àtúnwí asán bí àwọn aláìkọlà, nítorí wọn rò pé a ó titorí ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ gbọ́ tiwọn.

**Johanu 4:24...**Ẹ̀mí ni Ọlọ́run: àwọn ẹni tí ń sìn ín kò lè ṣe aláìsìn ín ní ẹ̀mí àti ní òtítọ́."

---

**Bakara 2:45...**ewa iranlowo pelu suru ati irun kiki, dajudaju o je nkan ti o wuwo, ayafi fun awon ti o paiya Olohun.

**Hud 11:114...**atipe ki o gbe irun duro ni igun mejeji osan ati n i ibere oru. Dajudaju awon ise rere ma npa ise buburu re ni. Eyi je iranti fun awon oluranti.

**İsra 17:78...**gbe irun duro ni (igba) iseri wale orun titi di (igba) okunkunoru atipe kehu kike (inu irun) ti owuro kutukutu, dajudaju kewu kike (inu irun) ti owuro kutu je ohun ti a jeri (re)

## 141.

**Se Ọlọ́run foju si wipe ki awon onigbagbo ma a rírin ìrìn àjò ìsìn lọ sáwọn ibi mímọ́ ni eekan nigba aye won? (Hajj)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 24:24-26...**26. "Nítorí náà, bí ẹnìkan bá sọ fún yín pé, 'Olùgbàlà ti dé,' àti pé, 'Ó wà ní ihà,' ẹ má ṣe wàhálà láti lọ wò ó, tàbí tí wọ́n bá ní ó ń fara pamọ́ sí iyàrá, ẹ má ṣe gbà wọn gbọ́.
**Johanu 4:19-24...21.**Jésù wí fún un pé, "Gbà mí gbọ́, obìnrin yìí, àkókò náà ń bọ̀, nígbà tí kì yóò se lórí òke yìí tàbí ní Jérúsálẹ́mù ni ẹ̀yin ó máa sin Baba. 24. Ẹ̀mí ni Ọlọ́run: àwọn ẹni tí ń sìn ín kò lè ṣe aláìsìn ín ní ẹ̀mí àti ní òtítọ́."

---

**Bakara 2:196...**Ki e si se asepe(ise) Hajj ati Umura fun Olohun...
**Al-i İmran 3:97...**irin ajo si Ile na nitori ti Olohun je iwo fun gbogbo enia enikeni ti o ba ni agabra irin-ajo lo si ibe...

## 142.

**Se Ọlọ́run si fẹ́pe ki awon eniyan oode oni ma a fi ẹranko rubo leekan lodun (Kurban)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Orin Dafidi 51:16-17...**16. Nítorí ìwọ kò ní inú dídùn sí ẹbọ, tí èmi kò bá mú wá; Ìwọ kò ní inú dídùn sí ọrẹ-ẹbọ sísun 17. Ẹbọ Ọlọ́run ni ìròbínújẹ́ ọkan ìròbìnújẹ́ àti ìrora àyà.
**Heberu 9:11-12 & 25-28...**11.Ṣùgbọ́n nígbà tí Kírísítì...12 nípa ẹ̀jẹ̀ òun tìkararẹ̀, o wọ ibi mímọ́ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo, lẹ́yìn tí ó ti rí ìdáǹdè àìnípẹ̀kun gbà fún wa. 25. Kì í si i ṣe pé kí ó lè máa fi ara rẹ̀ rúbọ nígbàkúgbà, 26...Ṣùgbọ́n nísinsin yìí ni ó fi ara hàn lẹ́ẹ̀kanṣoṣo lópìn ayé láti mi ẹ̀ṣẹ̀ kúrò nípa ẹbọ ara rẹ̀. 28...Bẹ́ẹ̀ni Kírísítì pẹ̀lú lẹ́yìn tí a ti fi rúbọ lẹ̀ẹ̀kanṣoṣo láti ru ẹ̀ṣẹ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀...

---

**Bakara 2:196...**Sugbon enikeni ninu nyin ti o ba saisan tabi ti ori ndun u, ki o se irapada nipa (gbigba) awe tabi sara tabi eran pipa...
**Hajj 22:28 & 34...**28 ma pe oruko Olohun lori awon nkan ti o pa lese fun nwon ninu eran-osin; nitorina e je ninu won ki e si fun eniti ara nni ti o je talika je. 34. ... Awa se oju ona esin fun olukuluku iran...

# 143.

**Ti Musulumi ba ni ìbéèrè nipa nnkan ninu Bíbélì Ǹjẹ o tona fun lati beere lowo Kristieni tabi ara Juu nipa re?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**2 Peteru 3:15...**Kí ẹ sì máa kà á sí pé, sùúrù Olúwa wa ìgbàlà ni; bí Pọọlù pẹlú arákùnrin wa olùfẹ́, ti kọwé sí yín gẹgẹ́ bí ọgbọ́n tí a fi fún un.

---

**Yunus 10:94...**Ti ire ba wa ninu iyemeji nipa ohun ti Awa so kale fun o, nigbana bi awon ti nwon ti nke tira siwaju re lere. Dajudaju ododo ti de wa ba o lati odo Oluwa re, nitorina ma se wa ninu osiyemeji.

**Nahl 16:43...**Awa ko ran (enikan) nise siwaju re bikose awon okunrin ti A ranse si, nitorina ki e bi awon oniranti lere bi enyin ko ba mo.

# 144.

**Ti eniyan ba woye pe nnkankan ninu okan ninu awon Ìwé mímọ́ yii kù síbì kan, se ki onigbagbo yera fun sise ibeere otito ti o ba je pe ko ni feran idahun re?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìṣe Àwọn Aposteli 17:11...**Àwọn wọ̀nyí sì ní ìyìn ju àwọn tí Tẹsalóníkà lọ, ní tí pé wọn fi tọkàntọkàn gbà ọ̀rọ̀ náà. Wọ́n sì ń wá inú ìwé-mímọ̀ lójoojúmọ́ bí ǹkan wọ̀nyí bá rí bẹ́ẹ̀.

**1 Johanu 4:1...**Olùfẹ́, ẹ má ṣe gba gbogbo ẹ̀mí gbọ́, ṣùgbọ́n ẹ dán àwọn ẹ̀mí wò bí wọn ba ń ṣe tí Ọlọ́run: nítorí àwọn wòlíì èké púpọ̀ tí jáde lọ sínú ayé.

---

**Bakara 2:108...**Abi enyin fe lati ma bere oro lowo Ojise nyin ni gegebi nwon ti bere oro lowo Musa nisiwaju, eniti o ba se pasiparo aigbagbo dipo igbagbo, nitorina dajudaju o ti sina oju ona tara.

**Maide 5:101...**Enyin ti e gbagbo ni ododo e ma se bere nipa awon nkan, ti a ba fi won han yin tan ti yio je ipalara fun yin; ti enyin ba n bere nipa won nigba ti an so Al-kurani kale a ba se afihan won fun nyin. 102. Dajudaju awon eniyan kan ti bere nipa won siwaju nyin, leyin na nwon di alaigba nwon gbo.

**Enbiya 21:7..** Awa ko ran enikan nise siwaju re ayafi ko je awon okunrin kan ti A nranse si won; nitorina e bi awon olusiti lere bi enyin ko ba mo.

## 145.

**Yato ṣi Ìṣípayá Àtọ̀runwá, se awon oro siso ti àtọwọ́dọ́wọ́ ati ìtumọ̀ eniyan ye ni eyi ti a le gbokan lẹ́ ti a si nilo lati fi ni oye kikun nipa Ìwé mímọ́ (Hadith)**

Bibeli **Rara / Bẹ̣ẹni** Al-Qur'an

**Jeremaya 17:5...**Báyìí ni Olúwa wí: "Ègbé ni fún àwọn tí ó fi ìgbẹ́kẹ̀lé wọn sínú ènìyàn, tí ó fi agbára rẹ̀ sínú ẹran ara, àti tí ọkàn rẹ̀ kò sí lọ́dọ̀ Olúwa

**Romu 3:4...**Kí a má rí i: kí Ọlọ́run jẹ́ olóòtọ́, àti olúkúlùkù ènìyàn jẹ́ èké; gẹ́gẹ́ bí a ti kọ ọ́ pé:"Kí a lè dá ọ láre nínú ọ̀rọ̀ rẹ, ṣùgbọ́n kí ìwọ lè borí nígbà tí ìwọ bá wá sí ìdájọ́."

---

**Nejm 52:33...**Abi won yio ma sope: o da a so funrare. Betieko, nwon ko gbagbo ni.

**Kíyèsí:** Laarin ẹ̀sìn Ìsìláàmù Ọ̀pọ̀ àwọn akojopo àkọ̀tun titun ti a fi okan te ti a si maa n saaba lo ati frequently used collecttabis of the Hadith Ibn Ishaq wà lára re (d. 768); EbuDavud (d. 775); Ibn Hisham (d. 833); Muhammed al-Bukhari (d. 870); Sahih Muslim (d.875); İbn Maje (d. 886); al-Tirmidhi (d. 892); EbuJaferTaberi (d. 923); ko si eyikeyi ninu awon eniyan wonyii ti o wa laaye nigba aye Hz. Muhammed (570-632). Ninu akojopo àkọ̀tun titun ẹgbẹ̀ta egberun-un akojopo àkọ̀tun titun Bukhari ti a ko po laarin odun merindinlogun, egberun meje le ni metadinirinwo nikan ni o toju pe ko ni amulu mala. O ko eyi ti o ju ida mọ́kàndínlọ́gọ́rùn-ún eyi ti o gba lowo Àwọn Mùsùlùm nu gege bi pe won ki I se ooto ati pe won sàsọdùn ninu won ni.

## 146.

**Se Ọlọ́run ro si awon onigbagbo pe ki won ma a se ijumo josin tara okan ki won sim aa se ise ajihinrere lati tan igbagbo won kale lode oni?**

Bibeli **Bẹ̣ẹni / Bẹ̣ẹni** Al-Qur'an

**Matiu 28:19...**Nítorí náà, Ẹ lọ, ẹ máa kọ́ orílẹ̀-èdè gbogbo, ẹ máa bamitíísì wọn ní orúkọ Baba àti ti Ọmọ àti ti Ẹ̀mí Mímọ́.

**2 Kọrinti 5:20...**Nítorí náà àwa ni ikọ̀ fún Kírísítì, bí ẹni pé Ọlọ́run ń ti ọ̀dọ̀ wa ṣìpẹ̀ fún yín: àwa ń bẹ̀ yín nípò Kírísítì, "Ẹ bá Ọlọ́run làjà,"

**2 Peteru 3:15...**Kí ẹ sì máa kà á sí pé, sùúrù Olúwa wa ìgbàlà ni; bí Pọ́ọ̀lù pẹ̀lú arákùnrin wa olùfẹ́, ti kọ̀wé sí yín gẹ́gẹ́ bí ọgbọ́n tí a fi fún un.

---

**Tevbe 9:33...**On ni eniti o ran Ojise Re pelu ona mimo ati esin ododo lati fori gbogbo esin pata, bi awon osebo ko tile fe.

**Nahl 16:125...**Pe ipe si oju ona Oluwa re pelu ogbon ati wasi ti o dara, bawon jiyan pelu eyiti o dara (ni oro).

## 147.

**Ṣe Ọlọ́run fẹ́ ki awon onigbagbo yapa si oríṣiríṣi ẹ̀ya ìsìn, onírúurú ẹlẹ́sìn ati onírúurú ẹ̀ya ẹ̀sìn?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 1:10-13...** 10. Mo bẹ̀ yín ẹ̀yin ara, ní orúkọ Olúwa wa Jésù Kírísítì, pé kí gbogbo yín fohùnsọ̀kan kí ó máa ṣe sí ìyàpá láàrin yín, àtipé kí a lè ṣe yín pé ní inú àti ìmọ̀kan náà.

**1 Kọrinti 3:3-4...3.**Nítorí ẹ̀yin jẹ́ ti ara síbẹ̀. Nítorí, níwọ̀n bí owú jíjẹ àti ìjà sì wà láàrin ara yín, ẹ̀yin kò ha ṣe ti ayé bí? Ẹ̀yin kò ha ṣe bí ènìyàn lásán bí? 4. Ǹjẹ́ ẹ̀yin kì í ṣe ènìyàn lásán bí? Níwọ̀n ìgbà tí ẹ ba ń sọ pé, "Èmi ń tẹ̀lé Pọ́ọ̀lù," àti ti ẹlòmíràn tún wí pé, "Èmi ń tẹ̀lé Àpólò."

---

**Al-i İmran 3:103...**Gbogbo yin e di okun Olohun mu ki e ma se pinya...

**En'am 6:159...**Dajudaju awon tin won npin esin ti nwon si je ijo kelekele, nwon ko ni nkankan pelu won, bi oro won yio ti je mbe lodo Olohun, lehinna yio fun nwon niro ohun ti won nse.

## 148.

**Nje awon ese ti o gba awon eniyan ni iyanju pe ki won maa dunu ki won si ma yo ninu igba aye won ni ile alaye wa ninu Ìwé mímọ́??**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Orin Dafidi 5:11....**Ṣùgbọ́n jẹ́ kí gbogbo àwọn tí ó sádi ọ́ kí ó yọ̀; jẹ kí wọn máa kọrin fún ayọ̀ tìtí. Tan ààbò Rẹ sórí wọn, àti àwọn tí ó fẹ́ràn orúkọ Rẹ yóò máa yọ̀ nínú Rẹ.

**Filipi 4:4...**Ẹ máa yọ̀ nínú Olúwa nígbà gbogbo: mo sì tún wí pé. Ẹ máa yọ̀

---

**Zuhruf 43:70...**Ewo ogab idera na, enyin ati awon aya nyin ki e si je eni ti yio ma dunnu.

**İnsan 76:11....**Nitorina Olohun yio so won nibi buburu ojo na yio si fin won se pekipeki idera ati idunnu.

**Kíyèsí:** awon ese inu Kùránì ti o soro nipa ayo ati idunu n toka si aye ti o wa leyin eyi ni.

## 149.

**Nje a ria won apeere ibi ti Ọlọ́run ti se ìmúniláradá pátápátá nípa tara fun awon eniyan ninu Ìwé mímọ?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Ẹkisodu 15:26...**nítorí èmi ni Olúwa ti ó mú ọ lára da.
**Orin Dafidi 103:2-3...**Yin Olúwa, ìwọ ọkàn mi, kí o má ṣe gbàgbé gbogbo oore Rẹ̀. 3.Ẹni tí ó dárí gbogbo ẹṣẹ Rẹ̀ jìn ọ́ tí
ó sì wo gbogbo àrùn Rẹ̀ sà.
**Matiu 4:23...**Jésù sì rin káàkiri gbogbo Gálílì, ó ń kọ́ni ní sínágọ́gù, ó ń wàásù ìyìn rere ti ìjọba ọ̀run. ó sì ń ṣe ìwòsàn àrùn gbogbo àti àìsàn láàrin gbogbo ènìyàn.
**Ìṣe Àwọn Aposteli 5:15-16....** 15.Tó bẹẹ̀ tí wọn ń gbé àwọn abirùn jáde sí òpópónà... a sì mu olúkúlùkù wọn ní ara dá.
**1 Kọrinti 12:28 & 30...** 28.Àti nínú ìjọ, Ọlọ́run ti yan àwọn àpósítélì àkọ́kọ́... lẹ́yìn náà, àwọn tí ó ní òsìṣẹ́ iṣẹ́ ìyanu, lẹ́yin náà àwọn tí ó ní ẹbùn ìmuláradá… 30. Ṣé gbogbo ènìyàn ló lè wonisàn bí? Rárá.

---

**Kíyèsí:** ona merindinlogbon ni a se akosile ibi ti Jésù nikan ti se ìmúniláradá pátápátá nípa tara fun awon eniyan ninu majemu titun, Sugbon ko si irufe akosile yii ninu Kùránì nigba aye Hz. Muhammed

## 150.

**Se awon ese ti o nipa pe ki a ma fi orin kíko, ilu ati ijo nigba ti a baa n josin fun Ọlọ́run wa ninu bibeli?**

Bibeli **Bẹẹni / Rara** Al-Qur'an

**Diutaronomi 31:19...**Ní báyìí kọ ọ́ kalẹ̀ fúnra à rẹ orin yìí kí o sì kọ ọ́ sí Ísírẹ́lì kí o sì jẹ́ kí wọn kọ ọ́ kí ó lè jẹ́ ẹ̀rí ì mi sí wọn.
**Orin Dafidi 100:1-2...**Ẹ hó ìhó ayọ̀ sí Olúwa, gbogbo ayé. 2. Ẹ fi ayọ̀ sin Olúwa: Ẹ wá ṣíwájú Rẹ̀ pẹ̀lú orin dídùn
**Efesu 5:18-19...18.**Ẹ má sí ṣe mú wáìnì ní àmupara, nínú èyí tí rúdurúdu wà; ṣùgbọ́n ẹ kún fún Ẹ̀mí Mímọ́. 19. Ẹ sì máa bá ara yín sọ̀rọ̀ nínú Sáàmù, àti orin ìyìn, atí orin ẹ̀mí, ẹ máa kọrin, kí ẹ sì máa kọrìn dídùn ní ọkàn yín sí Olúwa.
**Kolose 3:16...**Ẹ jẹ́ kí ọ̀rọ̀ Kírísítì máa gbé inú yín lí ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú ọgbọ́n gbogbo; kí ẹ sì máa gba ara yín, níyànjú nínú Sáàmù, àti orin ìyìn, àti orin ẹ̀mí, ẹ máa fi oore ọ̀fẹ́ kọrin ní ọkàn yín sí Olúwa

---

**Kíyèsí:** ese àádọ́talénírínwó lo wa ninu ti o fi idi orin kiko, ilu ati ijo mule ninu Bíbélì Sugbon a ko se akosile irufe eyi ninu Kùránì.

## 151.

Ni titele ife ati ohun ti Ọlọ́run ní lọ́kàn,Se o tona fun ènìyàn lati ni ju iyawo kan lo nigba kan naa?

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Diutaronomi 17:17...**Kò gbọdọ̀ kó aya jọ, kí ọkàn rẹ̀ má bàá yapa kúrò. Kò gbọdọ̀ kó fàdákà àti wúrà jọ fún ara rẹ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀.

**1 Kọrinti 7:2..**Ṣùgbọ́n nítorí àgbèrè pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ̀ kí ọkùnrin kọ̀ọ̀kan gbéyàwó tirẹ̀. Bẹ́ẹ̀ni kí obìnrin kọ̀ọ̀kan ní ọkọ tirẹ̀.

---

**Nisa 4:3-5 & 24...**3. Bi eyin ba nberu pe e ki yio le se dede nipa omo-orukan nje e fe eyiti i ba dara niti yin ninu awon obinrin meji tabi meta tabi merin...24. Atipe a se ni ewo fun nyin awon abileko ninu nawon obinrin ayafi eyiti owo otun yin kappa...

**Ahzab 33:21, 32-33, 38 & 50...3**3.Dajudaju ikose rere mbe fun nyin lara Ojise Olohun..32. Enyin iyawo Annabi..Ko si laifi fun Annabi nipa ohun ti Olohun se ni eto fun u..50.ati obinrin ti o je onigbagbo ododo, ti o ba fi ara re fun Annabi,ti Annabi ba fe lati fe e. O sa lesa fun o laije ti awon onigbagbo ododo...

## 152.

**Se eniyan le baa won iyawo re lo daadaa lai re eyikeyi ninu won je ti o ba ni ju eyookan lo?.**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**Diutaronomi 21:15...**Bí ọkùnrin kan bá ní ìyàwó méjì, tí ó sì fẹ́ ọkan ṣùgbọ́n tí kò fẹ́ èkejì, tí àwọn méjèèjì sì bí àwọn ọmọkùnrin fún un ṣùgbọ́n tí àkọ́bí jẹ́ ọmọ ìyàwó rẹ̀ tí kò fẹ́ràn.

**Nehemaya 13:26-27...** 26 .Kìí ha á ṣe àwọn ìgbéyàwó bí irú èyí ni ọba Sólómónì fi dá ẹ̀ṣẹ̀? Láàrin àwọn orílẹ̀ èdè, kò sí ọba kan bí i tirẹ̀. Ọlọ́run rẹ̀ féràn rẹ̀, Ọlọ́run sì fi jẹ ọba lórí gbogbo Ísírẹ́lì, ṣùgbọ́n àwọn obìnrin àjòjì ti sọ ọ́ sínú òfin ẹ̀ṣẹ̀.

---

**Nisa 4:3...**Bi eyin ba nberu pe e ki yio le se dede nipa omo-orukan nje e fe eyiti i ba dara niti yin ninu awon obinrin meji tabi meta tabi merin, sugbon bi eyin ba n beru pe eki yio le se dede (larin won) nje e fe okansoso tabi eniti owo otun yin yio kappa ninu awon eru-binrin ti o wa ni ikapa nyin ti e ba fe won ki ise Oranyan fun yin sise dede larin won eyi ni o sunmo pe ki e mase se abosi.

**Nisa 4:129...**Enyin ki yio le ni agbara lati se dede larin awon obinrin biotilesepe enyin enyin nse ojukokoro (lati se be)...

# 153.

**Se a fi aye gba igbeyawo onígbà díẹ̀tabi igbeyawo fi idi he?(Mut'ah / òfin àwọn ìfẹ́ ọkàn)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Malaki 2:16...**"Mo kóríìra ìkọsílẹ̀," ni Olúwa Ọlọ́run Ísírẹ́lì wí, ni Olúwa Ọlọ́run Ísírẹ́lì wí, "bẹ́ẹ̀ni mo kóríra kí èníyàn máa fi ipá bó ara rẹ̀ àti pẹlú asọ rẹ̀," ni Olúwa àwọn ọmọ ogun wí. Nítorí náà ẹ sọ́ ẹ̀mí yín, kí ẹ má se hùwà ẹ̀tàn.

**1 Kọrinti 7:10-13**…..10.Àwọn ti ó ti gbéyàwó àti àwọn tí ó lọ́kọ, ni mo fẹ́pa á láṣẹ fún kì í ṣe láti ọ̀dọ̀mi ṣùgbọ́n láti ọ̀dọ̀Olúwa: "Obìnrin kò gbọdọ̀fi ọkọ rẹ̀ sílẹ̀." 11.Ṣùgbọ́n tí ó bá kúrò lọ́dọ̀ọkọ rẹ̀; jẹ́kí ó wà láìní ọkọ mọ́, bí bẹ́ẹ̀kọ́, kí ó padà sọ́dọ̀ọkọ rẹ̀ti ó fi sílẹ̀àti ọkùnrin pàápàá kò gbọdọ̀fi ìyàwó rẹ̀sílẹ̀. 12. ọkọ náà tí í ṣe onígbàgbọ́ kò gbọdọ̀kọ̀ọ́sílẹ̀. 13. Tí ó bá sì jẹ́obìnrin ló fẹ́ọkọ tí kò gbàgbọ́, ṣùgbọ́n tí ọkọ náà ń fẹ́kí obìnrin yìí dúró tí òun, aya náà kò gbọdọ̀kọ̀ọ́sílẹ̀.

---

**Nisa 4:24...**Ati (pe a se ni ewo fun nyin) awon abileko ninu awon obinrin ayafi ohun ti owo otun nyin kappa, ofin Olohun ni eyi lori nyin ase ni eto fun nyin ohun tin be leyin iwonyi, e wa won pelu dukia nyin, e fe won ni iyawo laise agbere (pelu won). Ko si ese fun nyin nipa ohun ti e jo yonu si leyin oranyan dajudaju Olohun je Olumo, Ologbon.

**Maide 5:87...**Eyin ti e gbagbo ni ododo, e ma se ni ewo awon ohun daradara ti Olorun se ni eto fun nyin atipe ki e ma koja enu ala, dajudaju Olohun ko feran awon olukoja- enu ala,

# 154.

**Se a fi oju wo àwọn obìnrin tabi ìyáwo bí ẹni pé nǹkan èlò fún ìbálòpọ̀, ohun tó ṣọ́wọ́n gan-an tabi ohun ini oko won ninu Ìwé mímọ́?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**2 Peteru 3:7...**Ṣùgbọ́n àwọn ọ̀run àti ayé, tí ó ń bẹ nísinsìnyìí, nípa ọ̀rọ̀kan náà ni ó ti tò jọ bí ìṣúra fún iná, a pa wọ́n mọ́de ọjọ́ìdájọ́àti ìparun àwọn aláìwà-bí-Ọlọ́run.

**Efesu 5:25...** Ẹyin ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́bí Kírísítì tí fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fí ara rẹ̀ fún-un

---

**Baqara 2:223** – Awon obinrin nyin oko ni won je fun niyin. E ma lo si oko nyin bi e ba ti fe…

**Al-i Imran 3:14...**ife igbadun ti awon obinrin ati awon omo ati owo pupo ni ti wura ati fadaka ati awn esin tin won ri itoju ati awon eran-osin ati oko.

## 155.

**Awon obinrin nyin oko ni won je fun niyin. E ma lo si oko nyin bi e ba ti fe… Awon obinrin nyin oko ni won je fun niyin. E ma lo si oko nyin bi e ba ti fe…**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 7:23...**A sì ti rá yín ní iyè kan, nítorí náà ẹ má ṣe di ẹrú ènìyàn.
**Tẹsalonika Kinni 4:3-7...**3.Nítorí ìfẹ́ Ọlọ́run ni pé kí ẹ jẹ́ mímọ́, kí ẹ sì yàgò kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ àgbérè, 4. kí ẹnikọ̀ọ̀kan yín kọ́ láti sàkóso ara rẹ̀ ní ọ̀nà mímọ́ àti pẹ̀lú ọlá, 5. kì í ṣe ní ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ gẹ́gẹ́ bí àwọn aláìkọlà, ẹni tí kò mọ Ọlọ́run;

---

**Nisa 4:24...**Ati (pe a se ni ewo fun nyin) awon abileko ninu awon obinrin ayafi ohun ti owo otun yin kapa...
**Mü'minun 23:5-6...**5. Ati awon ti n so abe won. 6.Afi lodo awon aya won abi awon ti won fi owo otun nwon mu logun, nitorina nwon k ii se eni ebu.
**Ma'arij 70:22 & 29-30 ...**22. awon ti ma nkirun. 29...Ati awon eniti nso abe won. 30. Ayafi lodo awon iyawo won abi awon ti owo-otun nwon kappa (erubinrin won) nitorina awon k ii se eni ebu.

## 156.

**Se o ye ki awon obinrin ma a wà lábẹ́ ìbòjú ti won ko ba si ninu ile won?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 11:15...**Ṣùgbọ́n bí obìnrin bá ní irun gígún, ògo ni ó jẹ́ fùn un nítorí irun gígùn tí a fi fún un jẹ́ ìbòrí fún-ún
**Galatia 5:1...**Nítorí náà, ẹ dúró ṣinṣin nínú òmìnira náà èyí tí Kírísítì fi sọ wá di òmìnira, kí ẹ má sì ṣe tún fi ọrùn bọ̀ àjàgà ẹrú mọ́.
**Kolose 2:16...**Nítorí náà ẹ má ṣe jẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣe ìdájọ́ yín ní ti jíjẹ, tàbí ní ti mímu, tàbí ní ti ọjọ́ àṣẹ, tàbí oṣù titun, àtì ọjọ́ ìsinmi:

---

**Nur 24:30-31...**30. Ati ki o so fun awon olugbagbo ododo lobinrin pe ki awon na o ma...31. Ati ki nwon ma fi ibori nwon le ori ewu nwon ki won fib o igbaya ati orun won. Ati ki nwon ma se fi oso nwon han si ode aya fi fun awon oko nwon...
**Ahzab 33:59...**Ire Annabi, so fun awon iyawo re ati awon oinrin re ati awon olugbagbo ododo pe kin won je ki awon aso jalabu nwon o ma bale. E yini o dara lati le fi mo nwon yato. Ki nwon ma ba ma yo nwon lenu. Olohun je Alaforiji. Onike.

## 157.

**Se eto obinrin ba ti awon okunrin dogba?**

**Bibeli** **Bẹẹni / Rara** **Al-Qur'an**

**Diutaronomi 16:19...** Ẹ má ṣe yí ẹjọ́ po, ẹ kò sì gbọdọ̀ ṣe ojúṣàájú.
**2 Kronika 19:7...** 7. Ṣe ìdájọ́ pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́, nítorí pẹ̀lú Olúwa Ọlọ́run kò sí àìṣedéédéé tàbí ojúsàájú tàbí gbígba àbẹ̀tẹ́lẹ̀.”
**Romu 2:11...**Nítorí Olúwa kìí ṣe ojú ìsáájú ènìyàn.
**Galatia 2:6...** Ọlọ́run kò fi bí ẹnìkẹ́ni se rí se ìdájọ́ rẹ̀
**Galatia 3:28...**Kò le sí Júù tàbí Gíríkì, ẹrú tàbí òmìnira, ọkùnrin tàbí ọbìnrin nítorí pé ọ̀kan ni nínú Kírísítì Jésù.
**Jakọbu 2:9...**Ṣùgbọ́n bí ẹ̀yin bá ń ṣe ojúsáájú ènìyàn, ẹ̀yin ń dẹ́ṣẹ̀, a sì ń dá yín lẹ́bi nípa òfin bí arúfin.

---

**Bakara 2:228 & 282...**228 o wa fun awon obinrin lori oko iru oun ti o wa fun awon okunrin lori won pelu dada sugbon ajulo si mbe fun awon okunrin lori won. 282...ki e sip e awon eleri meji ninu awon okunrin yin ki won jeri s ii, sugbon bi e ko ba ri okunrin meji ki e wa okunrin kan ati obinrin meji ninu awon ti e fe...
**Nisa 4:3,11...**3.Nje e fe eyiti o bara dara niti yin ninu awon obinbrin meji tabi meta tabi merin… 11.okunrin yio ma ni ipin obinrin meji...

## 158.

**Se a fi aye gba ki okunrin na iyawo re?**

**Bibeli** **Rara / Bẹẹni** **Al-Qur'an**

**Efesu 5:25-29...**25. Ẹ̀yín ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́ bí Kírísítì tí fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fí ara rẹ̀ fún-un. 29.Nítorí kò sì ẹnìkan tí ó ti kóríra ara rẹ̀; bí kò ṣe pé kí ó máa bọ́ ọ kí ó sì máa sìkẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Kírísítì sì ti ń ṣe sí ìjọ
**Kolose 3:19...**Ẹ̀yin ọkọ, ẹ máa fẹ́ràn àwọn aya yín, ẹ má sì ṣe korò sí wọn.
**2 Peteru 3:7...**Ṣùgbọ́n àwọn ọ̀run àti ayé, tí ó ń bẹ nísinsìnyìí, nípa ọ̀rọ̀ kan náà ni ó ti tò jọ bí ìṣúra fún iná, a pa wọ́n mọ́ de ọjọ́ ìdájọ́ àti ìparun àwọn aláìwà-bí-Ọlọ́run.

---

**Nisa 4:34.....** ati awon ti e nberu sise orikunkun won e se kilikilo fun WON e takete si ibusun won ki e si lu won;

## 159.

**Se a fi aye gba ki Kristeni tabi Musulumi fe elesin oto?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Diutaronomi 7:3-4...**Ẹyin kò gbọdọ̀ bá wọn dá àna. Àwọn ọmọbìnrin yín kò gbọdọ̀ fẹ́ àwọn ọmọkùnrin wọn, bẹ́ẹ̀ ni ẹ kò gbọdọ̀ fẹ́ àwọn ọmọbìnrin wọn fún àwọn ọmọkùnrin yín, 4. torí pé wọn á yí àwọn ọmọ yín padà kúrò lẹ́yìn mi, láti jẹ́ kí wọn máa sin òrìṣà, ìbínú Olúwa yóò sì wá sórí yín, yóò sì run yín kíákíá.
**1 Kọrinti 7:28 & 39...**28.Ṣùgbọ́n bí ìwọ bá gbé ìyàwó ìwọ kò dẹ́ṣẹ̀, bí a bá gbé wúndíá ní ìyàwó òun kò dẹ́ṣẹ̀. Ṣùgbọ́n irú àwọn tí ó bá gbé ìyàwó yóò dojú kọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà nípa ti ara: ṣùgbọ́n mo dá a yín sí. 39. A fi òfin dé obìnrin níwọ̀n ìgbà tí òun pẹ̀lú ọkọ rẹ̀ wà láàyè, bí ọkọ rẹ̀ bá kú, ó ní òmìnira láti ṣe ìgbéyàwó pẹ̀lú ọkùnrin mìíràn, tí ó bá wù ú ó sì gbọdọ̀ jẹ́ ti Olúwa.
**2 Kọrinti 6:14 & 17...**14. Ẹ má ṣe fí àìdọ́gba dàpọ̀ pẹ̀lú àwọn aláìgbàgbọ́: nítorí idápọ̀ kín ni òdodo ní pẹ̀lú àìṣòdodo? Ìdápọ̀ kín ni ìmọ́lẹ̀ sì ní pẹ̀lú òkùnkùn? 17. "Nítorí náà ẹ jáde kúrò láàárin wọn, kí ẹ sì yá ara yín si ọ̀tọ̀, ni Olúwa wí. Ki ẹ má ṣe fi ọwọ kan ohun àìmọ́; Èmi ó sì gbà yín."

---

**Maide 5:5...**Loni yi ase ni eto fun nyin gbogbo ohun ti o dara...Ati awon obinrin omoluabi ninu awon onigbagbo ododo ati awon obinrin omoluabi ninu awon ti a ti fun ni tira siwaju nyin, nigbati e ba ti fun won ni owo ife won...

## 160.

**Ti eniyan ba ko oko tabi iyawo re sile fun idi miran ti o yato si Agbere, se aye wa fun lati fe elomiran?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 5:32...**Ṣùgbọ́n mo wí fún yín pé, ẹnikẹ́ni tí ó bá kọ aya rẹ̀, àfi nítorí àgbèrè, mú un se àgbèrè, ẹnikẹ́ni tí ó bá sì fẹ́ obìnrin tí a kọ̀ sílẹ̀ ní ìyàwó ṣe àgbèrè.
**Matiu 19:3-9...**Mo sọ èyí fún yín pé, ẹni tí ó bá kọ aya rẹ̀ sílẹ̀, láìṣe pé nítorí àgbèrè, tí ó sì fẹ́ òmíràn, ó ṣe panṣágà."

---

**Bakara 2:231...**nigbati e ba ko obinrin sile... e ju won sile pelu dada...
**Tahrim 66:5...**O le je pe Oluwa re yio fi ropo fun u awon obbinrin miran ti o dara ju yin lo. Ti o (Annabi) ba ko yin sile… awon adelebo ati wundia.

# 161.

**Se ohun isin ni pe ki Kristeni ma huwa bi Kristi, ki Musulumi sim aa huwa bi Hz. Muhammed?**

Bibeli **Bẹẹni / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 10:24-25...**"Akẹ́kọ̀ọ́ kì í ju olùkọ́ rẹ̀ lọ, bẹ́ẹ̀ ni ọmọ-ọ̀dọ̀ kì í ju ọ̀gá rẹ̀ lọ. 25. Ó tọ́ fún akẹ́kọ̀ọ́ láti dà bí olùkọ́ rẹ̀ àti fún ọmọ-ọ̀dọ̀ láti rí bí ọ̀gá rẹ̀. Nígbà tí wọ́n bá pe baálé ilé ní Béélísébúbù, mélòó mélòó ni ti àwọn ènìyàn ilé rẹ̀!
**Luku 6:40...**Ẹni tí a ń kọ́ kì í ju olùkọ́ rẹ̀ lọ: ṣùgbọ́n olúkúlùkù ẹni tí ó ba pé, yóò dàbí olùkọ́ rẹ̀.
**Johanu 14:15 & 23-24...15.**"Bí ẹ̀yin bá fẹ́ràn mi, ẹ ó pa òfin mi mọ́. 23 Jésù dáhùn ó sì wí fún un pé, "Bí ẹnìkan bá fẹ́ràn mi, yóò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́; Baba mi yóò sì fẹ́ràn rẹ, àwa ó sì tọ̀ ọ́ wá, a ó sì ṣe ibùgbé wa pẹ̀lú rẹ̀. 24. Ẹni tí kò fẹ́ràn mi ni kò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́; ọ̀rọ̀ tí ẹ̀yin ń gbọ́ kì í ṣe ti èmi, ṣùgbọ́n ti Baba tí ó rán mi.

---

**Al-i İmran 3:31...**Wipe: bi eyin ba je eniti o feran Olorun, e tele mi, Olohun yio feran yin, yio si fi ori awon ese nyn jin yin...
**Nisa 4:80...**Enikeni ti o ba tele ti Ojise na, lotito o ti tele ti Olohun...
**Ahzab 33:21...**Dajudaju ikose rere mbe fun yin lara Olohun fun eniti o beru Olohun...
**Zukhruf 43:63...**(Annabi) Isa... e beru Olohun ki ne si tele mi...
ọ̀tá ati Ogun

# 162.

**Nje a se awari kókó pàtàkì ninu awon tó wà nínú àwọn Ìwé mímọ́ ti o soro nipa pe ki esin kan ni iwoye pe awon yio joba le gbogbo esin ti o ku?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Luku 17:20-21...**20"Ìjọba Ọlọ́run kì í wá pẹ̀lú àmì: 21Bẹ́ẹ̀ ni wọn kì yóò wí pé, 'Kíyèsí i níhìn ín!' tàbí 'Kíyèsí i lọ́hùn ún ni!' sáà wòó, ìjọba Ọlọ́run ń bẹ nínú yín."
**Romu 14:17 & 22...**17. Nítorí náà, mo ní ìsògo nínú Kírísítì Jésù nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́ mi fún Ọlọ́run. 22. Ìdí nì yìí tí ààyè fi há pẹ́ tó bẹ́ẹ̀ fún mi kí n tó wa bẹ̀ yín wò.
Pọ́ọ̀lù Pinnu Láti Dé Rómù

---

**Tevbe 9:33...**On ni eniti o ran Ojise Re pelu ona mimo ati esin ododo lati fi bori gbogbo esin pata…
**Saf 61:8-9...8.** Olohun yio sip e imole Re biofe bi awon alaigbagbo ko. 9. On Olorun ni eniti o ran iranse re pelu itonisona ati esin ododo, ki o le fi bori gbogbo esin miran...

## 163.

**Se o ye ki a fi ìyà jẹ àwọn tó máa n lo ipa tabi àfipáṣe ọrọ ẹsìn?**

Bibeli **Rara / Rara** Al-Qur'an

**2 Timothy 2:24-25...24.** Ìránṣẹ́ Olúwa kò sì gbọdọ̀ jà; bí kò ṣe kí ó jẹ́ ẹni pẹ̀lẹ́ sí ènìyàn gbogbo ẹni tí ó lè kọ́ni, onísùúrù. 25. Ẹni tí yóò máa kọ́ àwọn alátakò pẹ̀lú ìwà tútù, nítorí ìrètí pé Ọlọ́run lè fún wọn ní ìrònúpìwàdà sí ìmọ̀ òtítọ́

**Filemoni 14...**Kì í ha á ṣe ẹ̀mí tí ń jíṣẹ́ ni àwọn áńgẹ́lì í ṣe bí; tí a rán lọ síta láti máa sisẹ́ fún àwọn tí yóò jogún ìgbàlà?

---

**Bakara 2:256...**ko si ifi agbra mu ni ninu nesin...

**Al-i İmran 3:20...**ti nwon ba te ara won ba (fun Olohun) nje nigbana nwon tele ona tara, sugbon tin won ba yi pada nigbana iba ki o mu ise jije de opin ni tire.

**Kaf 50:45...**Dajudaju awon ti wa ninu irorun siwaju eyi

**Gasiye 88:21-22...**rara o, nigbati a ba mi ile ni mimi. 22.Atipe Oluwa re yio de, awon malaika yio si to ni tito.

## 164.

**Ṣe Ọlọ́run fún awon onigbagbo ni nísìírí pe ki won ja abi ko ogun ja awon ti o gba esin miran titi ti esin tiwon ba bori? (Ogun eniyan Mímọ́/ Jihadi)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Romu 12:17-19...**17.Ẹ má ṣe fi búburú san búburú fún ẹnikẹ́ni. Ẹ má pèsè ohun tí ó tọ́ níwájú gbogbo ènìyàn. 18Bí ó le ṣe, bí ó ti wà ní ipa ti yín, ẹ má wà ní àlàáfíà pẹ̀lú gbogbo ènìyàn. 19Olùfẹ́, ẹ má ṣe gbẹ̀san ara yín, ṣùgbọ́n ẹ fi ààyè sílẹ̀ fún ìbínú; nítorí a ti kọ ọ́ pé, Olúwa wí pé, "Èmi ni ẹsan, èmi ó gbẹ̀san."

**Heberu 12:14...**Ẹ ki gbogbo àwọn tí ń ṣe olórí yín, àti gbogbo àwọn ènìyàn mímọ́. Àwọn tí o ti Ítalì wá ki yín.

---

**Bakara 2:190-193...190.** ki e si ma ba (won ja) l'oju ona Olohun awon eniti o n ban yin ja... 191. Ki e si ma pa won nibikibi ti owo bnyin ba te won...idamu buru ju pipa lo. 193.ki e si ma ba won ja titi ti...esin yio wa (ni omninira) fun Olohun.

**Tevbe 9:29...**Eba awon ti won ko ni igbagbo si Olohun ati si ojo ikehun ja,ti nwon ko si se lewo ohun ti lohun ati Ojise re se lewo,

**Kíyèsí:** Jihadi je kókó to gbile ju ninu Kùránì:egberun mefa, ese mọkàndínlógóje ninu ese ẹẹdẹgbẹrún din ni metalelogun = eyokan ninu gbogbo ese meedinlaadota. ìpín mokanlelogun ni Hadith fi ko oro Jihadi jo. Sirah (Itan ibi Hz. Muhammed) fe to ìpín mẹtàdínláàádọ́rin Kùránì o si

## 165.

**Ti eniyan ba di apẹ̀yìndà kuro ninu esin ti a bi won si tabi mu ipinu lati se ìyípadà si esin miran se o ye fun pipa?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Heberu 3:12-13...**Ẹ kíyèsára, ará, kí ọkàn búburú ti àìgbàgbọ́má ṣe wà nínú ẹnikẹ́ni yín, ní lílọ kúrò lọ́dọ̀Ọlọ́run alàáyè. 13.Ṣùgbọ́n ẹ máa gba ara yín ní ìyànjú ní ojoojúmọ́, níwọ̀n ìgbà tí a bá ń pè ní "Òní," kí a má ba à sé ọkàn ẹnikẹni nínú yín le nípa ẹ̀tàn ẹ̀ṣẹ̀

---

**Nisa 4:89...**bi nwon ba si yipada (niti ija) emu won ki e sib a won ja ayekaye ti e ba ba won eko si gbodo mu ore ninu nwon ati oniranlowo

**Kíyèsí:** Àwọn àyọkà tó tẹ̀lé e yìí ti Hz. Muhammed so nipa awon apẹ̀yìndà kuro lodo Haditi Aposteli allah: "Enikeni ti o ba yípadà kuro ninu esin Ìsìláàmù e pa won". fi èyí hàn(Sahih Bukhari: Vol. 9, Book 84, Bẹ́ẹ̀ko. 57-58, Cf. Vol. 4, Book 56, Bẹ́ẹ̀ko. 808)

## 166.

**Se a se iwifun ni wipe ki a ba ebi ara ati ojulumo ja?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**1 Kọrinti 7:13-24..**13. Tí ó bá sì jẹ́obìnrin ló fẹ́ọkọ tí kò gbàgbọ́, ṣùgbọ́n tí ọkọ náà ń fẹ́kí obìnrin yìí dúró tí òun, aya náà kò gbọdọ̀kọ̀ọ́ sílẹ̀. 14.Nítorí pé ó ṣe é ṣe kí a lè mú ọkọ tí kò gba Kírísítì gbọ́súnmọ́Ọlọ́run nípa aya tí í ṣe onígbàgbọ́...16.Báwo ni ẹ̀yin aya ṣe mọ̀pé ẹ̀yin ni yóò gba ọkọ yín là? Bákan náà ni a lè wí nípa ọkọ tí í ṣe onígbàgbọ́pé, kò sí ìdánilójú pé aya aláìgbàgbọ́le yípadà láti di onígbàgbọ́nípa dídúró ti ọkọ.

---

**Mujadila 58:22...**ire ko ni ri awon eniyan ko ti won gba Olohun gbo lododo ati ojo igbehin tin won yio ni ife si eni ti o tako Olohunati Ojise Re bi o fe bi awon je awon baba won tabi awon omo won tabi awon arakunrin won tabi awon ibatan won...

**Taghabun 64:14...**Enyin ti e gbagbo lododo dajudaju ota yio ma be fun nyin ninu awon iyawo nyin ati awon omo nyin, nitorna ki e sora ni odo won…

## 167.

**Ṣe Ọlọ́run fẹ́ ki awon onigbagbo ode oni pa awon elomiran ti o n se ìgbàgbọ́ miran bi o tile je wipe eri okan o fi aaye gba won**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Ìṣe Àwọn Aposteli 24:16...**Nínú èyí ni èmi sì ti ń gbìyànjú láti ní ẹ̀rí-ọkàn tí kò lẹ́ṣẹ̀ sí Ọlọ́run, àti sí ènìyàn nígbà gbogbo.
**1 Timoti 1:5...** Ète àṣẹ náà ni ìfẹ́ ti ń jáde wá láti inú ọkàn mímọ́ àti ẹ̀rí-ọkàn rere àti ìgbàgbọ́ àìṣẹ̀tàn.

---

**Bakara 2:216...**A pa ogun jija ni ase fun yin, sugbon o je ohun ti e korira. Beni o le je pee yin korira nkankan ti nkan na yio si je ore fu yin;
**Enfal 8:17...**nidi eyi eyin ko pa won sugbon Olorun lo pa won, ire ko ni o soko sugbon Olohun ni O soko ati ki O le bad a awon onigbagbo ododo wo ni adanwo ti o dara lati odo e.
**Note:** Cf. Haditi, Sahih Muslim, 4661-4662, Ch. 789.

## 168.

**Se jija ati wiwo iya ija pelu awon elesin miran je nnkan rere?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Galatia 5:19-21...** Ǹjẹ̀ àwọn iṣẹ́ tí ara farahàn, tíí ṣe wọ̀nyí… ìkórìra, ìjà, ìlara, ìbínú, ìmọtara-ẹni nìkan, ìyapa, ẹ̀kọ́-òdí. 21. Àrankan, ìpànìyàn, ìmutípara, ìréde-òru, àti irú ìwọ̀nyí; àwọn ohun tí mo ń wí fún yín tẹ́lẹ̀, gẹ́gẹ́ bí mo ti wí fún yín tẹ́lẹ̀ rí pé, àwọn tí ń ṣe nǹkan báwọ̀nyí kì yóò jogún ìjọba Ọlọ́run.
**Jakọbu 4:2 & 8.....** Ẹ̀yin ń fẹ́ ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́, ẹ kò sì ní: ẹ̀yin ń pànìyàn, ẹ sì ń ṣe ìlara, ẹ kò sì le ní: ẹ̀yin ń jà, ẹ̀yin sì ń jagun; ẹ kò ní, nítorí tí ẹ̀yin kò béèrè. 8.Ẹ súnmọ́ Ọlọ́run, òun ó sì súnmọ́ yín. Ẹ wẹ ọwọ́ yín mọ́, ẹ̀yin ẹlẹ́ṣẹ̀; ẹ sì ṣe ọkàn yín ní mímọ́, ẹ̀yin oníyèméjì

---

**Tebve 9:41...**E ma lo pelu idira niwon iba ati iba lekun, ki e si ma sa agbara pelu oro nyin ati ara nyin pelu si oju ona ti Olohun. Eyi lo dara fun nyin ju bi eyin ba je eni ti o mo.
**Ankebut 29:6....**Atipe enikeni ti o ba gbiyanju, dajudaju o giyanju fun ara re. Dajudaju Olohun ti roro tayo gbogbo eda.
**Saf 61:11...**(On ni pe) ki eyin gba Olohun gbo ni ododo ati Ojise Re, ki eyin si gbiyanju si oju ona Olohun pelu owo nyin ati emi nyin. Awonyi dara ju fun nyin tie yin ba je eni ti o mo be.

## 169.

**Ǹjẹ́ Ọlọ́run fún Hz. Muhammed ní ìṣírí pe ki o bere opolopo ogun tó fọwọ́ ara rẹ̀ fà lati le tan ẹ́sìn Ìsìláàmù ka**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Johanu 18:36...** Jésù dáhùn wí pé, "Ìjọba mi kì í ṣe ti ayé yìí: ìbáṣe pé ìjọba mi jẹ́ ti ayé yìí, àwọn ìránṣẹ́ mi ìbá jà, kí a má baà fi mí lé àwọn Júù lọ́wọ́: ṣùgbọ́n nísinsin yìí ìjọba mi kì í ṣe láti ìhín lọ."

**2 Kọrinti 10:3-5...**Nítorí pé, bí àwa tilẹ̀ rìn nípa ti ara, ṣùgbọ́n àwa kò jagun nípa ti ara. 4. Nítorí ohun ìjà wa kì í ṣe ti ara...

---

1 Ìjà ogun **Badri** : (March 624)
Al-i İmran 3:13 ati 123; Anfâl 8:5-19 ati 41-44
2. Ìjà ogun **Uhud**: (March 625)
Al-i İmran 3:121-122, 3:140 ati 165-172
3. Ìjà ogun **Hendek**: (May 627) The Trench
Ahzab 33:9-12 ati 25-27
4. Ìjà ogun **Hudeybiye**: (March 628)
Fetih 48:1-3 ati 22-27
5. Ìjà ogun **Muta**: (629) Baqara 2:191-193
6. Ìjà ogun **Hunayn**: (August 630)
Tevbe 9:25-27
7. Ìjà ogun **Tebük**: (630) Tevbe 9:38-40, 42-52, 65-66, 81-83, 86-87,90, 93, 117
8. Ìjà ogun **Mekka**: (630) Tevbe 9:12, Kasas 28:85, Saf 61:13, Nasr, 110:1-3.

## 170.

**Nínú Ìwé mímọ́se a fi owo si biba awon eniyan inu iwe mimo ja?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Romu 12:18...**Bí ó le ṣe, bí ó ti wà ní ipa ti yín, ẹ má wà ní àlàáfíà pẹ̀lú gbogbo ènìyàn.

---

**Tevbe 9:29....**E ba awon tin won ko ni igbagbo si Olorun ati si ojo ikehin ja, tin won ko si se lewo ohun ti Olohun ati Ojise re se lewo, ti nwon ko si sin esin ododo ninu awon ti a ti fun ni tira titi nwon yio fi san owo ori lati owo won nwon si di kekere.

**Ahzab 33:26..**(Olohun) O mu awon eniti o ran won lowo ninu awon onitira sokale kuro ninu odi won O so owariri sinu awon okan won; ti e fin pa apakan ninu won e si mu apakan (won) leru

## 171.

**Se a fún awa onigbagbo ode oni níṣìírí lati koju awon ti ki se onigbagbo niogun ati ija kòbákùngbé ati ìmúnibínú? (Jihadi)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Efesu 6:12...**nitoripe ki ise eje ati eran-ara li awa mba jijakadi, sugbon awon olola, awon alase ibi okunkun aiye yi, ati awon emi buburu ni oju orun.
**1 Timoti 2:1-2...**1. Nitorina mo gba nyin niyanju saju ohun gbogbo....2.ki a le ma lo aiye wa ni idakeje ati pepe ninu gbogbo iwa-bi-Olorun aati iwa agba.

---

**Nisa 4:76-77...**76.Awon tin won gbagbo jna ti oju ona ti OLohun...77...sugbon nigbati ase ogunjija ni oranyan le won lori, nigbana...Oluwa wa; ese ti o fi se ogun jija ni oranyan lewa lori? Ese ti ire ko lo wa lara di igba die kan? Wipe; igbadun aiye na die ni, (ojo) ikehin ni o dara fun eniti o nberu
**Kíyèsí:**Egberun mefa, ese mọkàndínlógóje ninu ese ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rún din ni metalelogun = eyokan ninu gbogbo ese meedinlaadota. ìpín mokanlelogun ni Hadith fi ko oro Jihadi jo. Sirah (Itan ibi Hz. Muhammed) fe to ìpín mẹ́tàdínláààdọ́rin Kùránì o si! a se kiko eko nipa ogun Kòbákùngbé ninu Tevbe 9:29 ati 123.

## 172.

**Ǹjẹ́ Ọlọ́run gbà awọ́n onigbagbo ode oni ní yànjú lati kogun ati lati kery awon eniyaan ti o n se e ìgbàgbọ́ miran?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Jẹnẹsisi 14:23...**pe, emi ki yio mu lati fonran owu titi de ojun bata, ati pe, emi ki yio mu ohun kan ti ise tire, ki iwo ki o ma ba wipe, Mo so Abramu di oloro.
**Ẹkisodu 20:15 & 17...**15. Iwo ko gbodo jale. 17.Iwo ko gbodo sojukokoro si ile enikeji re, iwo ko gbodo sojukokoro si aya enikeji re.
**Efesu 4:28...**Ki eniti njale mase jale mo: sugbon ki o kuku ma se lala, ki o ma fi owo re sise ohun ti o dara, ki on ki o le ni lati pin fun eniti o se alaini.

---

**Enfal 8:1 & 41....**1. Nwon 0o bi o lere nipa awon ikogun (Anfali). Sope: Awon ikogun je ti Olohun ati ti Ojise (Re)..41. Ki e si mo ohunkohun ti e ba ko ni kogun ti Olohun ni idamarun re ati fun Ojise na..

## 173.

**Se Ọlọ́run fẹ́ ki awon onigbagbo ode oni lo eru tabi ohun lile fun awon ọ̀tá?**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Jeremaya 22:3...**Bayi li Oluwa wi; Mu idajo ati ododo se, ki o si gba eniti a lo lowo gba kuro lowo aninilara, ki o nmase fi agbara ati ika lo alejo, alainibaba ati opo, beni ki o mase ta eje alaise sile nihinyi.

**2 Timothy 2:24-25...**24. Irasnse Olorun ko si gbodo ja; bikose ki o je eni pele si enia gbogbo, eniti o le koni, onisuru. 25. Eniti yio ma ko awon asodi pelu iwa tutu; boya Olorun le fun won ni ironupiwada si imo otito.

---

**A'raf 7:4...**Melo-melo ni ilu ti Awa ti pare ti iya Wa si ti Wa bawon ni oru tabi nigbati nwon nsun oru osan.

**Enfal 8:12...**Emi yio ju eru-jeje sinu okan awon eni ti o se aigbagbo. Nitorina ema lu oke orun won ki e si ma lo gbogbo awon omo ika won.

**Enfal 8:67...**Ko to s Annabi kan pe ki imuni-leru logun ma be fun u, ayafi ti o ba ja titi yio fi segun l'ori-le yanyan.

## 174.

**Ǹjẹ́ Ọlọ́run fẹ́ ki awon onigbagbo ode oni ma a san ẹ̀san iṣẹ́? (ojú fún ojú ati eyín fún eyín/ Kısas)**

Bibeli **Rara / Bẹẹni** Al-Qur'an

**Matiu 5:39...**Sugbon emi wi fun nyin, E mase ko ibi;sugbon enikeni ti o ba gba o li ereke otun, yi ti osi s ii pelu.

**Romu 12:19-20...**19. Olufe, e ma se gbesan ara nyin, sugbon e fi aye sile fun ibinu; nitori ati ko o pe, Oluwa wipe, Temi lie san, emi o gbesan.

---

